# " Ẹ̀sìn Ìsìláàmù

Ti awọn ọrọ Kuraani ati Sunna ẹni ti o dara julọ nínú àwọn ẹ̀dá n ṣe àfihàn rẹ”
Akojọpọ
Fahd Bn Hamd Al-Mubaaraq
Ni Orukọ Allah, Ajọkẹ-aye, Aṣakẹ ọrun

# Ọrọ iṣaaju

“Iyin ni fun Ọlọhun, awa nyin In, awa n wa iranlọwọ Rẹ, awa n wa aforijin Rẹ, ati pe a n fi Ọlọhun wa iṣọ kuro nibi awọn aburu awọn ẹmi wa ati awọn aburu awọn iṣẹ wa. Ẹniti Ọlọhun ba fi mọ ọ̀nà, onitọun ni o mọna, ẹniti o ba si ṣi lọna, iwọ ko nii ri alaranṣe ati olutọsọna fun un, ati pe mo n jẹrii pe ko si ọlọhun kankan ti ijọsin ododo tọ si yatọ si Ọlọhun Allaah, mo si tun n jẹrii pe Muhammad ni ẹru Rẹ ati Ojiṣẹ Rẹ (ki ikẹ ati ọla Ọlọhun maa ba a ni ọpọlọpọ)."
lẹyin igba naa..
“Dájúdájú a n bukaata gidi gan ni ayé òde òní si tira ṣókí kan ti ko nii le ti o maa ṣe afihan ẹsin Islam pẹ̀lú bi o ṣe kún kẹ́kẹ́, boya nipa nǹkan ti o nii ṣe pẹ̀lú adisọkan ni, tabi ìjọsìn, tabi ìbáṣepọ̀, tabi ẹ̀kọ́, tabi nǹkan tí ó yàtọ̀ sí ìyẹn.” Ẹni tí ó bá n ka a yóò ni ikapa láti jẹ ki ìròrí tí ó hàn ti o kún ti o pe nípa Islam o sarajọ si i lọ́dọ̀. Ẹni tí ó bá wọ inú ẹsin Isilaamu yóò rí nínú rẹ̀ ibusẹrisi àkọ́kọ́ láti kọ́ àwọn ìdájọ́ àti àwọn ẹ̀kọ́ àti àwọn àṣẹ àti àwọn nǹkan tí wọ́n kọ̀. Tira yìí máa wa ni arọwọto àwọn olupepe si ti Ọlọhun, wọn máa tú u sí gbogbo èdè pátá, wọ́n máa fún gbogbo ẹni ti bá n béèrè nípa ẹsin Isilaamu, àti gbogbo ẹni tí ba n wọ inú rẹ̀, tí ẹni tí Ọlọhun ba fẹ́ kí ó mọ̀nà ti ara rẹ̀ mọ̀nà, tí ẹri ati jijiṣẹ máa dúró lórí àwọn ẹni anù.
Ṣaaju ki a to  bẹrẹ kikọ iwe yii, o jẹ dandan lati ṣe agbekalẹ awọn ojú-òpó ati awọn òfin ti onkọwe maa tẹle; lati le mu erongba ti o pàtàkì jù fun tira yii ṣẹ láti ipasẹ rẹ, a maa darukọ nínú rẹ̀ awọn ofin to n bọ yii:
Ki wọn ṣe àfihàn ẹsin yii nipasẹ awọn ọrọ inu Kuraani ati Sunna ti Anabi ti a ti sọ di mimọ, ki o ma ṣe jẹ́ nipasẹ awọn agbekalẹ eniyan, ati ọna àwọn onímọ̀ ọrọ-sisọ nibi ijiroro ati imudaniloju, ìyẹn nítorí ọpọlọpọ awọn nkan:
1."Pẹ̀lú gbigbọ ọrọ Ọlọhun ati agbọye ohun ti O gbalero, ẹni tí Ọlọhun ba fẹ fi mọ̀nà yóò mọ̀nà, ati pe ẹri maa dé ọdọ ẹni anu alagidi, gẹgẹ bi Ọba ti ọla Rẹ ga ṣe sọ pe: Tí ẹnì kan nínú àwọn ọ̀sẹbọ bá wá ètò ààbò wá sọ́dọ̀ rẹ, ṣ’ètò ààbò fún un títí ó fi máa gbọ́ ọ̀rọ̀ Allāhu. Lẹ́yìn náà, mú u dé àyè ìfọ̀kànbalẹ̀ rẹ̀. [At-Taobah:6]" O ṣe e ṣe ki ẹri ati imude-ogongo ma waye pẹ̀lú agbekalẹ abara, ati awọn ọna àwọn onimọ nípa ọrọ, èyí ti adinku and ààyẹ maa n ṣẹlẹ si.
Wipe Ọlọhun pa wa láṣẹ láti mu ẹsin Rẹ ati imisi Rẹ de ogongo gẹ́gẹ́ bí wọn ṣe sọ ọ kalẹ, ko sì pa wa láṣẹ ki a hun ojú ọ̀nà àwọn onimọ ọrọ-sisọ láti fi àwọn èèyàn mọ̀nà, ti a maa wa lérò pé a maa jèrè ọkàn àwọn èèyàn pẹ̀lú ẹ, kilode ti a fi n ko airoju ba ẹ̀mí ara wa pẹ̀lú nǹkan ti wọn o pa wa láṣẹ ki a ṣe, ti a wa n ṣẹri kúrò níbi nǹkan ti wọn pa wa láṣẹ ki a ṣe?
3- Wipe àwọn ọna ipepe mìíràn, gẹgẹ bii sisọrọ pupọ nipa yiyẹgẹrẹ àwọn alátakò ati fífún wọn ní esi, bóyá ni abala adisọkan ni tabi ìwà tabi ẹkọ tabi ìsúnná, tabi lílo iyàn-jíjà ti ìròrí, gẹ́gẹ́ bíi sisọrọ nípa fífi bibẹ Ọlọhun rinlẹ- Ọlọhun ga gan tayọ nǹkan tí àwọn alabosi n sọ-, tabi sisọrọ nípa àyípadà ti o n bẹ nínú Bíbélì, ati Taoreeta, ati awọn tira àwọn ẹsin mìíràn, ati ṣíṣe àlàyé títakora ati ibajẹ rẹ. "Gbogbo eyi dara lati jẹ ibuwọle si ṣíṣe àlàyé ibajẹ ti o wa ninu awọn ipilẹ ati adisọkan awọn alatako, ati pe o tun dara fun jijẹ ìpèsè ti aṣa ati ọlaju fun Musulumi- bi o ti lẹ jẹ pe àìní ìmọ̀ nípa rẹ ko ṣe ipalara fun un- ṣugbọn ko dara rara fun jijẹ ipilẹ ati aaye ibẹrẹ fun nnkan ti pipepe lọ si oju ọna Ọlọhun ma duro le lori."
4."Awọn ti wọn wọ inu Islam nipasẹ awọn ọna ti a ti daruko ṣáájú wọnyi, ko jẹ dandan fun wọn lati jẹ Musulumi ododo, o le jẹ pe ọkan ninu wọn wọ inu ẹsin yii nitori ìfẹ́ ti o ni si ọrọ kan pato ti wọn ṣàlàyé nípa rẹ̀ fun un, ati pe o le ma ni igbagbọ si àwọn ọ̀rọ̀ pataki miiran ninu awọn ọrọ ẹsin, gẹgẹ bii ẹnikan ti o nífẹ̀ẹ́ si- fun apẹẹrẹ- awọn ìròyìn ti ètò isuna Isilaamu fi tayọ, ṣugbọn ko ni igbagbọ ninu ilé ikẹyin, tabi ki o ma gbagbọ ninu bibẹ awọn alujannu ati awọn èṣù, ati bẹẹ bẹẹ lọ".
Iru iran yii ninu awọn eniyan, ipalara rẹ fun Islam ju anfaani rẹ lọ.
5- Alukuraani ni aṣẹ lori awọn ẹmi ati ọkan, nítorí náà ti wọn bá dá a dá wọn,  awọn ẹmi mimọ yoo da a lóhùn, wọn yóò sì goke ni awọn ọna igbagbọ ati ìpayà, kini o wa de ti wọn fi wá ń kọdí laarin rẹ ati wọn (àwọn ẹ̀mí?"
"ki awọn idapada èsì àti ìkìmọ́lẹ̀ ìṣesí, ati awọn àlàyé àkọsílẹ̀ ti o ṣáájú má dapọ mọ ṣíṣe àfihàn ẹsin yii, bi ko ṣe pe ki wọn ṣe afihan ẹsin yii bi o se sọkalẹ, ni ẹni tí n tẹle ilana rẹ nibi iba àwọn eeyan sọrọ, ati mímú wọn gòkè diẹdiẹ ni ojú ọ̀nà idurosinsin"
"Kí ó mọ̀ọ́mọ̀ jẹ ki ọ̀nà igbe-ọrọ-kalẹ o rọrùn nibi nǹkan kíkọ, ki o si ṣe e ni soki bi o ba ṣe ni ikapa mọ, ni ọna ti o fi maa rọrun lati gbe tira naa, ati lati maa pin in láàrin awọn eeyan"

Gbà pé a parí iṣẹ́ yìí, a wa túmọ̀ tira yii si èdè mìíràn, a wa tẹ̀ ẹ̀dà miliọnu mẹ́wàá jáde nínú ẹ, ki o wa dé ọwọ́ èèyàn mílíọ̀nù mẹ́wàá, kí ẹnikan péré nínú ọgọ́rùn-ún nínú wọn wá ní ìgbàgbọ́ sí àwọn aaya àti àwọn hadiisi ti ó wà nínú ẹ, kí mọ́kàndín-lọ́gọ́rùn-ún nínú ọgọ́rùn-ún wá ṣe aigbagbọ sí i, kí ẹnikan yii wa bá wa ni ẹni tí n paya, ti o fẹ ni ìgbàgbọ́ àti ìpayà, ǹjẹ́ o mọ̀- irẹ ọmọ-ìyá mi alapọn-ọnle- pé ẹnikan nínú ọgọ́rùn-ún yii n túmọ̀ sí pé èèyàn ẹgbẹ̀rún ní ọ̀nà ọgọ́rùn-ún ni wọn maa wọ inú Islām? “Láìsí iyè méjì, aṣeyọri nla ni eléyìí, ati pe ti Ọlọhun ba fi ẹnikan mọ̀nà nípasẹ̀ rẹ, o dara fun ọ ju awọn rakunmi pupa lọ.”
“Kódà, ti ko ba si ẹni kankan ninu awọn eniyan ti a pe yii ti o gbagbọ, ti gbogbo wọn si ṣẹri kuro níbi ẹsin yii, dajudaju àwa ti pé àmọ̀ọ́nà, a si ti jẹ́ iṣẹ tí Ọlọhun fi ran wa.
"Dajudaju iṣẹ awọn olupepe si ojú ọ̀nà Ọlọhun kii ṣe lati rí aridaju pé àwọn ènìyàn gba ẹsin yii, tabi - gẹ́gẹ́ bí Alukuraani ti mẹnu ba a- lati ṣojú kòkòrò fun itọsọna wọn". Tí o bá ń ṣojú kòkòrò sí ìmọ̀nà wọn, ẹni tí Allāhu bá ṣì lọ́nà, dájúdájú kò níí fi mọ̀nà, "(An-Nahl:37)" "Ṣugbọn ojúṣe wọn ti ipilẹ naa ni ojúṣe Anabi wọn- ki ikẹ ati ọla Ọlọhun maa ba a- ẹniti Oluwa rẹ  sọ fun un pe- Ọba ti O gbọnngbọn ti O ga-." Ìwọ Òjíṣẹ́, fi gbogbo ohun tí wọ́n sọ̀kalẹ̀ fún ọ láti ọ̀dọ̀ Olúwa rẹ jíṣẹ́. Tí o ò bá sì ṣe bẹ́ẹ̀, o ò jíṣẹ́ pé. Allāhu yó sì dáàbò bò ọ́ lọ́dọ̀ àwọn ènìyàn. Al-Maaidah 67
"A n beere lọwọ Ọlọhun ki gbogbo wa ni ifọwọsowọpọ lori imu ẹsin Ọlọrun de etígbọ̀ọ́ gbogbo eniyan patapata, ati pe ki O ṣe wa ni kọ́kọ́rọ́ fun oore, ati olupepe si i, ki O si tun ṣe wa ni àgádágodo fun aburú, ki a ṣi le dúró ṣinṣin ni iwaju rẹ, ati pe Ọlọhun ni O mọ julọ, ki ikẹ ati ọla Ọlọhun maa ba Anabi wa Muhammad."

## Olùkàwé mi ọ̀wọ́n:

"Iwe ti o wa ni iwaju rẹ yii,  yoo jẹ ki o mọ nipa ẹsin Islam ni ọna ti o rọrùn ti o kún kẹkẹ pẹlu gbogbo awọn abala rẹ (adisọkan- iwa - ofin - gbogbo awọn ẹkọ rẹ toku)."
"Mo sì ṣe akiyesi ọpọlọpọ awọn nkan ti o pàtàkì nínú ìyẹn:"
"Akọkọ: Ifojusi awọn ipilẹ ẹsin ti o dúró lé lórí."
"Ikeji: Ṣíṣe ọrọ ni soki bi agbara ti mọ."
"Ẹẹkẹta: Fifi Islam han nipasẹ awọn orisun ipilẹ rẹ (AluKuraani alapọn-ọnle, ati awọn hadiisi ojiṣẹ, ki ikẹ ati ọla Ọlọhun maa ba a), ni ọ̀nà tí ó jẹ pe olukawe yóò fi wa ni iwájú àwọn orísun ipilẹ Islām, ti yoo maa mu omi imọna rẹ àti ẹkọ rẹ láti inú rẹ̀ tààrà.
"Iwọ olukawe mi ọ̀wọ́n, wàá rí, lẹyin ti o ba ti de opin iwe naa, pe irori ti o hàn nípa Islām ti sarajọ si ọ lọ́dọ̀, lẹhin rẹ o le maa lekun síi nipa imọ nípa Islam díẹ̀ díẹ̀.
Iwe yii ti o wa ni iwájú rẹ kan àwọn eniyan pupọ, àwọn tí o kọkọ kàn gan ni àwọn tí wọ́n fẹ́ gba Islām, ti wọn si fẹ́ kọ nípa adisọkan rẹ, àti ẹkọ rẹ, ati ìdájọ́ rẹ.
"O tun kan àwọn tí wọ́n ní akolekan mimọ nípa àwọn ẹsin, pàápàá jùlọ àwọn ẹsin ti mílíọ̀nù ẹgbẹẹgbẹ̀rún èèyàn n ṣe. O tún kan àwọn ọrẹ Islām ti wọn n káàánú rẹ ti wọn si nífẹ̀ẹ́ sí àwọn ìròyìn rẹ kan. Bákan náà ni o tún kan àwọn ọ̀tá Islām tí wọn n gbógun ti i, àwọn tí o ṣe pé ó le jẹ pé àìní imọ wọn nípa rẹ ni ọkan nínú àwọn okùnfà pàtàkì fún igbogunti yii àti ìkórìíra yẹn.
Nínú àwọn ti iwe yìí kan gbọ̀ngbọ̀ngbọ̀n ni àwọn Musulumi ti wọn nífẹ̀ẹ́ si ṣíṣe àlàyé Islām fun àwọn èèyàn, iwe yii maa din wàhálà wọn ku, o si maa ṣe iṣẹ́ naa ni irọrun fun wọn.
"O lè rí, irẹ olukawe mi ọjọgbọ- tí o o ba ni irori tẹlẹ nipa ẹsin Islam- pé o nilo afọkansi díẹ̀, ati kika pẹ̀lú ifarabalẹ lati mọ awọn itumọ ti o wa ninu iwe yii; nítorí náà ma ṣe ìyọnu nípa ìyẹn, àwọn ìkànnì pọ ti o jẹ ti Islam ti yóò maa dáhùn àwọn ìbéèrè rẹ.

# 1- "Gbolohun imọ Allaahu ni ọ̀kan (laa ilaaha illa Allahu )"

Ipilẹ ti o pàtàkì fún ẹsin Isilaamu naa ni gbólóhùn (Laa Ilaaha Illaa Allah). Láìsí ipilẹ ti o le yìí, ilé Islām tí ó ga kò lè dúró, òun ni gbólóhùn àkọ́kọ́ ti o jẹ dandan fún ẹni tí o ba fẹ gba Islām ki o wí i lẹniti yóò ni adisọkan gbogbo ìtumọ̀ rẹ. Kini ìtumọ̀ "Laa Ilaaha Illaa Allah".
"Laa ilaaha illaa Allahu" n túmọ̀ si"
"Ko si adẹdaa kankan fun gbogbo nǹkan ti n bẹ àyàfi Allahu".
"kò sí olukapa kankan àti olùdarí kankan nínú ayé yii ayafi Ọlọhun.
Ko si olujọsin fun kankan ti o ni ẹtọ si ijọsin ododo ayafi Ọlọhun Ọba Allah.
Ọlọhun Ọba Allah ni O ṣẹda ile aye yii ti o fẹ ti o si rẹwa daadaa. O si da sanmọ pẹlu awọn irawọ rẹ ti o tobi, ati awọn irawọ ti n rin, ti o si n rin pẹlu eto ti o pé, ati kikuro loju kan rẹ ti o jọ ni loju, ko si ẹni kankan ti o le mu wọn duro ayafi Ọlọhun Ọba Allaah. O si tun da ilẹ pẹlu awọn oke rẹ, ati awọn afonifoji, awọn òkè ati awọn akeremọdo rẹ, pẹlu awọn igi ati awọn irúgbìn rẹ, pẹlu atẹgun ati awọn omi rẹ, bákannáà

pẹlu ilẹ ati ibudo rẹ, pẹlu oru ati ọsan rẹ, pẹlu ohun ti o n gbe lori rẹ ati ohun ti n rin l'ori rẹ. Ọlọhun Ọba Allaah da wọn, bakan naa o si tun mu wọn bẹ lati àìsí.
Ọlọhun Ọba Allaah ti O ga sọ ninu tira Rẹ pe: Àti pé òòrùn yóò máa rìn lọ sí àyè rẹ̀. Ìyẹn ni ètò (ti) Alágbára, Onímọ̀. Òṣùpá náà, A ti ṣe òdíwọ̀n àwọn ibùsọ̀ fún un (tí ó ti ma máa tóbi sí i) títí ó máa fi padà dà bíi ọ̀gọ́mọ̀ ọ̀pẹ t'ó ti pé. Kò yẹ fún òòrùn láti lo àsìkò òṣùpá. Kò sì yẹ fún alẹ́ láti lo àsìkò ọ̀sán. Ìkọ̀ọ̀kan wà ní òpópónà róbótó t'ó ń tọ̀. [Yaa'siin:38-40]
Àti pé ilẹ̀, A tẹ́ ẹ pẹrẹsẹ. A sì ju àwọn àpáta t'ó dúró gbagidi sínú rẹ̀. A sì mú oríṣiríṣi irúgbìn t'ó dára hù jáde láti inú rẹ̀. (Ó jẹ́) àríwòye àti ìrántí fún gbogbo ẹrúsìn tó ń ṣẹ́rí padà (síbi òdodo). A ń sọ omi ìbùkún kalẹ̀ láti sánmọ̀. A sì ń fi mú àwọn ọgbà oko àti àwọn èso tí wọ́n máa kájẹ hù jáde. (A tún mú) igi dàbínù hù ga, tí àwọn èso orí rẹ̀ so jìgbìnnì. [Qof: 7-10]
Eleyii ni ẹda Ọlọhun ti O gbọ-n-gbọn ti O si ga, O ṣe ilẹ ni ohun ti o duro ṣinṣin, O si fi sinu rẹ iroyin ati le fa nnkan mọra ni deedee odiwọn nnkan ti ṣiṣẹmi lori rẹ n bukaata si, ko nii lekun, ki ílọ-bíbọ̀ ma baa ṣòro lori rẹ, bákannáà ni ko si nii kere, ki awon alaaye ma baa fọnka kuro nibẹ, gbogbo nnkan si n bẹ lọdọ Rẹ pẹlu odiwọn.
O si sọ omi ti o mọ kalẹ lati sanmọ, ti ṣiṣẹmi o le wa ayafi pẹlu rẹ. A si ṣe gbogbo nnkan ni abẹmi lati inu omi. Al-Anbiyaa 30 O mu irugbin jade ati awọn eso lati inu rẹ, O si fun awọn ẹranko ati awọn eniyan ni omi mu lati inu rẹ, O si pèsè ilẹ lati da ààbò bo o. Ó sì mú omi náà bọ́ sínú àwọn òpópónà odò nínú ilẹ̀.
O si fi hu awọn ọgba oko ti o dara jade, pẹ̀lú awọn igi rẹ àti awọn ododo rẹ ati ẹwa rẹ ti n fa ni mọ́ra, Ọlọhun Ọba Allaah ni o ṣẹda gbogbo nnkan daadaa, O si bẹrẹ dida ẹda latari iyepẹ (amọ).
Eeyan akọkọ ti Ọlọhun Ọba Allaah da naa ni baba gbogbo abara tii ṣe Aadam (Ki alaafia Ọlọhun maa ba a), O da a latara erupẹ amọ, ti O si to (orikeerikee) ara rẹ dọgba, o wa ya aworan rẹ, O wa fẹ atẹgun si i latara ẹmi Rẹ, O si da iyawo rẹ latara rẹ, O wa ṣe awọn arọmọdọmọ rẹ lati ara ohun ti A mu jade lati ara omi lilẹ yẹpẹrẹ.
Ọlọhun ti ọla Rẹ ga sọ pe: Dájúdájú A ti ṣe ẹ̀dá ènìyàn láti inú ohun tí A mọ jáde láti inú erùpẹ̀ amọ̀. Lẹ́yìn náà, A ṣe é ní àtọ̀ sínú àyè ààbò (ìyẹn, ilé-ọmọ). Lẹ́yìn náà, A sọ àtọ̀ di ẹ̀jẹ̀ dídì. Lẹ́yìn náà, A sọ ẹ̀jẹ̀ dídì di báàṣí ẹran. Lẹ́yìn náà, A sọ báàṣí ẹran di eegun. Lẹ́yìn náà, A fi ẹran bo eegun. Lẹ́yìn náà, A sọ ọ́ di ẹ̀dá mìíràn.1 Nítorí náà, ìbùkún ni fún Allāhu, Ẹni t'Ó dára jùlọ nínú àwọn ẹlẹ́dàá (oníṣẹ́-ọnà).2 Suuratul Muh'minuun: 12-14.
Ọlọhun ti O mọ tun sọ pe : Ẹ sọ fún Mi nípa àtọ̀ tí ẹ̀ ń dà jáde (sínú àpòlùkẹ́), ṣé ẹ̀yin lẹ ṣẹ̀dá rẹ̀ ni tàbí Àwa l'A ṣẹ̀dá rẹ̀? Àwa l'A yan kádàrá (ọjọ́) ikú fún gbogbo yín. Àwa kò sì lè kágara láti fi irú yín pààrọ̀ yín, kí á sì tun yín dá sínú ohun tí ẹ kò mọ̀. [Al-Waaqiah 58-61]
Woye bi Ọlọhun ṣe da ọ, waa ri eemọ nibi awọn irinṣẹ ti o munadoko ati awọn ilana ti o pe ti o jẹ pe àwọn díẹ̀ gan ni wọn mọ̀ ọ́n, ka mai tii sọ pe wọn wa fẹ maa ṣe àkóso rẹ. Woye si irinṣẹ yii ti o pe perepere fun dídà ounjẹ, yóò oo bẹrẹ lati ibi ẹnu, ti yoo ge ounjẹ yii wẹlẹwẹlẹ lati le baa jẹ ki dida ounjẹ o rọrun, lẹyin igba naa ni yoo lọ sinu ọfun, lẹyin igba naa ni yoo ti okele ounjẹ naa sinu gogongo, tan-an-na ọfun o wa ṣilẹkun fun ọna ọfun, lẹyin eleyii ni yóò wa ti ilẹkun irinṣẹ ti o ngbe atẹgun wọle pa mọ́ ọn, lẹyin igba naa ni okele yii o wa lọ sinu ikun pẹlu iranlọwọ ọna ọfun ti n lọ ti n bọ̀ bii ìdin. Ninu ikun, iṣẹ dida ounjẹ a maa tẹ̀ síwájú, ti ounjẹ maa yira pada ni nǹkan sísàn, yoo wa ṣi ilẹkun fun un ninu ikun, yoo wa doju kọ ọna ìfun kékeré níbi ti dida ounjẹ o ti tẹ siwaju, eleyii tii ṣe yiyi awọn ohun elo latara ounjẹ padà si ohun elo ti yoo wa ni ìbámu ti yoo si dara fun pipese ounjẹ fun awọn sẹẹli ara. Lẹyin naa, lati ibẹ ni yoo ti lọ sinu ifun, nibi yii ni dida ounjẹ o ti pari patapata, ti ounjẹ o si di ohun nnkan ti ó ṣeé fà pẹlu iranlọwọ awọn fọ́nrán ti n bẹ nínú ìfun ki o le baa máa sàn pẹ̀lú sísàn ẹjẹ. Iyẹn ni irinṣẹ ti o pe perepere fún ṣíṣàn ẹjẹ, èyí ti o tàn ka sinu òpó ẹ̀jẹ̀ ti ó díjú, ti o ba jẹ pe o nà án jáde ni, gígùn rẹ kì bá lé ní ẹgbẹẹgbẹrun kilomita ti yóò sọ pọ̀ mọ ọkan, kii rẹ ẹ, kii si sú u láti máa gbé ẹjẹ kaakiiri ninu awọn òpó ẹ̀jẹ̀ yẹn.
Bákannáà ni irinṣẹ miran wa fun eemi, ẹlẹẹkẹrin si wa fun iṣan, ẹlẹẹkarun wa fun fifa awọn ẹgbin jáde kuro ninu ara, ẹlẹẹkẹfa, ẹlẹẹkeje ati ẹlẹẹkẹwa, eléyìí ti imọ wa o maa lekun nípa rẹ ni ojoojumọ, nǹkan ti a ko mọ nipa rẹ si pọ ju eleyii ti a mọ lọ. Tani ẹni naa ti o da awọn nnkan yii pẹlu pípé ti o yatọ si Ọlọhun Ọba Allaah.
Fun idi eleyii, ninu awọn ẹṣẹ ti o tobi julọ ni ayé ni ki o maa mu orogun pẹlu Ọlọhun Ọba Allaah, ti o si jẹ pe Oun ni O da ọ.
Gbéra sọ pẹlu ọkan ti o ṣi silẹ, ati ẹ̀mí ti o mọ, ki o wa woye si iṣẹ Ọlọhun Ọba Allaah ti o rẹwa, woye si atẹgun ti o n fa simu, ti o si n yọ wọle si ẹ lára ni gbogbo àyè, láìní awọ kankan ti o le ko ìdààmú ba ojú, ti awọn nnkan yii ba fi le lọ da iṣẹ duro fun ìṣẹ́jú perete, waa jáde láyé. Omi ti o n mu yii, ounjẹ ti o n jẹ ati eeyan yii ti o nífẹ̀ẹ́ si, ati ilẹ ti o n rin lori rẹ yii, ati sanmọ ti o n wo, gbogbo ohun ti oju rẹ n ri ati awọn ti ko ri ninu awọn ẹda ti o tobi tabi ti o kere, gbogbo wọn yii ni wọn wa ninu ẹda Ọlọhun, Ọba Adẹdaa, Ọba Onimimọ.

Dajudaju mimaa ronu nipa awọn ẹda Ọlọhun, yoo maa mu wa mọ titobi Ọlọhun ati ikapa Rẹ. Ninu awọn eeyan ti agọ̀ wọn ati aimọkan wọn ati sisọnu wọn tóbi jù ni gbogbo ẹniti o n ri ẹda Ọlọhun yii ti o rẹwà, ti o tobi, ti o bára mu, ti o pé, ti o n tọka si ọgbọn ńlá ati ikapa ti ko ni ààlà, lẹyin igba naa, ko tun wa ni ni igbagbọ si Ọba Adẹdaa ti O mu u bẹ láti ibi aisi. Ọlọhun ti ọla Rẹ ga julọ sọ pe: Tàbí wọ́n ṣẹ̀dá wọn láì sí Aṣẹ̀dá? Tàbí àwọn ni wọ́n ṣẹ̀dá ara wọn ni? Tàbí àwọn ni wọ́n ṣẹ̀dá àwọn sánmọ̀ àti ilẹ̀? Rárá o, wọn kò màmọ̀ dájú ni. [At-Toor 35-36]

Dajudaju Ọlọhun Ọba ti O mọ ti O si ga, adamọ ti o ni alaafia mọ Ọn lai bukaata si kíkọ́, O ti jẹ́ ki dida oju kọ Ọ́ àti sisadi I maa bẹ nínú bi O ṣe ṣe adamọ, ṣùgbọ́n wọn maa n ṣì í (adamọ) lọ́nà, wọn si maa n mu u jìnà si I (Ọlọhun).

Fun idi eleyii, ti ajalu kan ba ṣẹlẹ si i, ati ajakalẹ arun, tabi inira ti o le, tabi ibanujẹ, tabi o dojukọ awọn ewu ti o rọgba yi i ka lori ilẹ ati lori omi, kíá ni yoo ṣẹri pada lọ si ọdọ Rẹ, ti yoo si maa wa iranlọwọ Rẹ ati bi yóò ṣe bọ́ kuro ninu ohun ti o wa ninu rẹ, Ọlọhun Ọba Allaah si maa n gbọ adua ẹniti o ba wa ninu inira nigba ti o ba pe E, Yóò si ka aburu kuro fun un.

Ọlọhun Aṣẹda ti O tobi yii tobi ju gbogbo nnkan lọ, ko si si nnkankan ti wọn le fi ṣe oṣuwọn Rẹ nínú àwọn ẹ̀dá Rẹ. Oun ni O tobi ti ko si si ààlà fun titobi Rẹ, ko si si ẹni kankan ti imọ rẹ le kari Rẹ, Oun ni Ẹni ti wọn n royin pẹlu iroyin giga lori awọn ẹda Rẹ loke sanmọ Rẹ. Kò sí kiní kan bí irú Rẹ̀. Òun sì ni Olùgbọ́, Olùríran. Suuratu Shuuroh: 11. Nkankan o le ṣe deedee Rẹ nínú àwọn ẹda Rẹ, nǹkan ti o ba wa si ọ lọ́kàn nipa Rẹ, Ọlọhun Ọba Allaah ko ri bẹẹ.

Ọlọhun n rí wa lati òkè àwọn sanmọ Rẹ, awa o si ri I. Àwọn ojú (ẹ̀dá) kò lè ká Allāhu. Òun sì ká àwọn ojú. Òun sì ni Aláàánú, Alámọ̀tán. [Al-An'am, 103] "Bi ko ṣe wípé àwọn ẹ̀yà ara wa ti a fi n ní ìmọ̀lára àti agbára wa ko leè gbé kí á rí I ni ayé yìí

Ọ̀kan nínú àwọn Anọbi Ọlọhun tii ṣe Musa- ki ọlà máa bá a- ti béèrè fún nǹkan yẹn nígbà tí Ọlọhun ba a sọ̀rọ̀ nibi òkè Tuur, ó sọ pé Ìwọ Olúwa mi, jẹ́ ki n rí Ọ, Ọlọhun ti ọla Rẹ ga sọ fun un pé: “Ìwọ kò lè rí Mi. Ṣùgbọ́n wo àpáta (yìí), tí ó bá dúró ṣinṣin sí àyè rẹ̀, láìpẹ́ o máa rí Mi.” Nígbà tí Olúwa rẹ̀ sì (rọra) fi ara Rẹ̀ han àpáta, Ó sọ ọ́ di pẹ̀tẹ́lẹ̀. (Ànábì) Mūsā sì ṣubú lulẹ̀, ó dákú. Nígbà tí ó tají, ó sọ pé: “Mímọ́ ni fún Ọ, èmi ronú pìwàdà sí ọ̀dọ̀ Rẹ. Èmi sì ni àkọ́kọ́ àwọn onígbàgbọ́ òdodo (ní àsìkò tèmi.) [Al-A'raaf:143] "Òkè ńlá tí ó ga ṣubú ti o sì fọ́ pẹtẹpẹtẹ látàrí ìfarahàn Ọlọhun si i, báwo wá ni ọmọniyan ṣe fẹ́ kápá ìyẹn pẹ̀lú agbára rẹ tí ó lẹ

Nínú àwọn ìròyìn Ọlọhun ti ọla Rẹ ga ni pé Ó ní ikapa lórí gbogbo nǹkan (Àti pé kò sí kiní kan nínú àwọn sánmọ̀ àti ilẹ̀ tí ó lè mórí bọ́ lọ́wọ́ Allāhu). [Faatir:44]

Ọwọ Rẹ ni iṣẹmi àti ikú wà. Gbogbo ẹ̀dá pátá ni o n bukaata si I, Oun ni O rọrọ̀ kúrò lọ́dọ̀ gbogbo ẹ̀dá, Ọlọhun ti ọla Rẹ ga sọ pe: Ẹ̀yin ènìyàn, ẹ̀yin ni aláìní (tí ẹ ní bùkátà) sí Allāhu. Allāhu, Òun ni Ọlọ́rọ̀, Ọlọ́pẹ́. [Faatir:15]

Nínú àwọn ìròyìn Rẹ náà ni imọ tí ó rọkirika gbogbo nǹkan: Ọ̀dọ̀ Rẹ̀ sì ni àwọn kọ́kọ́rọ́ ìkọ̀kọ̀ wà. Kò sí ẹni t’ó nímọ̀ rẹ̀ àfi Òun. Ó nímọ̀ ohun tí ń bẹ nínú ilẹ̀ àti odò. Ewé kan kò sì níí já bọ́ àfi kí Ó nímọ̀ rẹ̀. Kò sì sí kóró èso kan nínú òkùnkùn (inú) ilẹ̀, kò sí ohun tútù tàbí gbígbẹ kan àfi kí ó wà nínú àkọsílẹ̀ t’ó yanjú. Suuratul An’aam: 59. O n mọ nǹkan ti ahọ́n wa n sọ, ati nǹkan tí àwọn oríkèé wa n ṣe, kódà títí tí ó fi dórí nǹkan ti o pamọ sínú àyà wa (Allāhu) mọ ojú ìjàǹbá àti ohun tí àwọn ọkàn fi pamọ́. [Gaafir:19]

Ọlọhun n rí wa, O si mọ nípa àwọn iṣesi wa, nkankan ko pamọ fun Un ni ilẹ̀ àti sanmọ, kii gbàgbé, kii sii sùn. Ọba ti ola Rẹ ga sọ pe: Allāhu, kò sí ọlọ́hun kan tí ìjọ́sìn tọ́ sí àfi Òun, Alààyè, Alámòjúútó-ẹ̀dá. Òògbé kì í ta Á. Àti pé oorun kì í kùn Ún. TiRẹ̀ ni ohunkóhun t’ó wà nínú àwọn sánmọ̀ àti ohunkóhun t’ó wà nínú ilẹ̀. Ta ni ẹni tí ó máa ṣìpẹ̀ lọ́dọ̀ Rẹ̀ àfi pẹ̀lú ìyọ̀nda Rẹ̀? Ó mọ ohun tí ń bẹ níwájú wọn àti ohun tí ń bẹ lẹ́yìn wọn. Wọn kò sì ní ìmọ̀ àmọ̀tán nípa kiní kan nínú ìmọ̀ Rẹ̀ àfi ohun tí Ó bá fẹ́ (fi mọ̀ wọ́n). Àga Rẹ̀ gbààyè ju àwọn sánmọ̀ àti ilẹ̀. Ṣíṣọ́ sánmọ̀ àti ilẹ̀ kò sì dá A lágara. Allāhu ga, Ó tóbi. Suuratul Baqorah: 255.

TiRẹ̀ ni àwọn ìròyìn pípé pọ́nńbélé

TiRẹ̀ ni àwọn orúkọ ti o dáa ju lọ àti àwọn ìròyìn ti o ga julọ. Ọlọhun ti ọla Rẹ ga sọ pe: Ti Allāhu ni àwọn orúkọ t’ó dára jùlọ. Nítorí náà, ẹ fi pè É. Kí ẹ sì pa àwọn t’ó ń yẹ̀ kúrò níbi àwọn orúkọ Rẹ̀ tì. A óò san wọ́n ní ẹ̀san ohun tí wọ́n ń ṣe níṣẹ́. [Al-A'raaf:180]

Ọlọhun- mimọ Rẹ- ko ni orogun nibi ọlá Rẹ, ko si ni akẹgbẹ, bẹ́ẹ̀ ni ko ni oluranlọwọ.

Ko ni aya, bẹ́ẹ̀ ni ko si ni ọmọ, ko sì ni bukaata si gbogbo ìyẹn, Ọlọhun ti ọla Rẹ ga sọ pe: Sọ pé: "Òun ni Allāhu, Ọ̀kan ṣoṣo. Allāhu ni Aṣíwájú (tí ẹ̀dá ní bùkátà sí, tí Òun kò sì ní bùkátà sí wọn). Kò bímọ. Wọn kò sì bí I. Kò sì sí ẹnì kan tí ó jọ Ọ́." Suuratul Ikhlaas: 1-4. Ọlọhun Ọba ti ọla Rẹ ga sọ pe: Wọ́n wí pé: "Àjọkẹ́-ayé fi ẹnì kan ṣe ọmọ." Dájúdájú ẹ ti mú ǹǹkan aburú wá. Àwọn sánmọ̀ fẹ́rẹ̀ fàya pẹ́rẹpẹ̀rẹ nítorí rẹ̀, ilẹ̀ fẹ́rẹ̀ fàya pẹ́rẹpẹ̀rẹ, àwọn àpáta sì fẹ́rẹ̀ dà wó lulẹ̀ gbì fún wí pé wọ́n pe ẹnì kan ní ọmọ Àjọkẹ́-ayé. Kò sì yẹ fún Àjọkẹ́-ayé láti fi ẹnì kan ṣe ọmọ. Kò sí ẹnì kan nínú àwọn sánmọ̀ àti ilẹ̀ àyàfi kí ó wá bá Àjọkẹ́-ayé ní ipò ẹrúsìn. Suuratu Maryam: 88-93.

Ọlọhun- mimọ Rẹ- ni ìròyìn gbigbọnngbọn àti ẹwà, àti agbára, àti motomoto, àti ọlá, àti jíjẹ gàba.
O tún ní ìròyìn titọrẹ ati aforijin ati aanu ati ṣíṣe dáadáa, Òun ni Ajọkẹ-aye tí ikẹ Rẹ gbòòrò ju gbogbo nǹkan lọ.
Ọba Àṣàkẹ́-ọ̀run ti ikẹ Rẹ ṣáájú ìbínú Rẹ
Ọba Ọlọrẹ ti ọrẹ títa Rẹ ko ni ààlà, ti ilé-ọrọ̀ Rẹ ko nii tán
Gbogbo orúkọ Rẹ pátá ni o dára julọ ti wọn n tọ́ka sí àwọn ìròyìn pípé pọnnbele tí ko lẹtọọ fún ẹnì kankan àyàfi Allāhu.
Mimọ àwọn ìròyìn Ọlọhun máa n jẹ ki ọkàn lekun ni ifẹ àti gbigbọnngbọn, àti ìpayà àti irẹlẹ fún Ọlọhun
Fun ìdí èyí, ìtumọ̀ LAA ILAAHA ILLAL'LOOH ni kí ó ma yi nǹkan kan nínú ijẹ-ẹru fun ẹni kankan àyàfi fún Ọlọhun, ko si ẹni ti a le maa jọ́sìn fún pẹ̀lú òdodo àyàfi Ọlọhun, Ọlọhun ni O ni ìròyìn Ẹni ti ìjọ́sìn tọ si àti ìròyìn pípé. Oun ni Adẹdaa, Olùpèsè ijẹ-imu, Ẹni ti n ṣe idẹra fúnni, Olùyeni, Olùpani, Ẹni tí Ó ní ọlá lórí ẹ̀dá Rẹ, Oun nìkan ṣoṣo ni Ó lẹtọọ si ìjọsìn, ko ni orogun.
Ẹni tí ó bá kọ jijọsin fun Ọlọhun silẹ, tàbí ó jọ́sìn fún nǹkan tí ó yàtọ̀ sí Ọlọhun, o ti ṣe ẹbọ, o si tun ti ṣe Kèfèrí
Iforikanlẹ, ati rirukuu, ati ìtẹríba, àti irun, gbogbo e maa jẹ ti Ọlọhun nìkan.
A kii wa ìgbàlà àyàfi pẹ̀lú Ọlọhun, a kii dojú adua kọ ẹni kankan ayafi Ọlọhun, a kii wa bukaata àyàfi ni ọdọ Ọlọhun, a kii sunmọ nǹkan kan pẹ̀lú èyíkéyìí asunmọ ati itẹle ati ijọsin ayafi Ọlọhun Sọ pé: "Dájúdájú ìrun mi, ẹran (pípa) mi, ìṣẹ̀mí ayé mi àti ikú mi ń jẹ́ ti Allāhu, Olúwa gbogbo ẹ̀dá. Kò sí akẹgbẹ́ fún Un. Ìyẹn ni Wọ́n pa láṣẹ fún mi. Èmi sì ni ẹni-àkọ́kọ́ àwọn mùsùlùmí (ní àsìkò tèmi)." [Al-An'aam:162,163]

# B- Kilode tí Ọlọhun fi dá wa?

Ìdáhùn si ìbéèrè ńlá yìí pàtàkì gan, ṣùgbọ́n o di dandan ki a mu ìdáhùn naa lati inú imisi ti ọ̀dọ̀ Ọlọhun. Ọlọhun ni O da wa, Oun naa ni O n fun wa ni iro nípa nǹkan ti O torí rẹ da wa. Ọlọhun ti O gbọnngbọn sọ pe: Àti pé Èmi kò ṣẹ̀dá àlùjànnú àti ènìyàn bí kò ṣe pé kí wọ́n lè jọ́sìn fún Mi. Suuratudh Dhāriyāt: 56. Jijẹ ẹrú jẹ ìròyìn ti o pa gbogbo àwọn ẹ̀dá Ọlọhun papọ, èyí tí kò ní onka, láti orí àwọn ẹ̀dá ti wọn niyi jù (àwọn Malaika) dórí àwọn ti wọn yàtọ̀ sí wọn ninu awọn eemọ ẹ̀dá Ọlọhun, wọn da gbogbo àwọn ìjọ yii lórí ìjẹ́ ẹrú àti ṣíṣe afọmọ fún Ọlọhun Olúwa àwọn ẹ̀dá. Àwọn sánmọ̀ méjèèje, ilẹ̀ àti àwọn tí wọ́n wà nínú wọn ń ṣe àfọ̀mọ́ fún Un. Kò sì sí kiní kan àfi kí ó ṣe àfọ̀mọ́ àti ìdúpẹ́ fún Un. Ṣùgbọ́n ẹ kò lè gbọ́ àgbọ́yé àfọ̀mọ́ wọn. [Al-Isroo':44] Wọn maa n mí ṣíṣe afọmọ sí àwọn Malaika, gẹgẹ bi wọn ṣe máa ń mí èémí sí àwọn ọmọ Anọbi Adam.
Ṣùgbọ́n ijẹ ẹrú ọmọniyan fún Ẹni tí Ó da a jẹ́ nǹkan ẹsa, kii ṣe tipá (nǹkan ẹsa ti o jẹ ti idanwo): Òun ni Ẹni tí Ó ṣẹ̀dá yín. Aláìgbàgbọ́ wà nínú yín. Onígbàgbọ́ òdodo sì wà nínú yín. Allāhu sì ni Olùríran nípa ohun tí ẹ̀ ń ṣe. [At-Tagoobun:2]
(Ṣé o ò rí i pé dájúdájú Allāhu ni àwọn t'ó ń bẹ nínú àwọn sánmọ̀ àti àwọn t'ó ń bẹ lórí ilẹ̀, àti òòrùn, òṣùpá, àwọn ìràwọ̀, àwọn àpáta, àwọn igi, àwọn ñǹkan ẹlẹ́mìí àti ọ̀pọ̀lọ́pọ̀ nínú àwọn ènìyàn ń forí kanlẹ̀ fún? Ọ̀pọ̀lọpọ̀ sì tún ni ìyà ti kò lé lórí. Ẹnikẹ́ni tí Allāhu bá fi àbùkù kàn, kò sí ẹnì kan tí ó máa ṣe àpọ́nlé rẹ̀.) [Al-Hajj:18]
Ọlọhun da wa fun ìjọsìn Rẹ, àti láti le dán yíyege wa wo níbi fifi ìjọsìn yìí rinlẹ. Ẹni tí ó bá jọ́sìn fún Ọlọhun ti o si nífẹ̀ẹ́ Rẹ, ti o si rẹ ara rẹ silẹ fun Un, ti o si tẹle àṣẹ Rẹ, ti o si jina si máṣeé Rẹ, yoo ri iyọnu Rẹ ati àánú Rẹ ati ifẹ Rẹ, Yoo si san an ni esan daadaa. Ẹni tí ó bá kọ ìjọsìn fun Ọlọhun ti O da a ti O si pèsè ijẹ-imu fun un, ti o ṣe ìgbéraga, ti o wa kọ rírọ̀ fun àwọn àṣẹ Ọlọhun ati jíjìnnà si awọn nǹkan ti O kọ, onítọ̀hún ti padà pẹ̀lú ìbínú Ọlọhun, iya Rẹ si le koko. Ọlọhun kò da wa fun eré, ko si fi wa silẹ lasan. Ninu ẹni ti o ya alaimọkan ju ti o si gọ ju nínú àwọn èèyàn ni ẹni tí ó lérò pé oun wa si ayé, ti wọn si fun un ni igbọrọ ati irina ati làákàyè, lẹ́yìn náà yoo wa sẹmi ni ayé yìí fun àkókò kan, lẹ́yìn náà ti yoo wàá kú, kò wá mọ kini o torí rẹ wá sí ayé, ibo si ni yóò lọ lẹ́yìn rẹ, Ọlọhun ti O gbọnngbọn ti O ga n sọ pé: Ṣé ẹ lérò pé A kàn ṣẹ̀dá yín fún ìranù ni, àti pé dájúdájú wọn ò níí da yín padà sọ́dọ̀ Wa?" Suuratul Muh'minuun: 115.
Ko dọ́gba ni ọdọ Rẹ, ẹni tí ó ba gba A gbọ nínú wa, ti o si gbẹkẹ le E, ti o si maa n gbé ẹjọ́ lọ ba A, ti o si nífẹ̀ẹ́ Rẹ, ti o si rẹ ara rẹ nilẹ fun Un, ti o si n sunmọ Ọn pẹ̀lú àwọn ìjọsìn, ti o si n wa nǹkan ti yoo yọ Ọ nínú ni gbogbo ààyè, irú ẹni bẹ́ẹ̀ kò dọ́gba pẹ̀lú ẹni tí ó ń ṣe Kèfèrí pẹ̀lú Ọlọhun ti O da a, ti O ya àwòrán rẹ, ti o wa n pe àwọn aaya Rẹ ni irọ ati ẹsin Rẹ, ti ko wa rẹ ara rẹ nilẹ fun àṣẹ Rẹ
Ẹni àkọ́kọ́ yóò rí apọnle àti ẹsan ati ifẹ ati ìyọ́nú, tí ẹnì kejì maa ko ìbínú àti ìyà.
Ọlọhun maa gbe àwọn èèyàn dìde lẹ́yìn ikú wọn láti inú sàréè wọn, Yóò si san oluṣerere nínú wọn ni ẹsan pẹ̀lú idẹra ati apọnle nínú ọgbà idẹra. Yoo si fi ìyà jẹ aláìdára onigberaga ti kii jọ́sìn fun Ọlọhun nínú iná Jahiim.
Ronú si títóbi apọnle àti ẹsan ti n bẹ fun oluṣerere nígbà tí ẹsan ati apọnle yii ba ti ọdọ Ọlọhun wa, Ọba ti O rọrọ, Ọba Alapọn-ọnle ti apọnle ati aanu Rẹ ko ni ààlà, ti pẹpẹ-ọrọ̀ Rẹ ko nii tán. Dájúdájú ẹsan yii maa jẹ ọba idẹra ti ko nii tán ti ko si nii kúrò (eléyìí ni a maa sọ̀rọ̀ nípa rẹ ti o ba ya)

O tun yẹ ki o fojú inú wo ilekoko ìyà ti n bẹ fún Kèfèrí nígbà tí ìyà náà ba wa láti ọ̀dọ̀ Ọlọhun Olùjẹni-nípá, Atóbi, Onigberaga ti ko si ààlà fun ijẹni-nipa ati ìgbéraga Rẹ.

# 2- Muhammad ojiṣẹ Ọlọhun n:

Ìní-ìgbàgbọ́ si ijẹ-ojiṣẹ Muhammad- ki ikẹ ati ọla Ọlọhun máa bá a- ni abala kejì fun origun ipilẹ nínú àwọn origun Islām, àti ipilẹ àkọ́kọ́ ti nnkan ti a fẹ́ kọ́ maa dúró lé lórí

Ọmọniyan yoo di Mùsùlùmí lẹ́yìn ti o ba ti pe gbólóhùn ijẹrii méjèèjì, yoo jẹrii pe ko si ẹni ti ìjọsìn tọ si ni òdodo ayafi Allāhu, yoo si jẹrii pe Muhammad ojiṣẹ Ọlọhun ni.

## A- Kini ìtumọ̀ ojiṣẹ? Tani Muhammad? Ǹjẹ́ àwọn ojiṣẹ míràn wa yàtọ̀ si i?

Èyí ni nǹkan ti a maa gbìyànjú lati fèsì fun ni àwọn ojú-ewé yìí

Ojiṣẹ ni arákùnrin kan ni ti o wa ni òkè téńté nibi sísọ ọ̀rọ̀ òdodo ati ìwà dáadáa, Ọlọhun maa n ṣẹsa rẹ nínú àwọn èèyàn, Yóò wàá ranṣẹ si i pẹ̀lú nǹkan tí ó bá fẹ́ nínú àwọn àṣẹ ẹsin àti àwọn àlámọ̀rí ikọkọ, wọn yoo waa pa a láṣẹ ki o jiṣẹ naa fun àwọn ènìyàn. Abara ni ojiṣẹ, o da gẹ́gẹ́ bí àwọn abara yókù ni, o n jẹun gẹ́gẹ́ bí wọn ṣe n jẹun, o n mu gẹ́gẹ́ bí wọ́n ṣe n mu, o si n bukaata si awọn nǹkan ti àwọn abara n bukaata si. Ṣùgbọ́n o yatọ si wọn pẹ̀lú imisi ti o n wa ba a lati ọdọ Ọlọhun, Yóò wàá mu u ri nǹkan ti O ba fẹ nínú àlámọ̀rí kọkọ, ati awọn àṣẹ ẹsin ti o n mu de etigbọọ àwọn ènìyàn, o tun yatọ si wọn bákan náà pẹ̀lú iṣọ Ọlọhun kúrò nibi dídá ẹṣẹ ńlá, tabi èyíkéyìí àlámọ̀rí ti o ba le ba jijiṣẹ Ọlọhun rẹ jẹ.

A maa sọ ìtàn àwọn ojiṣẹ ti wọn ṣíwájú Muhammad (ki ikẹ ati ọla Ọlọhun máa bá a); ki o le hàn si wa pe iṣẹ ti wọn fi rán àwọn ojiṣẹ ẹyọkan ni, oun naa ni ipepe si ìjọsìn fún Ọlọhun nìkan ṣoṣo. A maa bẹ̀rẹ̀ pẹ̀lú ìtàn ìbẹ̀rẹ̀ ijẹ-abara ati ọ̀tá tí eṣu ba bàbá àwọn abara tii ṣe Adam ati awọn arọmọdọmọ rẹ ṣe.

## B- Àkọ́kọ́ àwọn ojiṣẹ ni bàbá wa Adam (ki ọlà maa ba a)

Ọlọhun da bàbá wa Adam- ki ọlà máa bá a- latara amọ, lẹ́yìn náà ni wọ́n fẹ́ ẹmi si i, Ọlọhun ti O gbọnngbọn sọ pé: Dájúdájú A da yín, lẹ́yìn náà A ya àwòrán yín, lẹ́yìn náà A sọ fún àwọn mọlāika pé: "Ẹ forí kanlẹ̀ kí Ādam." Wọ́n sì forí kanlẹ̀ kí i àfi ’Iblīs, tí kò sí nínú àwọn olùforíkanlẹ̀. (Allāhu) sọ pé: "Kí ni ó kọ̀ fún ọ láti forí kanlẹ̀ kí i nígbà tí Mo pa á láṣẹ fún ọ." (Èṣù) wí pé: "Èmi lóore jùlọ sí òun; iná ni O fi dá èmi, O sì dá òun láti ara erùpẹ̀ amọ̀." (Allāhu) sọ pé: "Sọ̀kalẹ̀ kúrò níbí nítorí pé kò lẹ́tọ̀ọ́ fún ọ láti ṣègbéraga níbí. Nítorí náà, jáde dájúdájú ìwọ ń bẹ nínú àwọn ẹni yẹpẹrẹ." . (Èṣù) wí pé: "Lọ́ mi lára títí di ọjọ́ tí wọn yóò gbé àwọn ènìyàn dìde." (Allāhu) sọ pé: "Dájúdájú ìwọ ń bẹ nínú àwọn tí A óò lọ́ lára." {Al-A'roof:10-15}

O wa tọrọ lọ́dọ̀ Ọlọhun ki O lọ oun lára ki O ma si kánjú fi ìyà jẹ oun, ki O si yọnda fun oun lati ṣi Adam ati awọn arọmọdọmọ rẹ lọ́nà ni ti keeta ati ìkórìíra wọn,

Ādam, kí ìwọ àti ìyàwó rẹ máa gbé nínú Ọgbà Ìdẹ̀ra. Nítorí náà, ẹ máa jẹ níbikíbi tí ẹ bá fẹ́. Kí ẹ sì má ṣe súnmọ́ igi yìí nítorí kí ẹ má baà wà nínú àwọn alábòsí. Èṣù sì kó ròyìròyí bá àwọn méjèèjì nítorí kí ó lè fi ohun tí A fi pamọ́ nínú ìhòhò ara wọn hàn wọ́n. Ó sì wí pé: "Olúwa ẹ̀yin méjèèjì kò kọ igi yìí fun yín bí kò ṣe pé kí ẹ̀yin méjèèjì má baà di mọlāika tàbí kí ẹ̀yin méjèèjì má baà di olùṣegbére." Ó sì búra fún àwọn méjèèjì pé: "Dájúdájú èmi wà nínú àwọn onímọ̀ràn fún ẹ̀yin méjèèjì." Ó sì tan àwọn méjèèjì jẹ. Nígbà tí àwọn méjèèjì tọ́ igi náà wò, ìhòhò àwọn méjèèjì sì hàn síra wọn. Wọ́n bá bẹ̀rẹ̀ sí fi àwọn ewé Ọgbà Ìdẹ̀ra bora wọn. Olúwa àwọn méjèèjì sì pè wọ́n pé: "Ǹjẹ́ Èmi kò ti kọ igi náà fun ẹ̀yin méjèèjì? (Ṣé) Èmi kò sì ti sọ fún ẹ̀yin méjèèjì pé ọ̀tá pọ́nńbélé ni Èṣù jẹ́ fun yín?" Àwọn méjèèjì sọ pé: "Olúwa wa, a ti ṣàbòsí sí ẹ̀mí wa. Tí O ò bá foríjìn wá, kí O sì kẹ́ wa, dájúdájú a máa wà nínú àwọn ẹni òfò." (Allāhu) sọ pé: "Ẹ sọ̀kalẹ̀, ọ̀tá ní apá kan yín fún apá kan. Ibùgbé àti ñǹkan ìgbádùn sì ń bẹ fun yín ní orí ilẹ̀ fún ìgbà (díẹ̀).” (Allāhu) sọ pé: “Lórí ilẹ̀ ni ẹ̀yin yóò ti máa ṣẹ̀mí, lórí rẹ̀ ni ẹ̀yin yóò máa kú sí, A ó sì mu yín jáde láti inú rẹ̀.” Ọmọ (Ànábì) Ādam, dájúdájú A ti sọ aṣọ kalẹ̀ fun yín, tí ó máa bo ìhòhò yín àti ohun àmúṣọrọ̀. Aṣọ ìbẹ̀rù Allāhu, ìyẹn l’ó sì lóore jùlọ. Ìyẹn wà nínú àwọn àmì Allāhu nítorí kí wọ́n lè lo ìrántí. Ọmọ (Ànábì) Ādam, ẹ má ṣe jẹ́ kí Èṣù kó ìfòòró ba yín gẹ́gẹ́ bí ó ṣe yọ àwọn òbí yín méjèèjì jáde kúrò nínú Ọgbà Ìdẹ̀ra. Ó gba aṣọ kúrò lára àwọn méjèèjì nítorí kí ó lè fi ìhòhò wọn hàn wọ́n. Dájúdájú ó ń ri yín; òun àti àwọn ọmọ ogun rẹ̀ (ń ri yín) ní àyè tí ẹ̀yin kò ti rí wọn. Dájúdájú Àwa fi Èṣù ṣe ọ̀rẹ́ fún àwọn tí kò gbàgbọ́. {Al-A'roof:19-27}

“Lẹ́yìn ti Adamọ ti sọkalẹ si ilẹ ti wọn si fun un ni awọn ọmọ ati awọn arọmọdọmọ (ki alaafia maa ba a), lẹyin naa, àwọn arọmọdọ́mọ́ rẹ pọ si ni ìran si ìran, eṣu ṣi wọn lọ́nà, iyapa si tan kaakiri laarin wọn ati jijọsin fun awọn sàréè awọn ẹniire ninu awọn baba wọn, ti wọn si yí padà lati igbagbọ si ibọriṣa; nítorí náà ni Ọlọhun ṣe ran ojiṣẹ kan si wọn laarin wọn, oun naa ni (Nuuh, ki alaafia máa bá a)."

## "3. Nuuh- ki alaafia maa ba a-:"

"Ọgọ́rùn-ún ọdún mẹwa ni o wa laarin rẹ àti Adamọ, Ọlọhun ran an si ìjọ rẹ lẹyin igba ti wọ́n ti sọnu ti wọ́n wa di ẹni tí n jọ́sìn fun awọn ooṣa ati awọn okuta ati awọn sàréè. Lára àwọn to gbajumọ jù ninu àwọn tí

wọn pe ni ọlọhun wọn ni "waddu, suwaa'u, yaguusu, ya'uuku ati nasrọọ, tori idi eyi ni Allahu ṣe ran Nuuh lati da wọn pada lọ sibi ìjọsìn Allahu nìkan, gẹ́gẹ́ bí Allahu ti ọla Rẹ ga ti fun wa ni iro nipa rẹ pe:" Dájúdájú A rán (Ànábì) Nūh nísẹ́ sí ìjọ rẹ̀. Ó sì sọ pé: "Ẹ̀yin ìjọ mi, ẹ jọ́sìn fún Allāhu. Ẹ ò ní ọlọ́hun mìíràn lẹ́yìn Rẹ̀. Dájúdájú mò ń bẹ̀rù ìyà Ọjọ́ Ńlá fun yín." Suratul A'raf: 59 “Ati pe o tẹsiwaju lati pe awọn ijọ rẹ lati jọsin fun Allāhu fun igba pipẹ, ati pe diẹ ni o gbagbọ pẹlu rẹ, ni o wa ké pe Oluwa rẹ pe: Ó sọ pé: "Olúwa mi, dájúdájú èmi pe ìjọ mi ní òru àti ní ọ̀sán. Ìpè mi kò sì ṣe àlékún kan fún wọn àyàfi sísá sẹ́yìn (fún òdodo). Àti pé ìgbàkígbà tí mo bá pè wọ́n pé kí O lè foríjìn wọ́n, wọ́n ń fi ọmọníka wọn dí etí wọn, wọ́n ń yíṣọ wọn borí, wọ́n ń takú (sórí ẹ̀ṣẹ̀), wọ́n sì ń ṣègbéraga gan-an. Lẹ́yìn náà, dájúdájú èmi pè wọ́n pẹ̀lú ohùn òkè. Lẹ́yìn náà, dájúdájú èmi kéde fún wọn, mo sì tún pè wọ́n ní ìdá kọ́ńkọ́. Mo sì sọ pé, ẹ tọrọ àforíjìn ní ọ̀dọ̀ Olúwa yín, dájúdájú Ó ń jẹ́ Aláforíjìn. Ó máa rọ̀jò fun yín ní òjò púpọ̀, Ó máa fi àwọn dúkìá àti àwọn ọmọkùnrin ràn yín lọ́wọ́. Ó máa ṣe àwọn ọgbà oko fun yín. Ó sì máa ṣe àwọn odò fun yín. Kí ló mu yín tí ẹ kò páyà títóbi Allāhu? Ó sì kúkú ṣẹ̀dá yín láti ìrísí kan sí òmíràn (nínú oyún). [Nuuh:5-14] “Tòun ti igbiyanju lemọlemọ yii, ati itara iyalẹnu lati ṣe itọsọna awọn ijọ rẹ yii, wọn pe e ni onirọ, won tun ṣe ẹlẹya rẹ, wọn tun fi ẹsun aṣiwere kan an".

"Allahu wa ranṣẹ si i pé" kò sí ẹnì kan tí ó máa gbàgbọ́ mọ́ nínú ìjọ rẹ àfi ẹni t’ó ti gbàgbọ́ tẹ́lẹ̀. Nítorí náà, má ṣe banújẹ́ nípa ñǹkan tí wọ́n ń ṣe nísẹ́. (Huud:36)" “O si paṣẹ fun un lati kan ọkọ oju omi ti yoo fi gbe gbogbo eniyan ti wọn gbagbọ pẹlu rẹ.” Ó sì ń kan ọkọ̀ ojú-omi náà lọ. Nígbàkígbà tí àwọn ọ̀tọ̀kùlú nínú ìjọ rẹ̀ bá kọjá lọ́dọ̀ rẹ̀, wọ́n yó sì máa fi ṣe yẹ̀yẹ́. (Ànábì Nūh) sì sọ pé: "Tí ẹ bá fi wá ṣe yẹ̀yẹ́, dájúdájú àwa náà yóò fi yín ṣe yẹ̀yẹ́ gẹ́gẹ́ bí ẹ ṣe ń fi wá ṣe yẹ̀yẹ́. Nítorí náà, láìpẹ́ ẹ máa mọ ẹni tí ìyà máa dé bá, tí ó máa yẹpẹrẹ rẹ̀, tí ìyà gbere sì máa kò lé lórí." (Báyìí ni ọ̀rọ̀ wà) títí di ìgbà tí àṣẹ Wa dé, omi sì ṣẹ́yọ gbùú láti ojú-àrò (tí wọ́n ti ń ṣe búrẹ́dì). A sọ pé: "Kó gbogbo ñǹkan ní orísì méjì takọ-tabo àti ará ilé rẹ sínú ọkọ̀ ojú-omi - àyàfi ẹni tí ọ̀rọ̀ náà ti kò lé lórí (fún ìparun) - àti ẹnikẹ́ni t’ó gbàgbọ́ ní òdodo. Kò sì sí ẹni t’ó ní ìgbàgbọ́ òdodo pẹ̀lú rẹ̀ àfi àwọn díẹ̀. (Ànábì Nūh) sọ pé: "Ẹ wọ inú ọkọ̀ ojú-omi náà. Ó máa rìn, ó sì máa gúnlẹ̀ ní orúkọ Allāhu. Dájúdájú Olúwa mi ni Aláforíjìn, Àṣàkẹ́-ọ̀run." Ó sì ń gbé wọn lọ nínú ìgbì omi t’ó dà bí àpáta. (Ànábì Nūh) sì ké sí ọmọkùnrin rẹ̀, tí ó ti yara rẹ̀ sọ́tọ̀: "Ọmọkùnrin mi, gun ọkọ̀ ojú-omi pẹ̀lú wa. Má sì ṣe wà pẹ̀lú àwọn aláìgbàgbọ́." Ó wí pé: “Èmi yóò forí pamọ́ síbi àpáta kan tí ó máa là mí níbi omi.” (Ànábì Nūh) sọ pé: "Kò sí aláàbò kan ní òní níbi àṣẹ Allāhu àfi ẹni tí Allāhu bá ṣàánú." Ìgbì omi sì la àwọn méjèèjì láàrin. Ó sì di ara àwọn olùtẹ̀rì sínú omi. A sọ pé: "Ilẹ̀, fa omi rẹ mu. Sánmọ̀, dáwọ́ (òjò) dúró." Wọ́n sì dín omi kù. Ọ̀rọ̀ ìparun wọn sì wá sí ìmúṣẹ. (Ọkọ̀ ojú-omi) sì gúnlẹ̀ sórí àpáta Jūdī. A sì sọ pé: “Ìjìnnà réré sí ìkẹ́ Allāhu ni ti ìjọ alábòsí.” (Ànábì) Nūh pe Olúwa rẹ̀, ó sì sọ pé: “Olúwa mi, dájúdájú ọmọ mi wà nínú ará ilé mi. Àti pé dájúdájú àdéhùn Rẹ, òdodo ni. Ìwọ l’O sì mọ ẹjọ́ dá jùlọ nínú àwọn adájọ́. Allāhu sọ pé: “Nūh, dájúdájú kò sí nínú ará ilé rẹ (ní ti ẹ̀sìn). Dájúdájú iṣẹ́ tí kò dára ni. Nítorí náà, o ò gbọdọ̀ bi Mí léèrè ñǹkan tí o ò ní ìmọ̀ nípa rẹ̀. Dájúdájú Èmi ń kìlọ̀ fún ọ nítorí kí o má baà di ara àwọn aláìmọ̀kan.” Ó sọ pé: "Olúwa mi, dájúdájú èmi ń sá di Ọ́ níbi kí ñg bi Ọ́ léèrè ñǹkan tí èmi kò ní ìmọ̀ rẹ̀. Tí O ò bá foríjìn mí, kí O sì ṣàánú mi, èmi yóò wà lára àwọn ẹni òfò." A sọ pé: "Nūh, sọ̀kalẹ̀ pẹ̀lú àlàáfíà láti ọ̀dọ̀ Wa. Àti pé kí ìbùkún wà pẹ̀lú rẹ àti àwọn ìjọ nínú àwọn t’ó ń bẹ pẹ̀lú rẹ. Àwọn ìjọ kan (tún ń bọ̀), tí A óò fún wọn ní ìgbádùn (oore ayé). Lẹ́yìn náà, ìyà ẹlẹ́ta-eléro yó sì fọwọ́ bà wọ́n láti ọ̀dọ̀ Wa." [Huud:38-48]

# "4- Ojiṣẹ Allahu Hud (ki alaafia maa ba a)"

“Lẹhin igba diẹ, Ọlọhun ranṣẹ si ẹya Aad ni agbegbe kan ti a n pe ni Al-Ahqaf- lẹ́hìn ti wọn ti ṣina ti wọn si jọsin fun ẹniti o yatọ si Allahu- O wa ran ojiṣẹ kan si wọn laarin wọn ti o n jẹ Huud, ki alaafia maa ba a. ”

"Allāhu ti ọla Rẹ ga fun wa ni iro nipa rẹ pẹlu ọrọ Rẹ pe:" A tún rán (ẹnì kan) sí àwọn ará ‘Ād, arákùnrin wọn, Hūd. Ó sọ pé: “Ẹ̀yin ìjọ mi, ẹ jọ́sìn fún Allāhu. Ẹ ò ní ọlọ́hun mìíràn lẹ́yìn Rẹ̀. Ṣé ẹ ò níí bẹ̀rù (Rẹ̀) ni?" Àwọn àgbààgbà t’ó ṣàì gbàgbọ́ nínú ìjọ rẹ̀ wí pé: “Dájúdájú àwa ń rí ọ pé o wà nínú agọ̀. Àti pé dájúdájú à ń rò pé o wà nínú àwọn òpùrọ́.” Ó sọ pé: "Ẹ̀yin ìjọ mi, kò sí agọ̀ kan lára mi, ṣùgbọ́n dájúdájú èmi ni Òjíṣẹ́ kan láti ọ̀dọ̀ Olúwa gbogbo ẹ̀dá. Mò ń jẹ́ àwọn iṣẹ́ Olúwa mi fun yín. Èmi sì ni onímọ̀ràn rere, olùfọkàntán fun yín. Àti pé ṣé ẹ ṣèèmọ̀ pé ìrántí láti ọ̀dọ̀ Olúwa yín dé ba yín ni, (èyí tí Wọ́n fún) ọkùnrin kan nínú yín, nítorí kí ó lè kìlọ̀ fun yín? Ẹ rántí nígbà tí (Allāhu) fi yín ṣe àrólé lẹ́yìn ìjọ (Ànábì) Nūh. Ó tún ṣe àlékún agbára fun yín nínú ìṣẹ̀dá (yín). Nítorí náà, ẹ rántí àwọn ìdẹ̀ra Allāhu, nítorí kí ẹ lè jèrè." Wọ́n wí pé: “Ṣé o wá bá wa nítorí kí á lè jọ́sìn fún Allāhu nìkan ṣoṣo àti nítorí kí á lè pa ohun tí àwọn bàbá ńlá wa ń jọ́sìn fún tì? Nítorí náà, mú ohun tí o ṣe ní ìlérí fún wa ṣẹ tí o bá wà nínú àwọn olódodo.” Ó sọ pé: “Ìyà àti ìbínú kúkú ti sọ̀kalẹ̀ sórí yín láti ọ̀dọ̀ Olúwa yín. Ṣé ẹ óò máa jà mí níyàn nípa àwọn orúkọ (òrìṣà) kan tí ẹ̀yin àti àwọn bàbá yín fún lórúkọ - Allāhu kò sì sọ ẹ̀rí kan kalẹ̀ fún un? – Nítorí náà, ẹ máa retí, dájúdájú èmi náà wà pẹ̀lú yín nínú àwọn olùretí.” Nítorí náà, pẹ̀lú àánú láti ọ̀dọ̀ Wa, A gba òun àti àwọn t’ó wà pẹ̀lú rẹ̀ là. A sì pa àwọn t’ó pe àwọn āyah Wa nírọ́ run; wọn kì í ṣe onígbàgbọ́ òdodo. (Al-A'raf:65-72)"

“Nitori naa Allāhu ran atẹ́gùn líle si wọn ni ọjọ mẹjọ ti o pa gbogbo nǹkan run pẹ̀lú aṣẹ Oluwa rẹ, Allahu si gba Hud ati awọn ti o gbagbọ pẹlu rẹ la».

## "5. Ojiṣẹ Allāhu to n jẹ Soolih, ki alaafia maa ba a"

"Lẹ́yìn naa, nígbà tí àkókò díẹ̀ rẹ kọjá, ìdílé Samudawa si dide ni ariwa erékùsù larubawa, ti awọn naa ṣìnà gẹ́gẹ́ bí awọn ti o ti ṣáájú wọn ti ṣe ṣìnà, ni Allāhu wa ran ojiṣẹ kan si wọn laarin wọn (Salihu), ki alaafia maa ba a, o si ṣe atilẹyin fun un pẹlu àmì kan ti n tọka si ododo rẹ, oun naa ni abo rakunmi nla ti ko ni afijọ ninu awọn ẹda, Allahu ti ọla Rẹ ga si fun wa ni ìró nipa rẹ pe:" A tún rán (ẹnì kan) sí àwọn ìran Thamūd, arákùnrin wọn, Sọ̄lih. Ó sọ pé: "Ẹ̀yin ìjọ mi, ẹ jọ́sìn fún Allāhu. Ẹ ẹ̀ ní ọlọ́hun mìíràn lẹ́yìn Rẹ̀. Iṣẹ́ ìyanu kúkú ti dé ba yín láti ọ̀dọ̀ Olúwa yín; èyí ni abo ràkúnmí Allāhu. (Ó jẹ́) àmì kan fun yín. Nítorí náà, ẹ fi sílẹ̀, kí ó máa jẹ kiri lórí ilẹ̀ Allāhu. Ẹ má ṣe fi ọwọ́ aburú kàn án nítorí kí ìyà ẹlẹ́ta-eléro má baà jẹ yín. Ẹ tún rántí nígbà tí (Allāhu) ṣe yín ní àrólé lẹ́yìn àwọn ara ‘Ād. Ó sì fun yín ní ilé ìgbé lórí ilẹ̀; ẹ̀ ń kọ́ ilé ńláńlá sínú pẹ̀tẹ́lẹ̀, ẹ sì ń gbẹ́ àwọn ilé sínú àpáta. Ẹ rántí àwọn ìdẹ̀ra Allāhu, kí ẹ sì má ṣe rìn lórí ilẹ̀ ní ti òbìlẹ̀jẹ́. Àwọn àgbààgbà t’ó ṣègbéraga nínú ìjọ rẹ̀ wí fún àwọn tí wọ́n fojú tínrín, (ìyẹn) àwọn t’ó gbàgbọ́ lódodo nínú wọn, pé: "Ǹjẹ́ ẹ mọ̀ pé dájúdájú Sọ̄lih ni Òjíṣẹ́ láti ọ̀dọ̀ Olúwa rẹ̀?" Wọ́n sọ pé: “Dájúdájú àwa gbàgbọ́ nínú ohun tí Wọ́n fi rán an níṣẹ́.” Àwọn t’ó ṣègbéraga wí pé: “Dájúdájú àwa ṣàì gbàgbọ́ nínú ohun tí ẹ̀yin gbàgbọ́.” Nítorí náà, wọ́n gún abo ràkúnmí náà pa. Wọ́n sì tàpá sí àṣẹ Olúwa wọn. Wọ́n sì wí pé: “Sọ̄lih, mú ohun tí o ṣe ní ìlérí fún wa ṣẹ tí o bá wà nínú àwọn Òjíṣẹ́.” Nítorí náà, ohùn igbe líle t’ó mi ilẹ̀ tìtì gbá wọn mú. Wọ́n sì di ẹni t’ó dà lulẹ̀, tí wọ́n ti dòkú sínú ìlú wọn. Nígbà náà, (Sọ̄lih) ṣẹ́rí kúrò lọ́dọ̀ wọn, ó sì sọ pé: “Ẹ̀yin ìjọ mi, mo kúkú ti jẹ́ iṣẹ́ Olúwa mi fun yín. Mo sì ti fun yín ní ìmọ̀ràn rere ṣùgbọ́n ẹ̀yin kò fẹ́ràn àwọn onímọ̀ràn rere.” [Al-A'raaf: 73-79]

Ọlọhun Ọba Allah ni ran awọn ojiṣẹ ti o pọ lẹyin igba naa si awọn ijọ ti o wa lori ilẹ, ko wa si ijọ kankan ayafi ki olukilọ ti rekọja láàárín wọn, Ọlọhun Ọba Allaah fun wa ni iro nipa apa kan ninu wọn, Ko si fun wa ni iro nipa ọpọ ninu wọn, gbogbo wọn patapata ni wọn fi iṣẹ kan náà ran tii ṣe mimaa pa awọn eeyan laṣẹ pẹlu ijọsin fun Ọlọhun Ọba Allah nikan ṣoṣo, ti ko si si akẹgbẹ kankan fun Un, ati gbígbé ijọsin fun ohun ti o yatọ si Ọlọhun Ọba Allaah jù silẹ. Ọlọhun ti ọla Rẹ ga sọ pe: Dájúdájú A ti gbé Òjíṣẹ́ dìde nínú ìjọ kọ̀ọ̀kan (láti jíṣẹ́) pé: “Ẹ jọ́sìn fún Allāhu. Kí ẹ sì jìnnà sí àwọn òrìṣà.” Nítorí náà, ó wà nínú wọn, ẹni tí Allāhu tọ́ sí ọ̀nà. Ó sì wà nínú wọn, ẹni tí ìṣìnà kò lé lórí. Nítorí náà, ẹ rìn kiri lórí ilẹ̀, kí ẹ sì wòye sí bí àtubọ̀tán àwọn t’ó pé àwọn Òjíṣẹ́ ní òpùrọ́ ṣe rí? [An-Nah'l:36]

## Ojiṣẹ tii ṣe Ibraahim (Ki alaafia Ọlọhun maa ba a)

Lẹyin igba naa ni Ọlọhun wa gbe Ojiṣẹ ti nṣe Ibrahiim (Ki alaafia Ọlọhun maa ba a) dide si ijọ rẹ lẹyin igba ti wọn ti sọnu, ti wọn si n jọsin fun awọn irawọ ati awọn oriṣa. Ọlọhun Ọba ti ọla Rẹ ga wa sọ pe: Dájúdájú A ti fún (Ànábì) ’Ibrọ̄hīm ní ìmọ̀nà tirẹ̀ ṣíwájú (kí ó tó dàgbà). Àwa sì ń jẹ́ Onímọ̀ nípa rẹ̀. (Rántí) nígbà tí ó sọ fún bàbá rẹ̀ àti ìjọ rẹ̀ pé: “Kí ni àwọn ère wọ̀nyí tí ẹ̀ ń dúró tì lọ́rùn ṣe jẹ́ ná?” Wọ́n wí pé: “A bá àwọn bàbá wa tí wọ́n ń jọ́sìn fún wọn ni.” Ó sọ pé: “Dájúdájú ẹ̀yin àti àwọn bàbá yín ti wà nínú ìṣìnà pọ́nńbélé.” Wọ́n wí pé: “Ṣé o mú òdodo wá fún wa ni tàbí ìwọ wà lára àwọn ẹlẹ́fẹ̀.” Ó sọ pé: "Rárá. Olúwa yin ni Olúwa àwọn sánmọ̀ àti ilẹ̀; Ẹni tí Ó pílẹ̀ ìṣẹ̀dá wọn. Èmi sì wà nínú àwọn ẹlẹ́rìí lórí ìyẹn. Àti pé mo fi Allāhu búra, dájúdájú mo máa dète sí àwọn òrìṣà yín lẹ́yìn tí ẹ bá pẹ̀yìn dà, tí ẹ lọ." Ó sì fọ́ wọn sí wẹ́wẹ́ àfi àgbà (òrìṣà) wọn nítorí kí wọ́n lè padà dé bá a. Wọ́n wí pé: “Ta ni ó ṣe èyí pẹ̀lú àwọn ọlọ́hun wa? Dájúdájú onítọ̀un wà nínú àwọn alábòsí.” Wọ́n wí pé: “A gbọ́ tí ọ̀dọ́kùnrin kan ń bu ẹnu àtẹ́ lù wọ́n. Wọ́n ń pe (ọmọ náà) ní ’Ibrọ̄hīm.” Wọ́n wí pé: “Ẹ mú un wá han àwọn èniyàn kí wọ́n lè jẹ́rìí lé e lórí.” Wọ́n wí pé: “Ṣé ìwọ l’o ṣe èyí pẹ̀lú àwọn ọlọ́hun wa, ’Ibrọ̄hīm?” Ó sọ pé: “Rárá o, àgbà wọn yìí l’ó ṣe (wọ́n bẹ́ẹ̀). Nítorí náà, ẹ bi wọ́n léèrè wò tí wọ́n bá máa ń sọ̀rọ̀.” Nígbà náà, wọ́n yíjú síra wọn, wọ́n sì wí pé: “Dájúdájú ẹ̀yin ni alábòsí.” Lẹ́yìn náà, wọ́n sorí kọ́ (wọ́n sì wí pé): “Ìwọ náà kúkú mọ̀ pé àwọn wọ̀nyí kì í sọ̀rọ̀.” Ó sọ pé: "Ṣé ẹ̀yin yóò máa jọ́sìn fún ñǹkan tí kò lè ṣe yín ní àǹfààní, tí kò sì lè kó ìnira ba yín lẹ́yìn Allāhu? Ṣíọ̀ ẹ̀yin àti ñǹkan tí ẹ̀ ń jọ́sìn fún lẹ́yìn Allāhu, ṣé ẹ̀yin kò níí ṣe làákàyè ni?" Wọ́n wí pé: “Ẹ dáná sun ún; kí ẹ sì ran àwọn ọlọ́hun yín lọ́wọ́, tí ẹ̀yin bá níkan-án ṣe.” A sọ pé: “Iná, di tútù àti àlàáfíà lára ’Ibrọ̄hīm.” Wọ́n gbèrò ète sí i, ṣùgbọ́n A ṣe wọ́n ní olófò jùlọ. [Al-Anbiyaah 50-70].

Lẹyin igba naa ni Ibrōhım (Ki alaafia Ọlọhun maa ba a) wa ṣe hijira ati ọmọ rẹ tii ṣe Ismãil lati ilẹ (Palestine) lọ si ilẹ Makkãh. Ọlọhun Oba Allah wa pa a laṣẹ ati ọmọ rẹ Ismãil pe ki wọn o kọ Ka'abah Abiyi, o si pe awọn eeyan lọ si ibẹ fun iṣẹ (Hajj) ati ijọsin fun Ọlọhun Ọba Allaah ni ibẹ. A si pa (Anabi) ’Ibrọ̄hīm ati (Anabi) ’Ismọ̄‘īl laṣẹ pe “Ẹ ṣe Ile Mi ni mimọ fun awọn oluyipo rẹ, awọn olukoraro sinu rẹ ati awọn oludawọtẹ-orunkun, awọn oluforikanlẹ (lori irun). Al-Baqara 125

## Ojiṣẹ Ọlọhun Lût (Ki alaafia Ọlọhun maa ba a)

Lẹyin igba naa ni Ọlọhun Ọba Allaah wa ran Lût si ijọ rẹ ti wọn si jẹ ijọ buruku ti wọn n jọsin fun nnkan ti o yatọ si Ọlọhun, bakannaa ti wọn si tun n wu iwa ibajẹ laarin ara wọn. Ọlọhun Ọba Allaah ti ọla Rẹ ga sọ pe: (Rántí Ànábì) Lūt, nígbà tí ó sọ fún ìjọ rẹ̀ pé: "Ṣé ẹ óò máa ṣe ìbàjẹ́ ni tí kò sí ẹnì kan nínú àwọn ẹ̀dá t’ó ṣe irú rẹ̀ rí? Dájúdájú ẹ̀yin (ọkùnrin) ń lọ jẹ adùn (ìbálòpọ̀) lára àwọn ọkùnrin (ẹgbẹ́ yín) dípò àwọn

obìnrin! Àní sẹ́, ìjọ alákọyọ ni yín." Kí sì ni ó jẹ́ èsì ìjọ rẹ̀ bí kò ṣe pé, wọ́n wí pé: "Ẹ lé wọn jáde kúrò nínú ìlú yín, dájúdájú wọ́n jẹ́ ènìyàn kan t'ó ń fọra wọn mọ́ (níbi ẹ̀ṣẹ̀)." [Al-A'rãf:80-82] Ọlọhun wa la oun ati awọn eeyan rẹ ayafi iyawo rẹ ti n bẹ ninu awọn olukọti Ọlọhun, nibi ti Ọlọhun ti pa oun ati awọn eeyan rẹ laṣẹ pe ki wọn kuro ninu abúlé naa ni alẹ, nigba ti idajọ Ọlọhun wa de, O sọ awọn oke wọn di ilẹ, bakan naa ni O si rọ òjò òkúta amọ̀ (sísun) lé wọn lórí ní tẹ̀léǹtẹ̀lé.

# Ojiṣẹ ti ń ṣe Shuaib (Ki alaafia Ọlọhun maa ba a) a

Lẹyin igba naa ni Ọlọhun wa gbe dide si ijọ Mad'yan ọmọ iya wọn ti ń ṣe Shuaib lẹyin ti wọn ti sọnu kuro nibi oju ọna ododo, ti awọn iwa ibajẹ si ti fọnka laarin wọn, ati títayọ ẹnu-ala si awọn eeyan, ati mimaa din awọn oṣuwọn kilo ati abọ ku. Ọlọhun Ọba Allaah wa fun wa ni iro nipa wọn pẹlu ọrọ rẹ pe: (A tún rán ẹnì kan) sí àwọn ará Mọdyan, arákùnrin wọn, Ṣu'aeb. Ó sọ pé: "Ẹ̀yin ìjọ mi, ẹ jọ́sìn fún Allāhu. Ẹ̀ ẹ̀ ní ọlọ́hun mìíràn lẹ́yìn Rẹ̀. Dájúdájú ẹ̀rí t'ó yanjú ti dé ba yín láti ọ̀dọ̀ Olúwa yín. Nítorí náà, ẹ wọn kóńgò àti òṣùwọ̀n kún. Ẹ má ṣe dín ǹǹkan àwọn ènìyàn kù. Ẹ sì má ṣe ìbàjẹ́ lórí ilẹ̀ lẹ́yìn àtúnṣe rẹ̀. Ìyẹn sì lóore jùlọ fun yín tí ẹ bá jẹ́ onígbàgbọ́ òdodo. Ẹ má ṣe lúgọ sí gbogbo ọ̀nà láti máa dẹ́rùba àwọn ènìyàn; ẹ̀ ń ṣẹ́rí ẹni t'ó gbagbọ́ kúrò lójú ọ̀nà (ẹ̀sìn) Allāhu, ẹ sì ń fẹ́ k'ó wọ́. Ẹ rántí o, nígbà tí ẹ kéré (lóǹkà), Allāhu sọ yín di púpọ̀. Ẹ sì wo bí ìkángun àwọn òbìlẹ̀jẹ́ ṣe rí. Tí ó bá jẹ́ pé igun kan nínú yín gbàgbọ́ nínú ohun tí Wọ́n fi rán mi níṣẹ́, tí igun kan kò sì gbàgbọ́, nígbà náà ẹ ṣe sùúrù títí Allāhu yóò fi ṣe ìdájọ́ láàárin wa. Òun sì lóore jùlọ nínú àwọn olùdájọ́. Àwọn àgbààgbà t'ó ṣègbéraga nínú ìjọ rẹ̀ wí pé: "Dájúdájú a máa lé ìwọ Ṣu'aeb àti àwọn t'ó gbàgbọ́ pẹ̀lú rẹ jáde kúrò nínú ìlú wa tàbí ẹ gbọ́dọ̀ padà sínú ẹ̀sìn wa." (Ṣu'aeb) sọ pé: "Ṣé (ẹ máa dá wa padà sínú ìbọ̀rìṣà) t'ó sì jẹ́ pé ẹ̀mí wa kọ̀ ọ́?" Dájúdájú a ti dá àdápa irọ́ mọ́ Allāhu tí a bá fi lè padà sínú ẹ̀sìn yín lẹ́yìn ìgbà tí Allāhu ti yọ wá kúrò nínú rẹ̀. Àti pé kò lẹ́tọ̀ọ́ fún wa láti padà sínú rẹ̀ àfi tí Allāhu, Olúwa wa bá fẹ́. Olúwa wa gbòòrò tayọ gbogbo ǹǹkan pẹ̀lú ìmọ̀. Allāhu l'a gbáralé. Olúwa wa, ṣe ìdájọ́ láàárin àwa àti ìjọ wa pẹ̀lú òdodo, Ìwọ sì lóore jùlọ nínú àwọn olùdájọ́." Àwọn àgbààgbà t'ó ṣàì gbàgbọ́ nínú ìjọ rẹ̀ wí pé: "Dájúdájú tí ẹ̀yin bá tẹ̀lé Ṣu'aeb, nígbà náà ẹ̀yin ti di ẹni òfò nìyẹn." Nítorí náà, ohùn igbe líle t'ó mi ilẹ̀ tìtì gbá wọn mú. Wọ́n sì di ẹni t'ó dà lulẹ̀, tí wọ́n ti dòkú sínú ìlú wọn. Àwọn t'ó pe Ṣu'aeb lópùrọ́ sì dà bí ẹni tí kò gbé nínú ìlú wọn rí; àwọn t'ó pe Ṣu'aeb lópùrọ́ ni wọ́n jẹ́ ẹni òfò. Nítorí náà, (Ṣu'aeb) ṣẹ́rí kúrò lọ́dọ̀ wọn, ó sì sọ pé: "Ẹ̀yin ìjọ mi, mo kúkú ti jẹ́ àwọn iṣẹ́ Olúwa mi fun yín. Mo sì ti fun yín ní ìmọ̀ràn rere. Báwo ni èmi yóò ṣe tún máa banújẹ́ lórí ìjọ aláìgbàgbọ́." "(Al-A'raf:85-93)

# "Ojiṣẹ Allahu, Musa (ki alaafia maa ba a).

"Lẹ́yìn náà ni olùtayọ-ẹnu-àlà ati onigberaga ọba kan dide ni ilu Egypt, wọn n pe e ni Farao, ti o sọ pe oun jẹ ọlọrun, ti o si paṣẹ fun awọn eniyan lati jọsin fun oun, o si n dú ẹnikẹni ti o ba fẹ, o si n ṣe abosi eniti o ba wù ú. Allahu ti ọla Rẹ ga fun wa ni iro nipa rẹ pe:" Dájúdájú Fir'aon ṣègbéraga lórí ilẹ̀. Ó ṣe àwọn ènìyàn rẹ̀ ní ìjọ-ìjọ. Ó ń dá igun kan nínú wọn lágara; ó ń pa àwọn ọmọkùnrin wọn, ó sì ń dá àwọn obìnrin wọn sí. Dájúdájú ó wà nínú àwọn òbìlẹ̀jẹ́. A sì fẹ́ ṣèdẹ̀ra fún àwọn tí wọ́n fojú tínrín lórí ilẹ̀, A (fẹ́) ṣe wọ́n ní aṣíwájú. A sì (fẹ́) kí wọ́n jogún (ilẹ̀). A (fẹ́) gbà wọ́n láàyè lórí ilẹ̀. Láti ara wọn, A sì (fẹ́) fi han Fir'aon àti Hāmọ̄n pẹ̀lú àwọn ọmọ ogun àwọn méjèèjì ohun tí wọ́n ń ṣọ́ra fún lára wọn. A sì ránṣẹ́ sí ìyá (Ànábì) Mūsā pé: "Fún un ní ọmú mu. Tí o bá sì ń páyà lórí rẹ̀, jù ú sínú agbami odò. Má ṣe bẹ̀rù. Má sì ṣe banújẹ́. Dájúdájú Àwa máa dá a padà sí ọ̀dọ̀ rẹ. A ó sì ṣe é ní ara àwọn Òjíṣẹ́. Nígbà náà, àwọn ènìyàn Fir'aon rí i he nítorí kí ó lè jẹ́ ọ̀tá àti ìbànújẹ́ fún wọn. Dájúdájú Fir'aon, Hāmọ̄n àti àwọn ọmọ ogun àwọn méjèèjì, wọ́n jẹ́ aláṣìṣe. Ìyàwó Fir'aon wí pé: "Ìtutù-ojú ni (ọmọ yìí) fún èmi àti ìwọ. Ẹ má ṣe pa á. Ó lè jẹ́ pé ó máa ṣe wá ní àǹfààní tàbí kí a fi ṣe ọmọ." Wọn kò sì fura. Ọkàn ìyá (Ànábì) Mūsā pami (lórí ọ̀rọ̀ Mūsā, kò sì rí ǹǹkan mìíràn rò mọ́ tayọ rẹ̀) ó kúkú fẹ́ẹ̀ ṣàfi hàn rẹ̀ (pé ọmọ òun ni nígbà tí wọ́n pè é dé ọ̀dọ̀ Fir'aon) tí kò bá jẹ́ pé A kì í lọ́kàn nítorí kí ó lè wà nínú àwọn onígbàgbọ́ òdodo. Ó sì sọ fún arábìnrin rẹ̀ pé: "Tọpa rẹ̀ lọ." Ó sì ń wò ó láti ibi t'ó jìnnà. Wọn kò sì fura (sí i). A kò sì jẹ́ kí ó mu ọyàn (mìíràn) ṣíwájú (tìyá rẹ̀.) Arábìnrin rẹ̀ sì wí pé: "Ṣé kí ñg fi ará ilé kan hàn yín, tí ó máa gbà á tọ́ fun yín? Wọn yó sì jẹ́ olùtọ́jú rẹ̀." A sì dá a padà sí ọ̀dọ̀ ìyá rẹ̀ nítorí kí ojú rẹ̀ lè tutù (fún ìdùnnú) àti nítorí kí ó má baà banújẹ́. Àti pé nítorí kí ó lè mọ̀ pé dájúdájú àdéhùn Allāhu, òdodo ni, ṣùgbọ́n ọ̀pọ̀lọ́pọ̀ wọn ni kò mọ̀. Nígbà t'ó dàgbà, t'ó di géńdé, A fún un ní ọgbọ́n àti ìmọ̀. Báyẹn ni A ṣe ń san àwọn olùṣe-rere ní ẹ̀san Ó wọ inú ìlú nígbà tí àwọn ará ìlú ti gbàgbé (nípa ọ̀rọ̀ rẹ̀). Ó rí àwọn ọkùnrin méjì kan tí wọ́n ń jà. Èyí wá láti inú ìran rẹ̀. Èyí sì wá láti (inú ìran) ọ̀tá rẹ̀. Èyí tí ó wá láti inú ìran rẹ̀ wá ìrànlọ́wọ́ rẹ̀ lórí èyí tí ó wá láti (inú ìran) ọ̀tá rẹ̀. Mūsā kàn án ní ẹ̀ṣẹ́. Ó sì pa á. Ó sọ pé: "Èyí wà nínú iṣẹ́ Èṣù. Dájúdájú (èṣù) ni ọ̀tá aṣini-lọ́nà pọ́ńńbélé." Ó sọ pé: "Olúwa mi, dájúdájú èmi ti ṣàbòsí sí ẹ̀mí ara mi. Nítorí náà, foríjìn mí." Ó sì foríjìn ín. Dájúdájú Allāhu, Òun ni Aláforíjìn, Àṣàkẹ́-ọ̀run. Ó sọ pé: "Olúwa mi, fún wí pé O ti ṣe ìkẹ́ fún mi, èmi kò níí jẹ́ olùrànlọ́wọ́ fún àwọn ẹlẹ́ṣẹ̀." Nítorí náà, ó di ẹni t'ó ń bẹ̀rù nínú ìlú, ó sì ń retí (ẹ̀hónú ìran Fir'aon). Nígbà náà ni ẹni tí ó wá ìrànlọ́wọ́ rẹ̀ ní àná tún ń lọgun rẹ̀ fún ìrànlọ́wọ́ rẹ̀. Mūsā sọ fún un pé: "Dájúdájú ìwọ ni olùṣìnà pọ́ńńbélé." Àmọ́ nígbà tí ó fẹ́ gbá ẹni tí ó jẹ́ ọ̀tá fún àwọn méjèèjì mú, ẹni náà wí pé: "Mūsā, ṣé o fẹ́ pa mí bí ó ṣe pa ẹnì kan ní àná? O ò gbèrò kan tayọ kí o jẹ́ aláìlójú-àánú lórí ilẹ̀; o ò sì gbèrò láti wà nínú àwọn

alátùn-únṣe.” Ọkùnrin kan sáré dé láti òpin ìlú náà, ó wí pé: “Mūsā, dájúdájú àwọn ìjòyè ń dá ìmọ̀ràn lórí rẹ láti pa ọ́. Nítorí náà, jáde (kúrò nínú ìlú), dájúdájú èmi wà nínú àwọn onímọ̀ràn rere fún ọ.” Ó sì jáde kúrò nínú (ìlú) pẹ̀lú ìpáyà, tí ó ń retí (ẹ̀hónú wọn), ó sì sọ pé: “Olúwa mi, là mí lọ́wọ́ ìjọ alábòsí.” Nígbà tí ó sì dojú kọ ọ̀kánkán ìlú Mọdyan, ó sọ pé: “Ó súnmọ́ kí Olúwa mi fọ̀nà tààrà (sí ìlú Mọdyan) mọ̀ mí.” Nígbà tí ó dé ibi (kànǹga) omi (ìlú) Mọdyan, ó bá ìjọ ènìyàn kan níbẹ̀ tí wọ́n ń fún àwọn ẹran-ọ̀sìn wọn ní omi mu. Lẹ́yìn wọn, ó tún rí àwọn obìnrin méjì kan tí wọ́n ń fà sẹ́yìn (pẹ̀lú ẹran-ọ̀sìn wọn). Ó sọ pé: “Kí l’ó ṣe ẹ̀yin méjèèjì?” Wọ́n sọ pé: “A ò lè fún àwọn ẹran-ọ̀sìn wa ní omi mu títí àwọn adaran bá tó kó àwọn ẹran-ọ̀sìn wọn lọ. Àgbàlagbà arúgbó sì ni bàbá wa.” Ó sì bá wọn fún (ẹran-ọ̀sìn) wọn ní omi mu. Lẹ́yìn náà, ó padà síbi ibòji, ó sì sọ pé: “Olúwa mi, dájúdájú èmi bùkátà sí ohun tí O bá sọ̀kalẹ̀ fún mi nínú oore.” Ọ̀kan nínú àwọn méjèèjì wá bá a, ó sì ń rìn pẹ̀lú ìtìjú, ó sọ pé: “Dájúdájú bàbá mi ń pè ọ́ nítorí kí ó lè san ọ́ ní ẹ̀san omi tí o fún (àwọn ẹran-ọ̀sìn) wa mu.” Nígbà tí ó dé ọ̀dọ̀ rẹ̀, ó sọ ìtàn (ara rẹ̀) fún un. (Bàbá náà) sọ pé: “Má bẹ̀rù. O ti là lọ́wọ́ ìjọ alábòsí.” Ọ̀kan nínú (àwọn ọmọbìnrin) méjèèjì sọ pé: “Bàbá mi o, gbà á síṣẹ́. Dájúdájú ẹni t’ó dára jùlọ tí o lè gbà síṣẹ́ ni alágbára, olùfọkàntán.” Ó sọ pé: “Dájúdájú mo fẹ́ fi ọ̀kan nínú àwọn ọmọbìnrin mi méjèèjì wọ̀nyí fún ọ ní aya lórí (àdéhùn) pé o máa bá mi ṣiṣẹ́ fún ọdún mẹ́jọ. Ṣùgbọ́n tí o bá ṣe é pé ọdún mẹ́wàá, láti ọ̀dọ̀ rẹ nìyẹn. Èmi kò sì fẹ́ kó ìnira bá ọ. Tí Allāhu bá fẹ́, o máa rí i pé mo wà nínú àwọn ẹni rere.” (Mūsā) sọ pé: “(Àdéhùn) yìí wà láàrin èmi àti ìwọ. Èyíkéyìí tí mo bá mú ṣẹ nínú àdéhùn méjèèjì náà, ìwọ kò gbọdọ̀ ṣàbòsí sí mi. Allāhu sì ni Ẹlẹ́rìí lórí ohun tí à ń sọ (yìí).” Nígbà tí Mūsā parí àkókò náà, ó mú ará ilé rẹ̀ rin (ìrìn-àjò). Ó sì rí iná kan ní ẹ̀bá àpáta. Ó sọ fún ará ilé rẹ̀ pé: “Ẹ dúró (síbí ná). Èmi rí iná kan. Ó ṣe é ṣe kí ǹg mú ìró kan wá ba yín láti ibẹ̀ tàbí (kí ǹg mú) ògúnná kan wá nítorí kí ẹ lè rí ohun yẹ́ná.” Nígbà tí ó dé ibẹ̀, A pè é láti ẹ̀gbẹ́ àfonífojì ní ọwọ́ ọ̀tún (rẹ̀) ní àyè ìbùkún láti ibi igi náà. (A sọ pé): “Mūsā, dájúdájú Èmi ni Allāhu, Olúwa gbogbo ẹ̀dá. Ju ọ̀pá rẹ sílẹ̀.” (Ó sì jù ú sílẹ̀). Nígbà tí ó rí i t’ó ń mira bí ẹni pé ejò ni, Mūsā pẹ̀yìn dà, ó ń sá lọ́, kò sì padà. (Allāhu sọ pé): “Mūsā, máa bọ̀ padà, má sì ṣe páyà. Dájúdájú ìwọ wà nínú àwọn olùfàyàbalẹ̀. Ti ọwọ́ rẹ bọ (abíyá láti ibi) ọrùn ẹ̀wù rẹ, ó sì máa jáde ní funfun tí kì í ṣe ti aburú. Pa ọwọ́ rẹ mọ́ra sí (abíyá rẹ) níbi ẹ̀rù. Nítorí náà, àwọn ẹ̀rí méjì nìwọ̀nyí láti ọ̀dọ̀ Olúwa rẹ sí Fir‘aon àti àwọn ìjòyè rẹ̀. Dájúdájú wọ́n jẹ́ ìjọ òbìlẹ̀jẹ́.” (Ànábì Mūsā) sọ pé: “Olúwa mi, dájúdájú èmi pa ẹnì kan nínú wọn. Nítorí náà, mò ń bẹ̀rù pé wọ́n máa pa mí. Àti pé arákùnrin mi, Hārūn, ó dá láhọ́n jù mí lọ. Nítorí náà, rán an níṣẹ́ pẹ̀lú mi, kí ó jẹ́ olùrànlọ́wọ́ tí yóò máa jẹ́rìí sí òdodo ọ̀rọ̀ mi. Dájúdájú èmi ń bẹ̀rù pé wọ́n máa pè mí ní òpùrọ́.” (Allāhu) sọ pé: “A máa fi arákùnrin rẹ kún ọ lọ́wọ́. A ó sì fún ẹ̀yin méjèèjì ní agbára, wọn kò sì níí lè dé ọ̀dọ̀ ẹ̀yin méjèèjì. Pẹ̀lú àwọn àmì Wa, ẹ̀yin méjèèjì àti àwọn t’ó bá tẹ̀lé ẹ̀yin méjèèjì l’ó máa borí.” "(-Al-Qasas:4-35)

"Ni Musa ati Haruna ọmọ iya rẹ wa lọ si ọdọ Fir'aun - ọba onigberaga - tí wọ́n si n pe e lati jọsin fun Allahu, Oluwa gbogbo agbaye:" Fir‘aon wí pé: “Kí ni Olúwa gbogbo ẹ̀dá?” (Ànábì Mūsā) sọ pé: “(Allāhu ni) Olúwa àwọn sánmọ̀ ilẹ̀ àti ohunkóhun t’ó ń bẹ láàárin àwọn méjèèjì (Fir‘aon) wí fún àwọn t’ó wà ní àyíká rẹ̀ pé: “Ṣé ẹ ẹ̀ gbọ́ ọ̀rọ̀ (t’ó ń sọ ni)?” (Ànábì Mūsā) sọ pé: “(Allāhu ni) Olúwa yín àti Olúwa àwọn bàbá yín, àwọn ẹni àkọ́kọ́.” (Fir‘aon) wí pé: “Dájúdájú Òjíṣẹ́ yín èyí tí wọ́n rán si yín, wèrè mà ni.” (Ànábì Mūsā) sọ pé: “(Allāhu ni) Olúwa ibùyọ òòrùn, ibùwọ̀ òòrùn àti ohunkóhun t’ó ń bẹ láàárin àwọn méjèèjì, tí ẹ bá máa ń ṣe làákàyè.” (Fir‘aon) wí pé: “Dájúdájú tí o bá fi lè jọ́sìn fún ọlọ́hun kan yàtọ̀ sí mi, dájúdájú mo máa sọ ọ́ di ara àwọn ẹlẹ́wọ̀n.” (Ànábì Mūsā) sọ pé: “Tí ó bá jẹ́ pé mo mú kiní kan t’ó yanjú wá fún ọ ńkọ́?” (Fir‘aon) wí pé: “Mú un wá nígbà náà tí ìwọ bá wà nínú àwọn olódodo.” Nígbà náà, ó ju ọ̀pá rẹ̀ sílẹ̀, ó sì di ejò pọ́nńbélé. Ó tún fa ọwọ́ rẹ̀ yọ, ó sì di funfun (gbòlà) fún àwọn olùwòran. (Fir‘aon) wí fún àwọn ìjòyè tí wọ́n wà ní àyíká rẹ̀ pé: “Dájúdájú èyí ni onímọ̀ nípa idán pípa. Ó fẹ́ ko yín kúrò lórí ilẹ̀ yín ni. Kí ni ohun tí ẹ máa mú wá ní ìmọ̀ràn?” Wọ́n wí pé: "Dá òun àti arákùnrin rẹ̀ dúró ná, kí o sì rán àwọn akónijọ sí àwọn ìlú (pé) kí gbogbo onímọ̀ nípa idán pípa wá bá ọ." Wọ́n sì kó àwọn òpìdán jọ ní àsìkò tí wọ́n fi àdéhùn sí ní ọjọ́ tí (gbogbo ìlú) ti mọ̀. Wọ́n sì wí fún àwọn ènìyàn pé: "Ṣé ẹ̀yin máa kó jọ (síbẹ̀) bí? Nítorí kí á lè tẹ̀lé àwọn òpìdán tí ó bá jẹ́ pé àwọn ni olùborí." Nígbà tí àwọn òpìdán dé, wọ́n wí fún Fir‘aon pé: “Ǹjẹ́ owó-ọ̀yà kan wà fún wa, tí ó bá jẹ́ pé àwa gan-an la jẹ́ olùborí?” (Fir‘aon) wí pé: “Bẹ́ẹ̀ ni, dájúdájú nígbà náà ẹ máa wà nínú àwọn alásùn-únmọ́ (mi).” (Ànábì) Mūsā sọ fún wọn pé: “Ẹ ju ohun tí ẹ fẹ́ jù sílẹ̀.” Wọ́n sì ju àwọn okùn wọn àti ọ̀pá wọn sílẹ̀. Wọ́n wí pé: “Pẹ̀lú ògo Fir‘aon, dájúdájú àwa, àwa ni olùborí.” Nígbà náà, (Ànábì) Mūsā ju ọ̀pá rẹ̀ sílẹ̀. Ó sì ń gbé ohun tí wọ́n pa níró kalẹ̀ mì kálókáló. Nítorí náà, iṣẹ́ ìyanu (Ànábì Mūsā) mú àwọn òpìdán wó lulẹ̀, tí wọ́n forí kanlẹ̀ (fún Allāhu). Wọ́n sọ pé: "A gbàgbọ́ nínú Olúwa gbogbo ẹ̀dá, Olúwa (Ànábì) Mūsā àti Hārūn." Fir‘aon wí pé: “Ẹ gbà Á gbọ́ ṣíwájú kí ǹg tó yọ̀nda fun yín! Dájúdájú òun ni àgbà yín tí ó kọ yín ní idán pípa. Láìpẹ́ ẹ̀ ń bọ̀ wá mọ̀. Dájúdájú mo máa gé ọwọ́ yín àti ẹsẹ̀ yín ní ìpasípayọ. Lẹ́yìn náà, dájúdájú mo máa kan gbogbo yín mọ́gi.” (Àwọn òpìdán) sọ pé: “Kò sí ìnira fún wa! Dájúdájú àwa yó sì fàbọ̀ sí ọ̀dọ̀ Olúwa wa. Dájúdájú àwa n retí pé Olúwa wa yóò ṣe àforíjìn àwọn àṣìṣe wa fún wa nítorí pé àwa jẹ́ ẹni àkọ́kọ́ (tí ó jẹ́) onígbàgbọ́ òdodo.” A fi ìmísí ránṣẹ́ sí (Ànábì) Mūsā pé: “Mú àwọn ẹrúsìn Mi rìn ní òru (nítorí pé) dájúdájú wọn yóò lépa yín.” Fir‘aon sì rán àwọn akónijọ sínú àwọn ìlú (láti sọ pé): "Dájúdájú àwọn (ọmọ ’Isrọ̄’īl) wọ̀nyí, ìjọ péréte díẹ̀ ni wọ́n. Àti pé dájúdájú wọ́n ti

ṣe ohun t’ó ń bí wa nínú. Dájúdájú gbogbo wa ni kí á sì wà tìfura-tìfura." Nítorí náà, A mú (ìjọ Fir‘aon) jáde kúrò nínú àwọn ọgbà oko àti ìṣẹ́lẹ̀rú omi, àti àwọn àpótí-ọrọ̀ àti ibùjókòó àpọ́nlé. Báyẹn (lọ̀rọ̀ rí). A sì jogún rẹ̀ fún àwọn ọmọ ’Isrọ̄’īl. Wọ́n sì lépa wọn ní àsìkò tí òòrùn yọ. Nígbà tí ìjọ méjèèjì ríra wọn, àwọn ìjọ (Ànábì) Mūsā sọ pé: “Dájúdájú wọn yóò lé wa bá.” (Ànábì) Mūsā sọ pé: “Rárá, dájúdájú Olúwa mi ń bẹ pẹ̀lú mi. Ó sì máa fi ọ̀nà mọ̀ mí.” A sì fi ìmísí ránṣẹ́ sí (Ànábì) Mūsā pé: “Fi ọ̀pá rẹ na agbami òkun.” (Ó fi nà á). Ó sì pín (sí ọ̀nà méjìlá). Ìpín kọ̀ọ̀kan sì dà bí àpáta ńlá. A sì mú ìjọ kejì (ìyẹn, ìjọ Fir‘aon) súnmọ́ ibẹ̀ yẹn. A gba (Ànábì) Mūsā àti gbogbo àwọn t’ó ń bẹ pẹ̀lú rẹ̀ là pátápátá. Lẹ́yìn náà, A tẹ ìjọ kejì rì (sínú agbami). Dájúdájú àmì wà nínú ìyẹn. Síbẹ̀síbẹ̀ ọ̀pọ̀lọ́pọ̀ wọn kò jẹ́ onígbàgbọ́ òdodo. Dájúdájú Olúwa rẹ, Òun mà ni Alágbára, Àṣàkẹ́-ọ̀run. (Ash-Shu'ara:23-67)
Nigba ti Fir'aun mọ pe  omi ti fẹ́ tẹ ẹ ri, o sọ pe mo gbagbọ pe ko si ọlọhun kankan ti ìjọsìn tọ si ni ododo ayafi Ẹni ti awọn ọmọ Israeli gbagbọ ninu Rẹ. Allahu ti ọla Rẹ ga sọ pe:" Ṣé nísinsìn yìí, tí ìwọ ti yapa ṣíwájú, tí o sì wà nínú àwọn òbìlẹ̀jẹ̀? "Nítorí náà, ní òní ní A óò gbé òkú rẹ jáde sí orí ilẹ̀ téńté nítorí kí o lè jẹ́ àmì (fèyíkọ́gbọ́n) fún àwọn t’ó ń bọ̀ lẹ́yìn rẹ. Dájúdájú ọ̀pọ̀lọ́pọ̀ nínú àwọn ènìyàn mà ni afọ́nú-fọ́ra nípa àwọn āyah Wa."( Yunus:91-92)
Allāhu sì jogún àwọn ibùyọ òòrùn lórí ilẹ̀ ayé àti ibùwọ̀ òòrùn rẹ̀, tí A fi ìbùnkún sí, fún àwọn ènìyàn tí wọ́n fojú tínrín (ìjọ Musa). Ó sì pa ohun tí Fir‘aon àti ìjọ rẹ̀ ń ṣe nísẹ́ àti ohun tí wọ́n ń kọ́ nílé run
"Lẹyin naa Allahu sọ iwe taoreeta kalẹ fun Anọbi Musa, iwe ti o se wipe imọna n bẹ nibẹ fun awọn eeyan ati imọlẹ kan ti n tọka wọn lọ sí nkan ti Allahu fẹ ti O si tun yọnu si, àti pé alaye nkan ẹtọ ati nkan eewọ ti o jẹ dandan lori awọn ọmọ Ísírẹ́lì lati tẹle n bẹ nibẹ pẹlu."
"Lẹyin naa Anọbi musa ku- ki alaafia maa ba a- Allahu si gbe ọpọlọpọ ninu awon Anọbi dide si awọn ijọ rẹ -awọn ọmọ Ísírẹ́lì- lẹyin rẹ, ti wọn n tọka wọn si oju ọna ti o tọ́, gbogbo ìgbà tí Anọbi kan ba ti ku ni Anọbi míràn maa wa lẹyin rẹ"
"Allahu sọ itan apa kan ninu wọn fun wa gẹ́gẹ́ bíi itan Anọbi Daud ati Sulaiman ati Ayub ati Zakariyau, ko si sọ itan ọpọlọpọ ninu wọn fun wa, lẹyin naa Allahu pari àwọn Anọbi ti O ran si awọ́n ọmọ Ísírẹ́lì lori Anọbi Isa ọmọ Maryam (ki alaafia maa ba a), ẹni ti o ṣe pe gbogbo igbesi aaye rẹ kun fun àwọn arisami iyanu, bẹrẹ lati igba bibi rẹ titi ti Allahu fi gbe e lọ si sanmọ".
"Bí ọjọ́ ṣe n gorí ọjọ́ ni Taoreeta ti Allahu sọkalẹ fun Anọbi Musa fi ojú winá àyípadà ati jijirọ lati ọwọ àwọn Yehudi ti wọn ro pe awọn ni ọmọlẹyin Anọbi Musa, ti Anọbi Musa si bọpa bọsẹ kúrò lára wọn, àti pé Taoreeta ti o wa lọ́dọ̀ wọn kii ṣe eyi ti a sọkalẹ lati ọdọ Allahu nipa pe wọn ti fi awọn nkan ti ko bójú mu ki o ti ọdọ Allahu wa sinu ẹ, wọn wa royin Allahu nibẹ pẹlu iroyin adinku ati aimọkan ati lilẹ- ti Allahu si ga gan tayọ awon ọrọ ti wọn n sọ, Allahu ti ọla Rẹ ga sọ nipa iroyin wọn pe:" Nítorí náà, ègbé ni fún àwọn t’ó ń fi ọwọ́ ara wọn kọ Tírà, lẹ́yìn náà tí wọ́n ń wí pé: “Èyí wá láti ọ̀dọ̀ Allāhu.” Nítorí kí wọ́n lè tà á ní owó pọ́ọ́kú. Ègbé ni fún wọn sẹ́ nípa ohun tí ọwọ́ wọn kọ. Ègbé sì ni fún wọn pẹ̀lú nípa ohun tí wọ́n ń ṣe níṣẹ. [Al-Baqarah:79]"

## "Ojiṣẹ Allahu, Isa (ki alaafia maa ba a)."

"Maryam Wúńdíá ti o mọ, tii ṣe ọmọbinrin Imran jẹ ọkan ninu awọn olujọsin ti o tẹle awọn aṣẹ Allahu ti a sọ kalẹ fun awọn anọbi lẹyin Musa, o si wa lati inu idile ti Allahu ṣẹsa lori awọn ẹda." Dájúdájú Allāhu ṣa Ādam, Nūh, ará ilé ’Ibrọ̄hīm àti ará ilé ‘Imrọ̄n lẹ́ṣà lórí àwọn ẹ̀dá (àsìkò tiwọn). Aal-Imraan 33 "Awọn Malaika fun un ni iro nipa bi Allahu ṣe sa a lẹsa" (Ẹ rántí) nígbà tí àwọn mọlāika sọ pé: “Mọryam, dájúdájú Allāhu ṣà ọ́ lẹ́ṣà. Ó fọ̀ ọ́ mọ́. Ó sì ṣà ọ́ lẹ́ṣà lórí àwọn obìnrin ayé (àsìkò tìrẹ). Mọryam, tẹ̀lé àṣẹ Olúwa rẹ. Forí kanlẹ̀ fún Un. Kí o sì dáwọ́ tẹ orúnkún pẹ̀lú àwọn olùdáwọ́tẹ-orúnkún (lórí ìrun). "(Aal-Imran:Ayah 42-43)"
"Lẹyin naa, Allahu- mimọ ni fún Un ti ọla Rẹ ga- ṣalaye fun wa bi O ṣe ṣeda Anọbi Isa ninu ile ọmọ Maryam láìní baba, gẹ́gẹ́ bí Allahu ṣe sọ pe: sọpe Sọ ìtàn Mọryam tí ó wà nínú al-Kur’ān. (Rántí) nígbà tí ó yẹra kúrò lọ́dọ̀ àwọn ènìyàn rẹ̀ sí àyè kan ní ìlà òòrùn. Ó mú gàgá kan (láti fi ara rẹ̀ pamọ́) fún wọn. A sì rán mọlāika Wa sí i. Ó sì fara hàn án ní àwòrán abara pípé. (Mọryam) sọ pé: “Èmi sá di Àjọkẹ́-ayé kúrò lọ́dọ̀ rẹ, tí o bá jẹ́ olùbẹ̀rù (Allāhu).” (Mọlāika) sọ pé: “Èmi ni Òjíṣẹ́ Olúwa rẹ, (Ó rán mi sí ọ) pé kí ñg fún ọ ní ọmọkùnrin mímọ́ kan.” Ó sọ pé: "Báwo ni mo ṣe máa ní ọmọ nígbà tí abara kan kò fọwọ́ kàn mí, tí èmi kò sì jẹ́ alágbèrè." (Mọlāika) sọ pé: “Báyẹn l’ó máa rí.” Olúwa rẹ sọ pé: “Ó rọrùn fún mi. Àti pé nítorí kí Á lè ṣe é ní àmì fún àwọn ènìyàn ni. Ó sì jẹ́ ìkẹ́ láti ọ̀dọ̀ Wa. Ó tún jẹ́ ọ̀rọ̀ tí A ti parí.” Nítorí náà, ó lóyún rẹ̀. Ó sì yẹra pẹ̀lú rẹ̀ sí àyè kan t’ó jìnnà. "Ìrọbí ọmọ sì mú un wá sí ìdí igi dàbínù. Ó sọ pé: “Háà! Kí ñg ti kú ṣíwájú èyí, kí ñg sì ti di ẹni tí wọ́n ti gbàgbé pátápátá" Nígbà náà, (mọlāika) pè é láti ìsàlẹ̀ ọ̀dọ̀ rẹ̀ pé: "Má ṣe banújẹ́. Dájúdájú Olúwa rẹ ti ṣe odò kékeré kan sí ìsàlẹ̀ ọ̀dọ̀ rẹ. Mi igi dàbínù náà sọ́dọ̀ rẹ, kí dàbínú tútù, tó tó ká jẹ sì máa jábọ́ sílẹ̀ fún ọ. Nítorí náà, jẹ, mu kí ojú rẹ sì tutù. Tí o bá sì rí ẹnì kan nínú abara, sọ fún un pé: "Dájúdájú mo jẹ́jẹ̀ẹ́ ìkẹ́nuró fún Àjọkẹ́-ayé. Nítorí náà, mi ò níí bá ènìyàn kan sọ̀rọ̀ ní òní." Ó sì mú ọmọ náà wá bá àwọn ènìyàn rẹ̀ (ní ẹni tí) ó gbé e dání. Wọ́n sọ pé: "Mọryam, dájúdájú o ti gbé

ñǹkan aburú ńlá wá. Arábìnrin Hārūn, bàbá rẹ kì í ṣe ènìyàn burúkú. Àti pé ìyá rẹ kì í ṣe alágbèrè." Ó sì tọ́ka sí ọmọ náà. Wọ́n sọ pé: “Báwo ni a ó ṣe bá ẹni t’ó wà lórí ìtẹ́, t’ó jẹ́ ọmọ òpóǹló sọ̀rọ̀?” (Ọmọ náà) sọ̀rọ̀ pé: "Dájúdájú ẹrú Allāhu ni èmi. (Allāhu) fún mi ni Tírà. Ó sì ṣe mí ní Ànábì. Ó ṣe mí ní ẹni ìbùkún ní ibikíbi tí mo bá wà. Ó pa mí láṣẹ ìrun kíkí àti Zakāh yíyọ lódiwọ̀n ìgbà tí mo bá wà nípò alààyè (lórí ilẹ̀ ayé). (Ó ṣe mí ní) oníwà rere sí ìyá mi. Kò sì ṣe mí ní ajẹninípá, olórí burúkú. Àlàáfíà ni fún mi ní ọjọ́ tí wọ́n bí mi, àti ní ọjọ́ tí mo máa kú àti ní ọjọ́ tí Wọ́n á gbé mi dìde ní alààyè (ní Ọjọ́ Àjíǹde)." Ìyẹn ni (Ànábì) ‘Īsā ọmọ Mọryam. (Èyí jẹ́) ọ̀rọ̀ òdodo tí àwọn (yẹhudi àti nasara) ń ṣeyèméjì nípa rẹ̀. Kò yẹ fún Allāhu láti sọ ẹnì kan kan di ọmọ. Mímọ́ ni fún Un. Nígbà tí Ó bá pèbùbù kiní kan, Ó kàn máa sọ fún un pé: "Jẹ́ bẹ́ẹ̀." Ó sì máa jẹ́ bẹ́ẹ̀. Àti pé dájúdájú Allāhu ni Olúwa mi àti Olúwa yín. Nítorí náà, ẹ jọ́sìn fún Un. Èyí ni ọ̀nà tààrà. "[Surah Maryam:16-36]"

"Nígbà tí Anọbi Isa- ki alaafia maa ba a- pe awọn èèyàn lọ sibi ijọsin fun Allahu, awọn ti wọn da a lohun jẹ ipe rẹ, sugbọn ọpọlọpọ wọn kọjalẹ, o si tẹsiwaju nibi pípe awọn èèyàn lọ sibi ijọsin fún Allahu; sugbọn ọpọ ninu wọn ni wọ́n ṣe aigbagbọ si i, ti wọn si mú un ní ọ̀tá, kódà wọn tun pejọ le e lórí, wọn si gbinyanju lati pa a, Allahu ti ọla Rẹ ga sọ fun un pe:" (Ẹ rántí) nígbà tí Allāhu sọ pé: “‘Īsā, dájúdájú Mo máa gbà ọ́ (kúrò lọ́wọ́ wọn).1 Mo máa gbé ọ wá sókè lọ́dọ̀ Mi. Mo sì máa fọ̀ ọ́ mọ́ lọ́dọ̀ àwọn t’ó ṣàì gbàgbọ́. Aal-Imraan 55

"Nitori naa, Allahu gbe aworan Anobi Isa wọ ọ̀kan ninu awọn ti n lepa rẹ, ni wọn ba mu u, ni ero pe Anọbi Isa ọmọ Maryam ni, ki alaafia maa ba a, wọn pa a, wọn si kàn án mọ agbelebu. Ni ti Anọbi Isa ọmọ Maryam tii ṣe ojiṣẹ, Allahu gbe e soke lọ si ọdọ Rẹ, ṣùgbọ́n ki o to kuro ni aye, o sọ fun awọn ẹmẹwa rẹ pe Ọlọhun yoo ran ojiṣẹ mìíràn ti o n jẹ Ahmad, Allahu yoo tan ẹsin ka pelu rẹ, Allahu ti ọla rẹ ga sọ pe:" (Rántí) nígbà tí ‘Īsā ọmọ Mọryam sọ pé: "Ẹ̀yin ọmọ ’Isrọ̄’īl, dájúdájú èmi ni Òjíṣẹ́ Allāhu si yín. Mò ń fi ohun t’ó jẹ́ òdodo rinlẹ̀ nípa èyí t’ó ṣíwájú mi nínú Taorāh. Mo sì ń mú ìró-ìdùnnú wá nípa Òjíṣẹ́ kan t’ó ń bọ̀ lẹ́yìn mi. Orúkọ rẹ̀ ni ’Ahmọd." "(As-Saf:6)"

"Lẹ́yìn náà, nígbà tí ó yá, awọn ọmọlẹhin Anọbi Isa pin, ẹgbẹ kan jade ninu wọn ti wọn kọja aala nipa rẹ, ti wọn si lero pe Anọbi Isa ni ọmọ Allahu- ti Allāhu si ga gan ju ohun ti wọn n sọ lọ- àti pé nkan ti o gbe iru ero bẹ́ẹ̀ sí wọn lọkan ni riri Anọbi Isa ni ẹni ti a bi laini baba, Allahu fun wa ni iro nipa ìyẹn pé:" Dájúdájú irú ‘Īsā lọ́dọ̀ Allāhu dà bí irú Ādam; (Allāhu) dá a láti ara erùpẹ̀. Lẹ́yìn náà, Ó sọ pé: “Jẹ́ bẹ́ẹ̀.” Ó sì jẹ́ bẹ́ẹ̀. Aal Im’raan/59 "Ṣiṣẹda Anọbi Isa láìní baba ko jẹ iyalẹnu tó ṣiṣẹẹda Adamọ láìní baba àti iya."

"Fun idi eyi, Allahu ba awọn ọmọ Ísírẹ́lì sọrọ ninu Kuraani lati jina si ìṣe Kèfèrí yìí pẹlu ọrọ Rẹ pe:" Ẹ̀yin ahlul-kitāb, ẹ má ṣe tayọ ẹnu-àlà nínú ẹ̀sìn yín, kí ẹ sì má sọ ohun kan nípa Allāhu àfi òdodo. Òjíṣẹ́ Allāhu ni Mọsīh ‘Īsā ọmọ Mọryam. Ọ̀rọ̀ Rẹ̀ (kun fayakūn) tí Ó sọ ránṣẹ́ sí Mọryam l’Ó sì fi ṣẹ̀dá rẹ̀. Ẹ̀mí kan (tí Allāhu ṣẹ̀dá) láti ọ̀dọ̀ Rẹ̀ sì ni (Mọsīh ‘Īsā ọmọ Mọryam). Nítorí náà, ẹ gbàgbọ́ nínú Allāhu àti àwọn Òjíṣẹ́ Rẹ̀. Ẹ yé sọ mẹ́ta (lọ́kan) mọ́. Kí ẹ jáwọ́ níbẹ̀ ló jẹ́ oore fun yín. Allāhu nìkan ni Ọlọ́hun, Ọ̀kan ṣoṣo (tí ìjọ́sìn tọ́ sí). Ó mọ́ tayọ kí Ó ní ọmọ. TiRẹ̀ ni ohunkóhun t’ó wà nínú àwọn sánmọ̀ àti ohunkóhun t’ó wà nínú ilẹ̀. Allāhu sì tó ní Alámòjúútó. Mọsīh kò kọ̀ láti jẹ́ ẹrú fún Allāhu. Bẹ́ẹ̀ náà ni àwọn mọlāika tí wọ́n súnmọ́ Allāhu. Ẹnikẹ́ni tí ó bá kọ̀ láti jọ́sìn fún Un, tí ó tún ṣègbéraga, (Allāhu) yóò kó wọn jọ papọ̀ pátápátá sí ọ̀dọ̀ Rẹ̀. Ní ti àwọn t’ó gbàgbọ́ ní òdodo, tí wọ́n sì ṣiṣẹ́ rere, (Allāhu) yóò san wọ́n ní ẹ̀san rere wọn. Ó sì máa ṣe àlékún fún wọn nínú oore àjùlọ Rẹ̀. Ní ti àwọn t’ó bá sì kọ̀ (láti jọ́sìn fún Allāhu), tí wọ́n sì ṣègbéraga, (Allāhu) yóò jẹ wọ́n níyà ẹlẹ́ta-eléro. Wọn kò sì níí rí alátìlẹ́yìn tàbí aláràǹṣe kan lẹ́yìn Allāhu. "[An-Nisa:171-173]"

Allahu maa sọ fun Anọbi Isa ni ọjọ igbedide pe:" (Rántí) nígbà tí Allāhu sọ pé: “‘Īsā ọmọ Mọryam, ṣé ìwọ l’o sọ fún àwọn ènìyàn pé: "Ẹ mú èmi àti ìyá mi ní ọlọ́hun méjì tí ẹ óò máa jọ́sìn fún lẹ́yìn Allāhu?" Ó sọ pé: "Mímọ́ ni fún Ọ, kò tọ́ fún mi láti sọ ohun tí èmi kò lẹ́tọ̀ọ́ (sí láti sọ). Tí mo bá sọ bẹ́ẹ̀, O kúkú ti mọ̀. O mọ ohun tí ń bẹ nínú ẹ̀mí mi. Ǹg ò sì mọ ohun tí ń bẹ nínú ẹ̀mí Rẹ. Dájúdájú Ìwọ ni Onímọ̀ nípa àwọn ìkọ̀kọ̀. Èmi kò sọ ohun kan fún wọn bí kò ṣe ohun tí O pa mí láṣẹ rẹ̀ pé: "Ẹ jọ́sìn fún Allāhu, Olúwa mi àti Olúwa yín." Mo sì jẹ́ ẹlẹ́rìí lórí wọn níwọ̀n ìgbà tí mò ń bẹ láàárin wọn. Ṣùgbọ́n nígbà tí O gbà mí kúrò lọ́wọ́ wọn, Ìwọ ni Olùṣọ́ lórí wọn. Ìwọ sì ni Arínú-róde gbogbo ñǹkan. Tí O bá jẹ wọ́n níyà, dájúdájú ẹrú Rẹ ni wọ́n. Tí O bá sì forí jìn wọ́n, dájúdájú Ìwọ, Ìwọ ni Alágbára, Ọlọ́gbọ́n. Allāhu sọ pé: “Èyí ni ọjọ́ tí òdodo àwọn olódodo yóò ṣe wọ́n ní àǹfààní. Àwọn Ọgbà Ìdẹra kan tí àwọn odò ń ṣàn ní ìsàlẹ̀ rẹ̀ ń bẹ fún wọn. Olùṣegbére ni wọ́n nínú rẹ̀ títí láéláé. Allāhu yọ́nú sí wọn. Wọ́n sì yọ́nú sí (ohun tí Allāhu fún wọn). Ìyẹn ni èrèǹjẹ ńlá. Suuratul Maaidah 116-119

"Nítorí náà, Mèsáyà Anọbi Isa ọmọ Mọryam- ki àlàáfíà máa bá a- bọpa bọsẹ kúrò lọdọ awọn miliọnu wọnyi ti wọn n pe ara wọn ni Kristẹni ti wọn n lero pe ọmọ ẹyin Anọbi Isa ni awọn.”

# 3- Muhammad ojiṣẹ Allahu (ìgbẹ̀yìn àwọn Anọbi ati awọn Ojiṣẹ)

“Lẹhin gbigbe Anọbi Isa- ki àlàáfíà maa ba a- lọ sókè, o pẹ gan lẹ́yìn ìgbà yẹn ti o to nǹkan bii ọgọ́rùn-ún mẹ́fà ọdún, ni iyẹgẹrẹ àwọn eniyan Kuro nibi imọna ba peléke si, ni aigbagbọ ati anù ba tan kalẹ laarin wọn, ati ìjọsìn fun elomiran yatọ si Allahu ti ọla Rẹ ga." "Nítorí náà, Ọlọhun gbé Muhammad- ki ikẹ ati ọla Ọlọhun maa ba a- dìde ni Mẹka, ni ilẹ Hijaaz pẹlu itọsọna ati ẹsin ododo; lati jọsin fun Allahu nikan laisi orogun fún Un, O si fun un ni awọn àmì ati iṣẹ iyanu ti o n tọka si ijẹ-anọbi rẹ ati ijẹ-ojiṣẹ rẹ, O si fi ṣe ìparí awọn ojiṣẹ, O si fi ẹsin rẹ ṣe ipari awọn ẹsin, O si sọ ọ kuro nibi ijirọ ati iyipada titi di opin igbesi aye ati ọjọ igbedide, tani Muhammad? ” "Àwọn wo ni ìjọ rẹ?" Bawo ni Allahu se rán an nisẹ?" "Kini awọn ẹ̀rí ijẹ anọbi rẹ?" "Kini àlàyé itan igbesi-aye rẹ ní ẹkunrẹrẹ" “Eyi ni ohun ti a maa gbiyanju lati ṣalaye rẹ pẹlu iyọnda Allahu ninu awọn oju-iwe kukuru wọnyi.”

## "1- Iran rẹ ati iyi rẹ "

“Oun náà ni Muhammad ọmọ Abdullah ọmọ Abdul Muttọlib ọmọ Haashim ọmọ Abd Manaaf ọmọ Qusayy ọmọ Kilaab, iran rẹ si tan mọ Ismail ọmọ Ibrahim- ki alaafia máa bá wọn- lati inu ìdílé Quraish, àti pé Quraish jẹ iran awọn Larubawa, wọn bi i ni Meka ni ọdun 571 si bibi Anọbi Isa (ki alaafia máa bá a). ” "Baba rẹ ku nigba ti o wa ninu ikùn ìyá rẹ̀, o dàgbà ni ọmọ orukan labẹ amojuto baba-baba rẹ Abdul Muttọlib. Lẹyin naa nígbà tí baba-baba rẹ ku, aburo baba rẹ Abu Talib ṣe amojuto rẹ."

## "2- Awọn iroyin rẹ"

“A mẹ́nu ba pe ojiṣẹ ti a ti yan lati ọdọ Allahu gbọdọ wa ni òkè téńté níbi gíga ẹmi, otitọ ọrọ sisọ, ati ihuwa ti o dara, bẹ́ẹ̀ náà ni Muhammad- ki ikẹ ati ọla Ọlọhun máa bá a- ṣe ri, o dàgbà ni olotitọ, ẹni tí a le fi ọkàn tán, oniwadáadáa, ti o dantọ ni ahọn, tí ẹni tí ó wà ní tòsí àti ọ̀nà ti o jìnà nífẹ̀ẹ́ sí, ti àwọn ìjọ rẹ maa n babara rẹ, ti wọn si maa n bọwọ fun un laarin wọn. Wọn o ki n pe e ni alajẹ kankan yatọ si Al-Amiin (olufọkantan), wọn si maa n fi àwọn àgbàfipamọ́ si i lọ́dọ̀ tí wọ́n bá fẹ́ ṣe ìrìn-àjò.

"Ni afikun si awọn iwa rere rẹ, o jẹ ẹni tí ó rẹwa, kii sú ojú láti maa wò ó, oju rẹ maa n kọ yànràn, ojú rẹ méjèèjì sì fẹ̀, irun ipenpeju rẹ si gùn, irun ori rẹ dudu, ejika rẹ méjèèjì sì fẹ̀, kò ga kò kúrú, o wa láàrin méjì, ṣùgbọ́n o sunmọ giga. Ọkan ninu awọn saabe rẹ ròyìn rẹ pe: “Mo ri ojiṣẹ Ọlọhun- ki ikẹ ati ọla Ọlọhun maa ba a- ninu aṣọ ilu Yemen, emi ko si ri nǹkan kan ti o dara ju u lọ.” "Ati pe o jẹ alaimọọkọ-mọọka, o wa lati inu ìjọ kan ti ko mọọkọ-mọọka, ẹni tí ó le kọ dáadáa ti o le ka dáadáa kéré nínú wọn. Ṣugbọn ọpọlọpọ wọn mú berebere, wọn si yára ní ọgbọ́n inú.

## "3- Kuraishi ati awọn larubawa".

"Awọn ijọ Anọbi Muhammad- ki ikẹ ati ọla Ọlọhun máa bá a- ati awọn mọlẹbi rẹ jẹ olùgbé Mẹka alapọnle ní ẹgbẹ ile ọwọ ati Ka'bah abiyi ti Allahu pa Anọbi Ibrahim- ki alaafia o maa ba a- ati ọmọ rẹ Ismaheel laṣẹ lati kọ ọ"

"Ṣugbọn lẹ́yìn ìgbà tí ó pẹ́, wọn yẹgẹrẹ kuro ninu ẹsin Anọbi Ibrọheem (ijọsin mimọ fun Allahu) wọn si gbe- awọn ati awọn ìdílé ti o wa ni ayika wọn- awọn oriṣa kalẹ latara okuta, igi, ati wura si ayika Kaaba, wọn si sọ wọn di mimọ, wọn si tun ni adisọkan pe anfaani ati ìpalára n bẹ lọ́wọ́ wọn, wọn si da awọn ààtò ìjọsìn kan silẹ fun awọn oriṣa naa, ninu eyi ti o gbajumọ ju ninu wọn ni ooṣa hubal ti o ṣe pe oun ni o tobi julọ ninu wọn ni ti iyi". “Ni afikun si awọn oriṣa ati awọn igi mìíràn tí kò si ni Mẹka ti wọn n jọsin fun dipo Allahu, ti wọn si maa n bàbàrà wọn gan, bíi Al-Laat, Al-Uzza ati Manaat, àti pé igbesi aye wọn pẹlu awọn agbegbe ti o wa ni ayika wọn kun fun igberaga, ati iyanran, ati motomoto, ati itayọ ẹnu-ala si awọn mìíràn, ati awọn ogun ti ó le, bí ó ti lẹ jẹ pé wọn ni awọn iwa rere kan bii igboya, ṣíṣe apọnle alejo, ati otitọ ọrọ ati awọn miiran.”

## "4- Igbedide Anọbi Muhammad (ki ikẹ ati ọla Ọlọhun máa bá a)

“Nigba ti Anọbi- ki ikẹ ati ọla Ọlọhun maa ba a- to ogoji ọdun, o wa ninu koto Hira ni ita Mẹka, ni imisi akọkọ lati ọrun lati ọdọ Allahu sọkalẹ fun un, Malaika Jibreel wa si ọdọ rẹ, o si fún un papọ̀, o si wi fun un pe: Kà, o sọ pe: Mi o mọ ọn kà. Lẹyin naa, o tun fun un papọ ni ẹẹkeji, titi ti ìnira yẹn fi de ibi pe ko le fi ara dà á mọ́, o tun sọ fun un pe: Kà, o sọ pe: Mi o mọ ọn kà, o tun fun un papọ ni ẹẹkẹta, titi ti inira yẹn fi tun le si i de ibi pe ko le fi ara da a mọ, o wa sọ pe: Ka, o sọ pe: Kini ki n ka? O sọ pe:" Ké (al-Kur’ān) pẹ̀lú orúkọ Olúwa rẹ, Ẹni tí Ó dá ẹ̀dá. Ó ṣẹ̀dá ènìyàn láti ara ẹ̀jẹ̀ dídì. Ké e. Olúwa rẹ ni Alápọ̀n-ọ́nlé jùlọ. Ẹni tí Ó fi ìmọ̀ nípa gègé ìkọ̀wé mọ ènìyàn. Ó fi ìmọ̀ tí ènìyàn kò mọ̀ mọ̀ ọ́n. "(Al-Alaq:1-5)"

"Lẹyin naa ni Malaika Jibreel lọ, o si fi i silẹ, ni Ojiṣẹ Allahu- ki ikẹ ati ọla Ọlọhun máa bá a- pada si ile rẹ ati si ọdọ iyawo rẹ ni ẹni tí n bẹru. O sọ fun iyawo rẹ Khọdija pe: Da aṣọ bo mi; nitori emi n paya lórí ẹ̀mí ara mi, iyawo rẹ sọ fun un pe: Rara, mo fi Ọlọhun bura, Allahu ko nii dójú ti ọ lailai; nítorí pé dájúdájú ìwọ n da ibi pọ, àti pé o maa n ba ọ̀lẹ gbe ẹru rẹ nibi ti o ti wúwo, o tun maa n ṣe iranlọwọ nígbà tí àdánwò bá ṣẹlẹ̀ sí àwọn ènìyàn. eeyan o tun ran ododo lọwọ"

"Lẹ́yìn náà ni Jibreel wa sọdọ rẹ ni aworan gẹ́gẹ́ bí Allahu ṣe da a, ti o di oju-ọrun, o sọ pe: Irẹ Muhammad, emi ni Jibreel, iwọ si ni ojiṣẹ Allahu.
"Lẹ́yìn náà ni imisi n sọkalẹ lati ọrun ni tẹle-n-tẹle, ti o n paṣẹ fun Ojiṣẹ lati pe awọn ijọ rẹ lati jọsin fun Allahu nikan, ati lati kilọ fun wọn kúrò níbi ẹbọ ati aigbagbọ, ni o wa bẹrẹ si ni pe awọn ijọ rẹ ni ọkọọkan bi wọn ṣe sunmọ ọn sí lati wọ inu ẹsin Islam. Ẹni tí o kọkọ gba a gbọ ni iyawo rẹ khọdijah ọmọ khuwaileed, ati ọrẹ rẹ tii ṣe Abubakr As-siddiik, ati ọmọ ẹgbọn baba rẹ Aliyu ọmọ Abu tọọlib."
"Lẹ́yìn ìgbà tí awọn ijọ rẹ mọ si ipepe rẹ, wọn bẹrẹ lati maa koju rẹ, wọn si n dete si i, wọn si tun n ba a ṣe ọ̀tá. O jade si awọn ijọ rẹ ni ọjọ kan, ni o ba képè wọn pẹ̀lú ohùn rara pé: "WAA SOBAAHAAH", eleyii ni gbólóhùn ti ẹni ti o ba fẹ ko awọn eeyan jọ maa n sọ, ni awọn ijọ rẹ ba bẹrẹ si ni kojọ lati tẹti si nkan ti o fẹ ba wọn sọ, nígbà tí wọn wa kojọ, o sọ fun wọn pe: "Ti mo ba sọ fun yin pe ọta maa dìgbò lù yín ní àárọ̀ tàbí ni irọlẹ, ǹjẹ́ ẹ maa gba mi gbọ bi?", wọn dahun pe: A o ba ọrọ rẹ ni irọ ri, o wa sọ pe: Emi ni olukilọ fun yin kuro nibi ìyà kan ti o n bọ̀ ti le koko. Báyìí ni ẹgbọn baba rẹ Abu laabi- ti o jẹ okan ninu awọn ẹgbọn baba rẹ ti oun ati iyawo rẹ jẹ awọn to le ju ni ọta fun ojiṣẹ Ọlọhun- ki ikẹ ati ọla Ọlọhun máa bá a- sọ pe: Ègbé ni fún ọ, ṣé tori eyi ni o fi ko wa jọ?Nitori idi eyi ni Allahu fi sọ ọrọ Rẹ kalẹ fun ojiṣẹ Rẹ pe:" Ọwọ́ Abu-Lahab méjèèjì ti ṣòfò. Òun náà sì ṣòfò. Àwọn dúkìá rẹ̀ àti ohun tí ó ṣe níṣẹ́ (ìyẹn, àwọn ọmọ rẹ̀) kò sì níí rọ̀ ọ́ lọ́rọ̀ (níbi ìyà). Ó sì máa wọ inú Iná eléjò fòfò. Àti ìyàwó rẹ̀, aláàárù-igi-ìṣẹ́pẹ́ ẹlẹ́gùn-ún, (ó máa wọná). Igbà-ọ̀pẹ pọ̀npọ̀nràn máa wà ní ọrùn rẹ̀ (nínú Iná). "(Al-Masad:1-5)"
“Lẹ́yìn náà ni ojiṣẹ- ki ikẹ ati ọla Ọlọhun maa ba a- tẹ síwájú láti máa pe wọn si Islam, o si sọ fun wọn pe: Ẹ sọ pe "Laa ilaaha illal-Looh" ki ẹ le baa jere, ni wọn ba sọ pe: Ṣe o fẹ sọ awọn ọlọhun di ọlọhun kan ṣoṣo ni, dajudaju eléyìí jẹ nkan ìyàlẹ́nu."
“Awọn aaya sọkalẹ lati ọdọ Allahu ti o n pe wọn si imọna ti o si n kilọ fun wọn nipa iṣina ti wọn wa ninu rẹ, ọkan ninu wọn ni ọrọ Allahu ti ọla Rẹ ga ti O sọ pe:" Sọ pé: "Ṣé dájúdájú ẹ̀yin máa ṣàì gbàgbọ́ nínú Ẹni tí Ó ṣẹ̀dá ilẹ̀ fún ọjọ́ méjì, ẹ sì ń sọ (ẹ̀dá Rẹ̀) di akẹgbẹ́ fún Un?" Ìyẹn sì ni Olúwa gbogbo ẹ̀dá. Ó sì fi àwọn àpáta sínú ilẹ̀ láti òkè rẹ̀. Ó fi ìbùkún sínú rẹ̀. Ó sì pèbùbù àwọn arísìkí (àti ohun àmúsọrọ̀) sínú rẹ̀ láàárin ọjọ́ mẹ́rin. (Àwọn ọjọ́ náà) dọ́gba (síra wọn) fún àwọn olùbèèrè (nípa rẹ̀). Lẹ́yìn náà, Allāhu wà ní òkè sánmọ̀, nígbà tí sánmọ̀ wà ní èéfín. Ó sì sọ fún òhun àti ilẹ̀ pé: "Ẹ wá bí ẹ fẹ́ tàbí ẹ kọ̀." Àwọn méjèèjì sọ pé: "A wá pẹ̀lú ìfínnú-fíndọ̀." Ó sì parí (ìṣẹ̀dá) rẹ̀ sí sánmọ̀ méje fún ọjọ́ méjì. Ó sì fi iṣẹ́ sánmọ̀ kọ̀ọ̀kan ránṣẹ́ sínú rẹ̀. A sì fi àwọn àtùpà (ìràwọ̀) ṣe sánmọ̀ ilé ayé ní ọ̀ṣọ́ àti ààbò (fún un). Ìyẹn ni ètò Alágbára, Onímọ̀. Tí wọ́n bá gbúnrí, sọ pé: "Èmi ń ṣèkìlọ̀ ìparun irú ìparun ìjọ ‘Ād àti Thamūd fun yín ni." "(Fussilat:9-13)"
“Ṣugbọn awọn aaya wọnyi ati ipe yẹn le wọn kun ni igberaga lati gba òdodo, wọn bẹrẹ si nii lekoko nipa fifi iya jẹ gbogbo eniyan ti o wọ inu ẹsin Islam, pàápàá jù lọ awọn ọlẹ ti ko ni ẹnikan lati daabo bo wọn, wọn maa gbe apata nla sókè àyà ọkan ninu wọn, wọn maa wa máa wọ́ ọ kiri nínú ọjà ninu ooru gbígbóná, wọn maa wa sọ fun un pe: Nínú ki o ṣe aigbagbọ si ẹsin Muhammad, tabi ki o faramọ ìyà yìí, titi tí awọn ti wọn kú fi kú nínú wọn latara ijiya tí ó le."
"Ṣùgbọ́n ojiṣẹ Allahu- ki ikẹ ati ọla Ọlọhun maa ba a- wa ni abẹ́ aabo ẹ̀gbọ́n baba rẹ Abu Talib ti o fẹran rẹ ti o si maa n káàánú rẹ̀, o jẹ ọkan ninu awọn àgbààgbà ìdílé Quraysh ti wọn máa n bẹ̀rù, ṣugbọn kò gba Islam. ”
Awọn ijọ Qurayshii gbiyanju lati ba ojiṣẹ Ọlọhun (Ki ikẹ ati ọla Ọlọhun maa ba a) dunadura lori ipepe rẹ. Wọn fi owo, ọla ati awọn nnkan ifanimọra lọ̀ ọ́, pẹ̀lú majẹmu pe ki o kora ro nibi pipepe lọ si inu ẹsin tuntun yii, eleyii ti o n fi aburu kan awọn ọlọrun wọn ti wọn n babara rẹ, ti wọn si n jọsin fun wọn yatọ si Ọlọhun. Iduro ojiṣẹ Ọlọhun (Ki ikẹ ati ọla Ọlọhun maa ba a) si jẹ ohun ti o mulẹ daadaa, nítorí pe eleyii ni aṣẹ kan ti Ọlọhun pa a laṣẹ rẹ wi pe ki o mu un de etígbọ̀ọ́ awọn eeyan, ti o ba fi le lọ fi aṣẹ yii silẹ ni, Ọlọhun O ba jẹ ẹ niya. O wa sọ fun wọn pe: Oore ni mo fẹ fun yin, ijọ mi ni ẹ si jẹ ati mọlẹbi mi. Mo fi Ọlọhun bura, ka ni pe irọ ni mo ba n pa fun gbogbo awọn eeyan ni, mi o le pa irọ fun yin, ka ni pe mo ba n tan awọn eeyan jẹ ni, mi ò le tan yin jẹ.
Nígbà tí diduna-dura náà ko ṣe anfaani láti dá ipepe náà dúró, ni ṣiṣe ọta awọn Qurayshii wa lekun si ojiṣẹ Ọlọhun (Ki ikẹ ati ọla Ọlọhun maa ba a) ati awọn olutẹlẹ rẹ, awọn Qurayshii wa fẹ lati ọdọ Abu Tọọlib pe ki o yọnda Muhammad fun awọn lati le baa pa a, ki wọn o si fun un ni ohun ti o ba fẹ, abi ki o kora ro nibi kikede ẹsin rẹ laarin wọn, ni egbọn baba rẹ wa tọrọ lati ọdọ rẹ pe ki o kora ro kuro nibi pipepe lọ si idi ẹsin yii.
Ojiṣẹ Ọlọhun (Ki ikẹ ati ọla Ọlọhun maa ba a) wa sun ẹkun, o si sọ pe: Irẹ ẹgbọn baba mi, mo fi Ọlọhun bura, bi wọn ba gbe oorun si ọtun mi ati oṣupa si osi mi lori ki n le baa fi ẹsin yii silẹ, mi ò le gbe e ju silẹ titi ti Ọlọhun o fi ṣe àfihàn rẹ, bibẹẹkọ màá yáà parun ni.
Ẹgbọn baba rẹ si sọ pe: maa ba iṣẹ lọ, ki o si maa sọ ohun ti o ba wu ọ. Mo fi Ọlọhun bura, wọn o le mu aburu kankan de ọdọ rẹ, wọn o yáà pa mí dí i ni. Nigba ti iku wa ba Abû Tọọlib ni alejo, ti awọn agbaagba Qurayshii si n bẹ lọdọ rẹ, Ojiṣẹ Ọlọhun (Ki ikẹ ati ọla Ọlọhun maa ba a) wa de si ọdọ rẹ, ti o si n wonkoko

mọ ọn pe ki o wọnu Isilaamu, o wa n sọ fun un pe: Irẹ ẹgbọn baba mi, sọ gbolohun kan ti maa fi ṣìpẹ̀ fun ẹ ni ọdọ Ọlọhun. Sọ gbolohun (Laa iLaaha illa Llaah), awọn agbaagba yii wa sọ fun un pe: Njẹ o fẹ korira ẹsin Abdul-Mutollib ni? Njẹ o fẹ korira ẹsin awọn baba ati awọn baba baba rẹ ni?. O wúwo lára rẹ láti fi ẹsin awọn baba baba rẹ silẹ ki o wa wọ inú ẹsin Isilaamu. O si ku sidi jijẹ ẹlẹbọ. Anabi (Ki ikẹ ati ọla Ọlọhun maa ba a) si banujẹ gidi gan-an lori iku ẹgbọn baba rẹ lori bi o ti ṣe ku sori ẹbọ. Ọlọhun wa fun un ni iro pẹlu ọrọ Rẹ pe: Dájúdájú ìwọ kò lè fi ọ̀nà mọ ẹni tí o fẹ́ràn, ṣùgbọ́n Allāhu l'Ó ń fi ọ̀nà mọ ẹni tí Ó bá fẹ́. Àti pé Ó nímọ̀ jùlọ nípa àwọn olùmọ̀nà. [Al-Qasas:56]

Suta si kan Anabi (Ki ikẹ ati ọla Ọlọhun maa ba a) lẹyin iku ẹgbọn baba rẹ, wọn si maa n mu awọn idọti (latara awọn ẹranko), wọn o waa gbe wọn si ẹyin rẹ nigba ti o ba n kirun lọwọ ni Kaaba

Lẹyin igba naa ni ojiṣẹ (Ki ikẹ ati ọla Ọlọhun maa ba a) wa jade lọ si ìlú Taaif lati pe awọn ara ibẹ sinu ẹsin Isilaamu. Ilu kan ni ti o jina si Makkah ni ohun ti o ṣe deedee aadọrin kilomita. Awọn ara ilẹ Taaif wa dojukọ ipepe rẹ pẹlu ohun ti o le ju nnkan ti awọn ara ilẹ Makkah ṣe lọ, wọn wa dẹ awọn omugọ inu wọn si i láti lẹ oko mọ Anabi (Ki ikẹ ati ọla Ọlọhun maa ba a) ati lati le e jina si ilẹ Taaif, wọn wa sin in lẹniti wọn n ju oko mọ ọn titi ti gigisẹ rẹ mejeeji abiyi si fi  yọ ẹjẹ.

Ojiṣẹ (Ki ikẹ ati ọla Ọlọhun maa ba a) wa dojukọ Ọlọhun rẹ lẹniti n pe e, bakan naa ti o si n wa iranlọwọ lọ si ọdọ Rẹ. Ọlọhun wa ran malaika kan si i, o si sọ fun un pe: Ọlọhun Ọba rẹ gbọ ọrọ awọn ijọ rẹ ti wọn n sọ si ọ, ti o  ba fẹ, mo le re oke meji nla lu wọn, o wa sọ pe: Rara oo, ṣugbọn mo fẹ lati ọdọ Ọlọhun pe ki O mu jade láti ìbàdí wọn awọn ti yoo maa jọsin fun Un ni Oun nikan ṣoṣo ti wọn o si nii da nnkan miran pọ mọ Ọn ni ẹbọ ṣiṣe.

Lẹyin igba naa ni Ojiṣẹ (Ki ikẹ ati ọla Ọlọhun maa ba a) wa ṣẹri pada si Makkah, iṣe ọta yii wa tẹsiwaju ati adojukọ aburu lati ọdọ awọn ijọ rẹ si gbogbo awọn ti wọn gba a gbọ. Lẹyin igba naa ni awọn ikọ kan wa wa lati ilu (Yathrib) eleyii ti o pada di orukọ kan ti wọn n pe ni (Madeenah) ti wọn si de si ọdọ ojiṣẹ (Ki ikẹ ati ọla Ọlọhun maa ba a), o wa pe wọn si oju ọna ẹsin Isilaamu, wọn si gba Isilaamu. Lẹyin igba naa ni o wa ran ọkan ninu awọn Saabe rẹ ti wọn n pe ni Mus'hab ọmọ Umayr lati kọ wọn ni awọn ẹkọ ẹsin Isilaamu. Ọpọlọpọ ninu awọn ara ilu Madeena ni o si ti ara rẹ gba Isilaamu.

Wọn wa ba Anabi (Ki ikẹ ati ọla Ọlọhun maa ba a) ni ọdun ti o tẹle e lati ṣe àdéhùn fun un nipa Isilaamu, lẹyin igba naa ni o wa pa awọn sahabe rẹ ti wọn fun ilẹ mọ pe ki wọn ṣe hijira lọ si ilu madeena, wọn si ṣe hijira ni janmọọn ati ni ẹyẹẹyọ, wọn si fun wọn ni alajẹ ti wọn n pe ni (Muhaajiruun). Awọn ara ilu Madeena si pade wọn pẹlu apọnle ati kiki-kaabọ ati pẹlu itẹwọgba, wọn si gba wọn ni alejo sinu ile wọn, wọn si pin awọn dukia wọn ati awọn ile wọn laarin ara wọn, wọn wa sọ wọn ni orukọ ti a n pe ni (Ansaar).

Lẹyin igba ti awọn Qurayshii mọ nipa hijira yii, wọn pinnu lati pa Anabi (Ki ikẹ ati ọla Ọlọhun maa ba a), wọn si tun pinnu láti ṣí i mọ́lé tí ó ń sùn sí, ti o ba ti wa jade wọn o fi ida bẹ ori rẹ ni ẹẹkan náà. Ọlọhun si la a lọwọ wọn, o si kuro laarin wọn ti wọn o si fura. Abubakr' Siddeeq wa lọ ba a lójú ọ̀nà, o si pa Aliyy laṣẹ pe ki o duro si Makkah lati le ba maa da awọn nnkan ti wọn fi pamọ si Anọbi lọ́wọ́ pada fún awọn ti wọn ni wọn.

Ni oju ọna hijira, awọn Qurayshii gbe ẹbun nla kalẹ fun ẹniti o ba ri Muhammad (Ki ikẹ ati ọla Ọlọhun maa ba a) mu laaye abi ni òkú, ṣugbọn Ọlọhun Ọba la a kuro lọwọ wọn, o wa de ilẹ Madeena pẹlu saabe rẹ ni ẹniti nnkan kan o ṣe.

Awọn ara ilu Madeena si pade rẹ pẹlu iro ìdùnnú ati ikini-kaabọ ati ìdùnnú ti o pọ. Wọn si jade ni apapọ lati awọn ile wọn lati lọ pade ojiṣẹ Ọlọhun (Ki ikẹ ati ọla Ọlọhun maa ba a). Wọn wa n sọ pe: Ojiṣẹ Ọlọhun ti de, Ojiṣẹ Ọlọhun ti de.

Ojiṣẹ (Ki ikẹ ati ọla Ọlọhun maa ba a) di ẹni tí ó n gbé ìlú Madina. O wa kọkọ bẹrẹ pẹlu kikọ mọṣalaṣi si ilu Madeena lati le maa gbe iru duro nibẹ, o wa bẹrẹ lati maa kọ awọn eeyan ni awọn ẹkọ ofin ẹsin, o si tun n ka alukurani fun wọn, o si n re wọn pẹlu awọn iwa alapọn-ọnle. Awọn saabe rẹ wa rọkiri ka rẹ ti wọn si n kọ imọna lati ọdọ rẹ, wọn si tun fi n fọ ẹmi ara wọn mọ, ti awọn iwa wọn si n ga pẹlu rẹ, ti ifẹ wọn ti wọn ni si ojiṣẹ (Ki ikẹ ati ọla Ọlọhun maa ba a) si tun jindò síi, wọn si lapa pẹlu awọn iroyin rẹ ti o ga julọ, asopọ ijẹ ọmọ-iya onigbagbọ si ni agbara laarin wọn. Madeena wa pada di arikọṣe rere eleyii ti o n ṣẹmi ninu ìdùnnú ati ijẹ ọmọ-iya, ti ko si si iyatọ kankan laarin awọn ti wọn n gbe ibẹ láàrin olowo àti tálákà, eeyan funfun ni o abi eeyan dudu, larubawa ni o abi elede miiran. Ko si si gbigbe ọla fun apa kan ju apa kan lọ ayafi nibi igbagbọ ati ipaya. Latara àwọn ẹni ẹ̀sà yii ni ìran ti o lọla ju nínú ìtàn ti kọ́jọ.

Lẹyin ọdun kan ti ojiṣẹ (Ki ikẹ ati ọla Ọlọhun maa ba a) ṣe hijira, awọn ogun wa bẹ̀rẹ̀ laarin ojiṣẹ pẹ̀lú àwọn saabe rẹ ati idile Qurayshii pẹ̀lú awọn ti wọn wa pẹ̀lú wọn nibi gbigbe ọta dide si ẹsin Isilaamu.

Ogun akọkọ wa ṣẹlẹ laarin wọn ti o si jẹ ogun ti a n pe ni Badru-l-kub'rah ni àfonífojì kan ti nbẹ laarin Makkah ati Madeenah. Ọlọhun wa kun awọn Mùsùlùmí lọwọ, ti onka wọn si jẹ 314, ti onka awọn Qurayshii si jẹ ẹgbẹrun kan (1000) ọmọ ogun. Wọn bori wọn, wọn si pa àádọ́rin (70) ninu awọn Qurayshii, ti o si jẹ pe awọn ti o pọ ju ninu wọn ni awọn agbaagba wọn ati aṣiwaju wọn, wọn ko awọn aadọrin ninu wọn lẹru, awọn ti o ṣẹku si salọ.

Lẹyin igba naa ni awọn ogun miiran ṣẹlẹ̀ laarin ojiṣẹ (Ki ikẹ ati ọla Ọlọhun maa ba a) ati awọn Qurayshii, ojiṣẹ (Ki ikẹ ati ọla Ọlọhun maa ba a) si ni ikapa nibi ikẹyin rẹ (lẹyin ọdun mẹjọ ti o ti jáde kuro ni Mẹka) lati ran àwọn ọmọ ogun ti onka wọn jẹ ẹgbẹ̀rún ninu awọn ti wọn gba Isilaamu lọ si ilu Makkah lati lọ ba awọn Qurayshii ja ogun ninu ile wọn, ki wọn si wọ ibẹ ni tipá, ki wọn si bori wọn. Bayii ni o ṣe bori ìdílé rẹ ti wọn gbèrò láti pa a, ti wọn si fi iya jẹ àwọn saabe rẹ, ti wọn si ṣẹri àwọn èèyàn kúrò níbi ẹsin ti o mu wa láti ọ̀dọ̀ Ọlọhun.
O wa ko wọn jọ lẹyin bibori ti o gbajumọ naa. O wa sọ fun wọn pe: Ẹyin Qurayshii, kini ẹ lero pe maa ṣe fun yin? Wọn sọ pe: Ọmọ iya alapọn-ọnle, ọmọ ọmọ-iya alapọn-ọnle. O sọ pe: Ẹ maa lọ, ẹ si ti wa ni ẹni itusilẹ, o wa ṣe amojukuro fun wọn, o si fi ominira silẹ fun wọn lati ṣe ẹsin Isilaamu.
Eleyii wa jẹ okunfa ti awọn eeyan fi wọ inu Isilaamu nijọnijọ. Gbogbo erékùsù ilẹ larubawa ni o si gba Isilaamu, wọn si wọ inu ẹsin Isilaamu.
Ko pẹ si ìgbà yẹn ti Ojiṣẹ (Ki ikẹ ati ọla Ọlọhun maa ba a) fi ṣe hajj, awọn 114,000 si ṣe hajj pẹlu rẹ ninu awọn ti wọn ṣẹ̀ṣẹ̀ wọnu ẹsin Isilaamu.
O wa duro ni ẹniti o n ṣe khutuba fun wọn ni ọjọ hajj nla. O si n se alaye awọn idajọ ẹsin fun wọn ati awọn ofin Isilaamu. Lẹyin igba naa ni o wa sọ fun wọn pe: O ṣee ṣe ki a ma pade ara wa lẹyin ọdun yii, ẹ tẹti ki ẹ gbọ o, ki ẹniti o wa nibi sọ fun ẹniti ko si nibi. Lẹyin igba naa ni o wa wo wọn, o si sọ pe: Ẹ tẹti ki ẹ gbọ o, njẹ mo jẹ iṣẹ́ ti wọn ran mi? Awọn eeyan wa sọ pe: Bẹẹni, o wa sọ pe: Ìwọ Ọlọhun, jẹrii si i, ẹ tẹti ki ẹ gbọ o, njẹ mo jẹ iṣẹ́ ti wọn ran mi? Awọn eeyan wa sọ pe: Bẹẹni, o wa sọ pe: Ìwọ Ọlọhun, jẹrii si i.
Ẹyin igba naa ni Ojiṣẹ (ki ikẹ ati ọla Ọlọhun maa ba a) wa ṣẹri pada lẹyin igba ti o ṣe hajj lọ si ilu Mẹdina, o si ṣe khutuba fun awọn eeyan ni ọjọ kan, o wa sọ fun wọn pe: Dajudaju ẹru kan, Ọlọhun fun un ni iyọnda lati ṣẹsa láàrin ṣíṣe gbere ni ilé-ayé ati nǹkan ti n bẹ ni ọdọ Ọlọhun, o wa ṣẹsa nǹkan ti n bẹ ni ọdọ Ọlọhun. Awọn saabe wa sunkun, wọn si mọ pe ara rẹ ni o n ba wi, bakan naa kikuro rẹ ninu ile aye yii ti sunmọ. Nigba ti o wa di ọjọ Monday, ọjọ́ kejila ninu oṣu kẹta ninu oṣu hijirah ni ọdun kọkanla ti o ṣe hijira, aisan wa lekoko fun Ojiṣẹ (Ki ikẹ ati ọla Ọlọhun maa ba a), ihunrira iku wa bẹrẹ pẹlu rẹ, o wa wo awọn saaabe rẹ ni wiwo idagbere. O wa sọ asọtẹlẹ fun wọn lori mimaa mojuto irun, ẹmi si jade kúrò lára rẹ.
Ikú ojiṣẹ- kí ikẹ ati ọla Ọlọhun máa bá a- ba awọn saabe (Ki Ọlọhun ba wa yọnu si gbogbo wọn) lójijì, ibanujẹ wọn si de ogongo, adanwo naa si lapa lara wọn, titi ti ọkan ninu wọn tii ṣe Umar ọmọ Khattāb (Ki Ọlọhun ba wa yọnu si i) fi dide lẹniti o fa idà rẹ̀ yọ latara ibẹru adanwo ojiji yii, o wa n sọ pe: Ti mo ba gbọ ti ẹni kan ba n sọ pé ojiṣẹ Ọlọhun- ki ikẹ ati ọla Ọlọhun máa bá a- kú, màá bẹ́ orí rẹ̀.
Abubakr' Siddeeq wa dide, o si n ran an leti ọrọ Ọlọhun ti o sọ pe: Kí ni (Ànábì) Muhammad bí kò ṣe Òjíṣẹ́, tí àwọn Òjíṣẹ́ kan ti lọ ṣíwájú rẹ̀. Ṣé tí ó bá kú tàbí tí wọ́n bá pa á, ẹ máa pẹ̀yìn dà (sẹ́sìn)? Ẹnikẹ́ni tí ó bá pẹ̀yìn dà (sẹ́sìn) kò lè kó ìnira kan kan bá Allāhu. Allāhu yó sì san àwọn olùdúpẹ́ ní ẹ̀san rere. Suuratu Aal-Imraan: 144 Ni kete ti Umar gbọ aaya yii, o wo lulẹ lẹniti o daku.
Ẹni yii ni Muhammad, Ojiṣẹ Ọlọhun (Ki ikẹ ati ọla Ọlọhun maa ba a) ti o si tun jẹ igbẹyin awọn Anabi ati awọn ojiṣẹ. Ọlọhun gbe e dide si gbogbo awọn eeyan pátápátá ni olufunni ni iro ìdùnnú ati olukilọ. O jẹ iṣẹ naa, o si pe awọn nnkan afọkantan naa, o si ṣe iṣiti fun awọn ijọ naa.
Ọlọhun kun un lọwọ pẹlu Alukurani Alapọn-ọnle, tii ṣe ọrọ Ọlọhun ti wọn sọkalẹ lati sanmọ, eleyii ti o ṣe wi pe: Ìbàjẹ́ kò níí kàn án láti iwájú rẹ̀ àti láti ẹ̀yìn rẹ̀. Ìmísí tí wọ́n sọ̀kalẹ̀ ni láti ọ̀dọ̀ Ọlọ́gbọ́n, Ẹlẹ́yìn. [Fussilat:42] Eleyii ti o ṣe wipe ti awọn abara lati igba ti aye ti bẹrẹ titi ti aye o fi pari ba kojọ lori wipe awọn fẹ mu irú rẹ wa, wọn o le mu irú rẹ wa, apá kan wọn ìbáà jẹ́ olùrànlọ́wọ́ fún apá kan."
Ọlọhun Ọba ti ọla Rẹ ga sọ pe: Ẹ̀yin ènìyàn, ẹ jọ́sìn fún Olúwa yín, Ẹni tí Ó da ẹ̀yin àti àwọn t'ó ṣíwájú yín, nítorí kí ẹ lè ṣọ́ra (fún ìyà Iná). (Ẹ jọ́sìn fún) Ẹni tí Ó ṣe ilẹ̀ fun yín ní ìtẹ́, (Ó ṣe) sánmọ̀ ní àjà, Ó sọ omi òjò kalẹ̀ láti sánmọ̀, Ó sì fi mú àwọn èso jáde ní ìjẹ-ìmu fun yín. Nítorí náà, ẹ má ṣe bá Allāhu wá akẹgbẹ́, ẹ sì mọ̀ (pé kò ní akẹgbẹ́). Tí ẹ bá wà nínú iyèméjì nípa ohun tí A sọ̀kalẹ̀ fún ẹrúsìn Wa, nítorí náà, ẹ mú sūrah kan wá bí irú rẹ̀, kí ẹ sì pe àwọn ẹlẹ́rìí yín, yàtọ̀ sí Allāhu, tí ẹ bá jẹ́ olódodo. Tí ẹ ò bá sì ṣe bẹ́ẹ̀, ẹ ò wulẹ̀ lè ṣe bẹ́ẹ̀, nítorí náà ẹ ṣọ́ra fún Iná, èyí tí ìkoná rẹ̀ jẹ́ àwọn ènìyàn àti òkúta tí Wọ́n pa lésè sílẹ̀ de àwọn aláìgbàgbọ́. Fún àwọn t'ó gbàgbọ́ ní òdodo, tí wọ́n sì ṣe àwọn iṣẹ́ rere ní ìró ìdùnnú pé, dájúdájú àwọn Ọgbà Ìdẹ̀ra kan ń bẹ fún wọn, èyí tí àwọn odò ń ṣàn ní ìsàlẹ̀ rẹ̀. Nígbàkígbà tí A bá p'èsè jíjẹ-mímu kan fún wọn nínú èso rẹ̀, wọn yóò sọ pé: "Èyí ni wọ́n ti pèsè fún wa tẹ́lẹ̀tẹ́lẹ̀." – Wọ́n mú un wá fún wọn ní ìrísí kan náà ni (àmọ́ pẹ̀lú adùn ọ̀tọ̀ọ̀tọ̀). – Àwọn ìyàwó mímọ́ sì ń bẹ fún wọn nínú Ọgbà Ìdẹ̀ra. Olùṣegbére sì ni wọ́n nínú rẹ̀. Suratul Bakarat: 21-25
Alukurani yii, wọn ko o jọ latara ọgọ́rùn-ún suura lé ní mẹrinla ti àwọn aaya inú rẹ̀ si le ni ẹgbẹ̀rún mẹ́fà. Ọlọhun si maa n pe awọn eeyan nija láti ìgbà dégbà pe ki wọn mu suura kan bíi irú awọn suura Alukurani wa, suura ti o si kere julọ ninu Alukurani alapọn-ọnle jẹ ohun ti wọn kó jọ latara aaya mẹta pere.
Ti wọn ba ni ikapa rẹ ni, ki wọn yaa lọ mọ pe Alukurani yii kii ṣe ọdọ Ọlọhun ni o ti wa, eleyii si jẹ ọkan ninu awọn iṣẹ ìyanu ti o tobi julọ ti Ọlọhun fi kun ojiṣẹ (Ki ikẹ ati ọla Ọlọhun maa ba a) Rẹ lọwọ, gẹgẹ bi

Ọlọhun ti ṣe kun un lọwọ pẹlu awọn iṣẹ ìyanu Rẹ miiran ti o jẹ awọn nnkan ti o yapa si nǹkan ti a ti bá saaba. Ninu rẹ naa ni:

## Kikun Anabi (ki ikẹ ati ọla Ọlọhun maa ba a) lọ́wọ́ pẹlu àwọn iṣẹ́ iyanu

Oun naa ni pe: O maa n pe Ọlọhun ti yoo si ki ọwọ rẹ bọ igba, omi si maa sẹ jade laarin awọn ọmọnika rẹ, awọn ọmọ ogun o si mu ninu omi yii, ti onka wọn si jẹ nnkan ti o le ni ẹgbẹrun.
2- O maa n pe Ọlọhun, yoo wa ti ọwọ rẹ bọ inu ounjẹ, ti ounjẹ o si tara rẹ pọ ninu abọ titi ti ẹgbẹrun kan le ni ẹẹdẹgbẹta ninu awọn saabe o si jẹun ninu rẹ.
3- O maa n tẹ ọwọ rẹ mejeeji si sanmọ ti yoo si maa kepe Ọlọhun láti rọ ojo, ko nii tii kuro ni aye ibi ti o wa titi ti omi o fi maa san bọ silẹ loju rẹ abiyi latara oripa ojo naa. Awọn iṣẹ ìyanu miiran si wa ti o pọ.
Ọlọhun kun un lọwọ pẹlu didaabo bo o, ẹnikẹni o si le de ọdọ rẹ ninu awọn ti o gbero lati pa a ati lati pa imọlẹ ti o mu wa lati ọdọ Ọlọhun, gẹgẹ bi o ṣe wa ninu ọrọ Rẹ ti ọla Rẹ ga pe: Ìwọ Òjíṣẹ́, fi gbogbo ohun tí wọ́n sọ̀kalẹ̀ fún ọ láti ọ̀dọ̀ Olúwa rẹ jíṣẹ́. Tí o ò bá sì ṣe bẹ́ẹ̀, o ò jíṣẹ́ pé. Allāhu yó sì dáàbò bò ọ́ lọ́dọ̀ àwọn èniyàn. Al-Maaidah 67
Ojiṣẹ Ọlọhun (Ki ikẹ ati ọla Ọlọhun maa ba a) si jẹ arikọṣe rere, pẹlu ikunlọwọ Ọlọhun fun un, nibi gbogbo awọn iṣẹ rẹ ati awọn ọrọ rẹ. O si jẹ ẹni akọkọ ti o maa n ṣe amulo awọn aṣẹ ti o n sọkalẹ fun un lati ọdọ Ọlọhun. O si jẹ ẹniti o lojukokoro julọ ninu awọn eeyan nibi ṣiṣe awọn ijọsin ati awọn itẹle, oun naa ni ẹni tí o n ta ọrẹ julọ ninu awọn eeyan, owo kankan kii ṣẹku si i lọwọ ayafi ki o na an si oju ọna Ọlọhun fun awọn alaini ati awọn olọṣi ati awọn ti ni bukaata si i titi ko fi yọ ogún naa silẹ. O sọ fun awọn saabe rẹ pe: Dájúdájú awa ti a jẹ Anabi, wọn kii jogun wa, gbogbo ohun a ba fi silẹ o maa jẹ saara. [1]
Ṣugbọn awọn iwa rẹ, ẹnikan kan o le le e ba. Ẹnikan kan o si nii ba a ṣe ọrẹ ayafi ki o jẹ ẹniti yoo nifẹẹ si i lati isalẹ ọkan rẹ. Ojiṣẹ (Ki ikẹ ati ọla Ọlọhun maa ba a) wa maa ti ara rẹ di ẹniti yoo nifẹẹ si ju ọmọ rẹ lọ ati obi rẹ ati gbogbo eeyan lapapọ.
Anas ọmọ Maalik ti o jẹ ọmọ-ọdọ Ojiṣẹ Ọlọhun (Ki ikẹ ati ọla Ọlọhun maa ba a) maa n sọ pe: Mi o tii fi ọwọ kan atẹlẹwọ kankan ti o dara to tabi ti o fẹlẹ to tabi ti oorun rẹ dun to atẹlẹwọ Ojiṣẹ Ọlọhun (Ki ikẹ ati ọla Ọlọhun maa ba a). Mo ti ṣe ọmọ-ọdọ rẹ fun odidi ọdun mẹwa, ko si sọ fun mi ni nnkan ti mo ba ṣe pe kilode ti o fi ṣe e, tabi nnkan ti mio ṣe pe kilode ti o o fi ṣe e. [2]
Muhammad yẹn ni ojiṣẹ Ọlọhun, ẹniti o ṣe pe Ọlọhun gbe iyi rẹ ga soke, O si gbe iranti rẹ naa ga bakan naa laarin awọn ẹda. Ko si ẹni kankan ti wọn le maa darukọ rẹ ni ayé ni oni tàbí ṣíwájú òní gẹ́gẹ́ bi wọn ṣe maa n dárúkọ rẹ. Lati ẹgbẹrun ọdún kan le ni ọgọ́rùn-ún mẹrin ni awọn aaye ti wọn ti n perun kààkiri orilẹ ti maa n pariwo ni ẹẹmarun ni ojoojumọ pe: Mo jẹrii pe dajudaju Muhammad Ojiṣẹ Ọlọhun ni. Aimọye àwọn olukirun ni wọ́n maa n paara ni ẹẹmẹwa lojoojumọ nibi gbogbo irun wọn pe: Mo n jẹrii pe Muhammad Ojiṣẹ Ọlọhun ni.

## Awọn saabe alapọn-ọnle:

Awọn saabe alapọn-ọnle mojuto ipepe si oju ọna ẹsin Isilaamu lẹyin iku Ojiṣẹ (Ki ikẹ ati ọla Ọlọhun maa ba a), wọn si mu un lọ si awọn aaye ibuyọ oorun lórílẹ̀ ati awọn aaye ibuwọ oorun. Wọn si jẹ ẹniti o loore julọ ninu awọn olupepe si oju ọna ẹsin yii, wọn si tun jẹ olododo julọ ati onideede julọ ati olupe nnkan afọkantan julọ ninu awọn eeyan, wọn si tun jẹ oluṣe ojúkòkòrò julọ lati fi awọn eeyan mọ ọna ati fifọn oore ka laarin ara wọn.
Wọn ni ìwà àwọn Anọbi lara, wọn si kọṣe àwọn iroyin wọn. Oripa ti o foju han si nbẹ nibi awọn iwa rẹ yii ti o si fi mu ki awọn èèyàn lorilẹ ṣe tẹwọ gba ẹsin yii. Wọn si wọnu ẹsin Isilaamu ni sisẹntẹle ati nijọnijọ ni ibuwọ oorun Afrika ati ibuyọ oorun Asia, ati titi de aarin Yúróòpù ni ẹni tí ó nífẹ̀ẹ́ si ẹsin yii laifi tulaasi abi tipatipa mu wọn.
Awọn ni saabe Ojiṣẹ Ọlọhun, ti wọn jẹ ẹniti o lọla julọ ninu awọn eeyan lẹyin awọn Anabi. Awọn ti o gbajumọ ju ninu wọn ni awọn (Khulafaahu Rọọshiduun) awọn Khaleefah ti wọn mọ̀nà, ti wọn jẹ mẹrin, ti wọn si ṣe ijọba ẹsin Isilaamu lẹyin iku Ojiṣẹ (Ki ikẹ ati ọla Ọlọhun maa ba a). Awọn naa ni:
1- Abubakr' As-Siddeeq
2- Umar ọmọ Khattaab
3- Uthmaan ọmọ Affaan
4- Aliyy ọmọ Abuu Tọọlib

---

[1] Hadiisi yii, Imam Ahmad lo gbe e jade (2/463), Isnaad rẹ si ni alaafia gẹgẹ bi Ahmad Shaakir ṣe sọ nibi iṣẹ́ ìwádìí láti fi ìní àlàáfíà Mus'nad múlẹ̀ (19/92). (Àwọn ajogún mi ko gbọdọ gba nǹkan kan kódà ko jẹ Dínárì kan, ohunkohun ti mo ba si fi silẹ, yàtọ̀ sí inawo àwọn iyawo mi ati awọn ọ̀ṣìṣẹ́ mi, saara ni yoo jẹ)
[2] Bukhari ni o gbe e jade (4/230)

Awọn Mùsùlùmí si maa n mọ rírì wọn, wọn si maa n sunmọ Ọlọhun ti O ga julọ pẹlu ifẹ Ojiṣẹ Rẹ ati ifẹ awọn saabe ojiṣẹ Rẹ, ọkùnrin inú wọn ni tàbí obìnrin wọn, wọn maa n babara wọn, wọn si tun maa n gbe wọn tobi, wọn si maa n gbe wọn si ipo ti ó yẹ wọn.
Ẹni kankan ko nii korira wọn, bákannáà ko si nii tàbùkù wọn ayafi ẹniti o ba jẹ keferi pẹlu ẹsin Isilaamu, koda ki o pe ara rẹ ni musulumi. Ọlọhun yin wọn pẹlu ọrọ Rẹ pe: Ẹ jẹ ijọ t'o loore julọ, ti A gbe dide fun awọn eniyan; ẹ n paṣẹ ohun rere, ẹ n kọ ohun buruku, ẹ si gbagbọ ninu Allāhu. Aal Im'raan/110
O si fi iyọnu Rẹ rinlẹ si wọn nigba ti wọn ṣe àdéhùn fun ojiṣẹ (ki ikẹ ati ọla Ọlọhun maa ba a). Ọlọhun Ọba ti O mọ julọ sọ pe: Dájúdájú Allāhu ti yọ́nú sí àwọn onígbàgbọ́ òdodo nígbà tí wọ́n ń ṣàdéhùn fún ọ lábẹ́ igi (pé àwọn kò níí fẹsẹ̀ fẹ́ẹ̀ lójú ogun). Nítorí náà, (Allāhu) mọ ohun tí ó wà nínú ọkàn wọn. Ó sì sọ ìfọ̀kànbalẹ̀ kalẹ̀ fún wọn. Ó sì san wọ́n ní ẹ̀san ìṣẹ́gun t'ó súnmọ́ [Fath' 18]

# 4- Awọn origun Isilaamu.

Awọn origun márùn-ún ti o jẹ ipilẹ ti o si foju han ni o n bẹ fun Isilaamu. Yoo maa jẹ dandan lori Mùsùlùmí lati duni mọ ọn titi ti iroyin jijẹ Mùsùlùmí fi maa jẹ ododo lórí rẹ.

## 1- Origun akọkọ: Jijẹrii pe ko si ọlọhun kankan ti ijọsin ododo tọ si ayafi Ọlọhun Ọba Allaah, ati pe dajudaju Muhammad Ojiṣẹ Ọlọhun ni.

Oun si ni gbolohun akọkọ ti yoo maa jẹ dandan fun ẹniti o ba wọnu Isilaamu lati maa wi i. Yoo waa maa sọ pe: "Mo n jẹrii pe ko si ọlọhun kankan ti ijọsin ododo tọ si ayafi Ọlọhun Ọba Allaah, ati pe dajudaju Muhammad ẹru Ọlọhun ati Ojiṣẹ Rẹ ni", ni ẹniti yoo ni adisọkan gbogbo awọn itumọ rẹ gẹgẹ bi a ti ṣe ṣalaye rẹ ṣíwájú.
Yoo wa ni adisọkan pe dajudaju Ọlọhun ni Ọba kan ṣoṣo, ti O jẹ Aso, ko bimọ bẹẹ si ni ẹni kankan ko bi I, ko si si olubakẹgbẹ kankan fun Un. Bakan naa, Oun ni Adẹdaa, ohun ti wọn da si ni oun ti o ba yatọ si I. Oun nikan si ni Ọlọhun ti ijọsin ododo tọ si, ko si Ọlọhun kankan ayafi Oun, ko si Oluwa kankan ti o yatọ si I. Yoo si tun maa ni adisọkan pe dajudaju Muhammad jẹ ẹru Ọlọhun ati Ojiṣẹ Rẹ, ẹniti wọn so imisi kalẹ fun lati sanmọ, ti o si jẹ ẹniti o jẹ iṣẹ Ọlọhun níbi àṣẹ Rẹ ati awọn nǹkan ti O kọ. Gbigba a gbọ si maa jẹ dandan nibi gbogbo oun ti O fun ni ni iro nipa rẹ, ati titẹle e nibi gbogbo ohun ti o pa laṣẹ, ati jijina si gbogbo ohun ti o kọ.

## 2- Origun keji: Gbigbe irun duro

Àwọn ìròyìn ijẹ-ẹru ati irẹlẹ fun Ọlọhun yoo maa han nibi irun, ẹru maa duro ni ẹni tí yoo rẹ ara rẹ nilẹ ti yoo maa ka àwọn aaya Kuraani, Yoo maa gbe Ọlọhun tobi pẹ̀lú oríṣiríṣi ìrántí àti ẹyin, yoo maa rukuu fun Un, yoo si maa fi ori balẹ fun Un, yoo maa ba A sọ̀rọ̀ kẹlẹkẹlẹ, yoo maa pe E, yoo si maa tọrọ ọlá ńlá Rẹ, oun ni asopọ láàrin ẹru ati Oluwa rẹ ti O da a, ti O si mọ kọkọ rẹ ati gbangba rẹ àti ìyírapadà rẹ (fún rukuu àti ìforíkanlẹ̀) lááàrin àwọn olùforíkanlẹ̀, oun ni okunfa ìfẹ́ Ọlọhun si ẹrú Rẹ, ati sisunmọ Ọn, ati yiyọnu Rẹ si i, ẹni tí ó ba gbe e ju silẹ ni ti ìgbéraga si ijẹ-ẹru fun Ọlọhun, Yoo binu si i, Yoo si ṣẹ ibi le e, yoo si jade kúrò nínú Islam.
Awọn irun márùn-ún ni o jẹ dandan ninu rẹ lojumọ, ti o ko diduro sinu ati kike suuratul Faatiha Ní orúkọ Allāhu, Àjọkẹ́-ayé, Àṣàkẹ́-ọ̀run. Gbogbo ọpẹ́ ń jẹ́ ti Allāhu, Olúwa gbogbo ẹ̀dá, Ajọkẹ-aye, Aṣakẹ-ọrun, Olùkápá-ọjọ́-ẹ̀san. Ìwọ nìkan ni à ń jọ́sìn fún. Ọ̀dọ̀ Rẹ nìkan sì ni à ń wá oore sí. Fi ẹsẹ̀ wa rinlẹ̀ l'ójú ọ̀nà tààrà ('Islām), ọ̀nà àwọn tí O ṣe ìdẹ̀ra fún,yàtọ̀ sí (ọ̀nà) àwọn ẹni-ìbínú (ìyẹn, àwọn yẹhudi) àti (ọ̀nà) àwọn olùṣìnà (ìyẹn, àwọn nasara). Sūratul Fātiha: 1-7. Ati kika nǹkan ti o rọrùn nínú àwọn aaya Kuraani, o si tu ko rukuu ati iforikanlẹ sínú, ati pipe Ọlọhun, ati sísọ pé (Allāhu Akbar), ati ṣíṣe afọmọ Rẹ ni rukuu pẹ̀lú gbólóhùn (Subhaana Robbiyal Azeem), ati ni iforikanlẹ pẹ̀lú gbólóhùn (Subhaana Robbiyal Ah'laa).
Ṣíwájú ki èèyàn o to kirun, o gbọdọ wa ni mimọ kúrò nibi awọn ẹgbin (bii ìtọ̀ àti ìgbẹ́) ni ara rẹ ati aṣọ rẹ ati ààyè ti o ti fẹ kirun, ni ẹni tí yoo fi omi ṣe aluwala pẹ̀lú fifọ oju rẹ ati ọwọ rẹ méjèèjì, yoo waa pa orí rẹ, lẹyin naa yoo waa fọ ẹsẹ rẹ méjèèjì
Ti o ba ni janaba lara (pẹlu sisunmọ ẹlẹtọ ẹni) dandan ni fun un lati wẹ pẹ̀lú fifọ gbogbo ara rẹ.

## 3- Origun kẹta: Zakaat

Oun naa ni odiwọn kan pàtó nínú owó idokowo, Ọlọhun ṣe e ni ọranyan lori awọn olowo, wọn maa fun àwọn talika ati awọn alaini ti wọn ni ẹtọ si i ninu awọn eeyan ti n bẹ nínú àwùjọ láti gbọ bukaata wọn, odiwọn rẹ nínú owó naa ni ipin méjì àti aabọ nínú ọgọ́rùn-ún nínú owó idokowo, wọn maa pin in fun àwọn ti wọn ni ẹtọ si i.
Origun yii ni okunfa titanka ifọwọsowọpọ ni awujọ pẹ̀lú lilekun ìfẹ́ ati ríran-ara-ẹni-lọwọ laarin wọn, ati kikuro ikorira ti àwọn talika ni si awọn olówó, oun naa ni okunfa àkọ́kọ́ fun idagbasoke isuna ati gbigberu

rẹ ni ọ̀nà ti o dara, ati lati kari gbogbo ipele ti n bẹ nínú àwùjọ. Zakaat yii si jẹ dandan nibi awọn dukia pẹlu awọn oniran-an-ran rẹ ninu owo, ati awọn ẹran-osin, ati awọn eso, ati awọn koro, ati awọn nnkan ti a pese kale fun owo-ṣiṣẹ, ati ohun ti o yatọ si i, pẹlu awọn odiwon ti o ṣe ọtọọtọ ninu oju-owo fun gbogbo iran kookan

## "4- Origun kẹrin: Aawẹ Ramadan"

"Aawẹ: Oun ni kiko ara ro kuro nibi jijẹ ati mimu ati isumọ awọn iyawo, pẹlu aniyan ijọsin fun Allahu, lati igba ti alufajari ba ti yọ titi di igba ti oorun yoo fi wọ"

"Oṣu Ramadan eyi ti wọn ṣe aawẹ ni dandan nínú ẹ, oun naa ni oṣù kẹsàn-án ninu oṣù oju ọ̀run (ti òṣùpá), ati pe ninu ẹ ni Kuraani bẹrẹ si nii sọkalẹ fun ojiṣẹ Allahu (ki ikẹ Ọlọhun ati ọla Rẹ maa ba a)

Ọlọhun Ọba ti ọla Rẹ ga sọ pe: "Oṣù Rọmọdọ̄n èyí tí A sọ al-Kur’ān kalẹ̀ nínú rẹ̀ 1 (tí ó jẹ́) ìmọ̀nà, àwọn àlàyé pọ́nńbélé nípa ìmọ̀nà àti ọ̀rọ̀-ìpínyà 2 fún àwọn ènìyàn; nítorí náà, ẹnikẹ́ni tí ó bá wà nínú ìlú rẹ̀ nínú yín nínú oṣù náà, 3 kí ó gba ààwẹ̀ oṣù náà. " Al-Baqara 185

Nínú àwọn àǹfààní ńlá ti n bẹ fun aawẹ naa ni fifi sùúrù kọ́ra, ati fífún ìròyìn ipaya ati ìgbàgbọ́ nínú ọkàn ni agbára, Ìyẹn ni pe aawẹ jẹ àṣírí láàrin ẹrú àti Ọlọhun, o rọ ọmọniyan lọrun ti o ba dá wà ni ààyè kan ki o jẹ ki o si mu ti ẹni kankan ko si nii mọ si pe ko gba aawẹ, ti o ba gbe ìyẹn ju silẹ láti fi jọsin fun Ọlọhun ati lati fi tẹle àṣẹ Rẹ nìkan ti ko ni orogun, ti o si mọ pe Ọlọhun nìkan ni o n ri òun nibi ìjọsìn rẹ yii. Ìyẹn maa jẹ okunfa fun alekun ìgbàgbọ́ ati ipaya rẹ, tori naa ni ẹsan àwọn alaawẹ ṣe tobi ni ọdọ Ọlọhun, kódà wọn tun ni ojú ọ̀nà kan ti wọn maa da nìkan gba wọ inu alujanna ti orúkọ rẹ n jẹ "Baabur-Royyaan". "Aawẹ agbagbọrẹ wa fun Mùsùlùmí yatọ si ti oṣù Ramadan ni gbogbo ọjọ aye yatọ si awọn ọjọ ọdun itunu awẹ ati ileya".

## "5- Origun karùn-ún: ṣíṣe hajj lọ si ile ọwọ (ka'ba)"

"Allahu ṣe e ni dandan fun Mùsùlùmí ni ẹẹkan ṣoṣo ni ìgbésí ayé, ti o ba lekun lori ẹẹkan yẹn, iyẹn maa jẹ aṣegbọrẹ. Allahu ti ọla Rẹ ga sọ pe." Allāhu ṣe àbẹ̀wò sí Ilé náà ní dandan fún àwọn ènìyàn, t’ó lágbára ọ̀nà tí ó máa gbà débẹ̀. Aal Im’raan/97 Mùsùlùmí maa ṣe ìrìn-àjò lọ sí àwọn ààyè àmì ni Mẹka nínú oṣù hajj, oun naa ni igbẹyin àwọn oṣù ti hijira. ṣíwájú ki o to wọ Mẹka, o maa bọ àwọn aṣọ rẹ silẹ, o maa wa wọ aṣọ áràmí, oun naa ni aṣọ funfun meji.

"Lẹyin naa yoo ṣe awọn iṣẹ hajj ti o sọtọọtọ, bii irọkirika ile Allahu abiyi, ati pipọṣẹṣẹ laarin apata safa ati mariwa, ati diduro ni arafa, ati sisun musidalifa mọju, ati nǹkan ti o yatọ si i."

Hajj ni akojọpọ ti o tobi ju fun àwọn Mùsùlùmí lórí ilẹ̀, ti ibara ẹni lo bii ọmọ-iya ati níní aanu ara ẹni ati gbigba ara ẹni ni imọran maa fọnka nibẹ, ọkan naa ni aṣọ wọn ati ìjọsìn wọn, ko si ọlá fun ẹnikan ninu wọn lori ẹlòmíràn ayafi pẹ̀lú ipaya. Ẹsan hajj nǹkan ti o tobi ni, ojiṣẹ Ọlọhun (ki ikẹ ati ọla Ọlọhun máa bá a) sọ pe: “(Ẹnikẹni ti o ba ṣe Hajj ti ko si ba iyawo rẹ ni aṣepọ, ti ko si da ẹṣẹ, yoo jade kuro ninu ẹṣẹ rẹ bii ọjọ ti iya rẹ bi i) [3]

# "5- Awọn origun igbagbọ "

Ti o ba ti wa mọ pe àwọn origun Isilaamu naa ni àwọn àmì rẹ ti o han ti Mùsùlùmí maa ṣe afihan rẹ, ni eyi ti ṣiṣe e rẹ n tọka si gbigba Isilaamu rẹ. Àwọn origun kan n bẹ ninu ọkan ti o jẹ dandan fun Mùsùlùmí ki o ni ìgbàgbọ́ si i ki Isilaamu rẹ le baa ni àlàáfíà, wọn n pe e ni origun ìgbàgbọ́. Gbogbo igba ti odiwọn rẹ ba ti n lekun ninu ọkan rẹ ti o si pe naa ni yoo ṣe maa goke sii ni ìgbàgbọ́, ti yoo si ni ẹtọ si wiwọ inu awọn ẹru Ọlọhun ti wọn jẹ onigbagbọ. Ipo yii tun ga ju ipo ijẹ Mùsùlùmí lọ, gbogbo onigbagbọ pata ni Mùsùlùmí, ṣùgbọ́n gbogbo Musulumi kọ ni o ti de ipo onigbagbọ.

"Nǹkan ti o daju ni pe o ti ni ipilẹ igbagbọ, ṣugbọn o le ma ni pipe rẹ."

"Awọn origun igbagbọ mẹfa ni"

"Awọn náà ni ki o ni igbagbọ ninu Allahu ati awọn Malaika Rẹ, ati awọn tira Rẹ, ati awọn ojiṣẹ Rẹ, ati ọjọ ikẹyin, ati kadara, eyi ti o dara nibẹ ati eyi ti o buru."

"Origun akọkọ: Ki o gbagbọ ninu Ọlọhun, ki ọkàn o kun fun ìfẹ́ Ọlọhun ati gbígbé E tobi, ati yiyẹpẹrẹ ara ẹni ni iwaju Rẹ, ati titẹle àwọn àṣẹ Rẹ nikan ṣoṣo ti ko ni orogun, gẹgẹ bi ọkàn ṣe maa kun fun ibẹru Ọlọhun ati irankan nǹkan ti n bẹ ni ọdọ Rẹ, ti yoo waa di ẹni ti yoo wa ninu awọn ẹru Ọlọhun ti wọn jẹ olupaya ti wọn n rin ni ojú ọ̀nà ti o tọ.

“Origun keji: Igbagbọ ninu awọn Malaika, ati pe wọn jẹ ẹrú Ọlọhun ti wọn da latara imọlẹ, ti ko si ẹni ti o mo onka wọn ni sanmọ ati ilẹ ayafi Allahu nikan, wọn da ìjọsìn ati ìrántí Ọlọhun ati ìṣe afọmọ mọ wọn, wọn maa n ṣe afọmọ ni oru ati ọsan, kii rẹ̀ wọ́n. " Wọn kò níí yapa àṣẹ Allāhu níbi ohun tí Ó bá pa láṣẹ fún wọn. Wọ́n sì ń ṣe ohun tí wọ́n bá pa láṣẹ fún wọn." ( At-Tahrim:6) Ọkọọkan wọn ni o ni iṣẹ ti Ọlọhun rọ ọ fun, o n bẹ nínú wọn àwọn ti wọn gbe Ìtẹ́-ọlá Rẹ, o n bẹ nínú wọn àwọn ti wọn n gba ẹ̀mí, o n bẹ ninu

[3] “[4] Hadisi naa, Bukhari ni o gbe e jade (2/164), Iwe Hajj, Abala "Ọla ti n bẹ fun Hajj ti a gba wọle.”

wọn ẹni tí n sọkalẹ pẹlu imisi láti sanmọ, oun naa ni Jibril (ki ọlà maa ba a), oun naa ni o lọla ju ninu wọn, o n bẹ ninu wọn ẹ̀ṣọ́-alujanna ati awọn ẹ̀ṣọ́-iná, ati awọn ti wọn yàtọ̀ si wọn ni àwọn Malaika rere ti wọn nífẹ̀ẹ́ àwọn onigbagbọ ninu awọn abara, ti wọn si maa n tọrọ aforijin fun wọn gan, ti wọn si maa n ṣe adua fun wọn lọpọlọpọ.

"Origun kẹta: Igbagbọ ninu awọn tira ti a sọkalẹ lati ọdọ Allahu."

Musulumi maa ni igbagbọ pe Ọlọhun sọ àwọn tira kalẹ fun ẹni tí O wu u ninu awọn ojiṣẹ Rẹ, ti o (tira) ko ìró ododo sínú ati àṣẹ deedee lati ọdọ Rẹ, O si sọ Taoreeta kalẹ fún Musa, O sọ Injiila kalẹ fun Isa, O sọ Sabura kalẹ fun Daud, O sọ Suhuf kalẹ fun Ibrahim. Awọn tira yii ko si mọ ni oni gẹ́gẹ́ bi O ṣe sọ wọn kalẹ. O tun maa ni igbagbọ pe Ọlọhun sọ Kuraani kalẹ fun opin àwọn Anọbi tii ṣe Muhammad (ki ikẹ ati ọla Ọlọhun máa bá a) O si sọ àwọn aaya kalẹ ni tẹ̀lẹ́ntẹ̀lé fun ọdun méta le ni ogún, O si da aabo bo o kuro nibi ijirọ ati yiyipada Dájúdájú Àwa l'A sọ Tírà Ìrántí kalẹ̀ (ìyẹn al-Kur'ān). Dájúdájú Àwa sì ni Olùṣọ́ rẹ̀. Al-Hijr 9

Origun kẹrin: Níní ìgbàgbọ́ nínú àwọn ojisẹ.

(Ọrọ ni ẹ̀kúnrẹ́rẹ́ ti ṣíwájú nípa wọn), ninu ìtàn, gbogbo àwọn ìjọ pátá ni wọn ran àwọn Anọbi si, ẹsin wọn ẹyọkan ni, Oluwa wọn ẹyọkan ni, wọn n pe àwọn abara si imọ Ọlọhun lọkan ati jijọsin fun Un, wọ́n sì ń sọ wọn lára kúrò nibi ìṣe Kèfèrí àti ẹbọ ati iyapa " Kò sí ìjọ kan (ṣíwájú rẹ) àfi kí olùkìlọ̀ ti rè kọjá láàrin wọn." Fatir:24) "Ati pe abara ni awọn naa gẹgẹbi awọn abara yoku, Allahu kan sa wọn lẹsa lati jẹ iṣẹ Rẹ ni." Dájúdájú Àwa (fi ìmísí) ránṣẹ́ sí ọ gẹ́gẹ́ bí A ṣe fi ránṣẹ́ sí (Ànábì) Nūh àti àwọn Ànábì (mìíràn) lẹ́yìn rẹ̀. A fi ìmísí ránṣẹ́ sí (àwọn Ànábì) 'Ibrọhīm, 'Ismọ̄'īl, 'Ishāk, Ya'kūb àti àwọn àrọ́mọdọ́mọ (rẹ̀), àti (Ànábì) 'Īsā, 'Ayyūb, Yūnus, Hārūn àti Sulaemọ̄n. A sì fún (Ànábì) Dāwūd ní Zabūr. Àti àwọn Òjíṣẹ́ kan tí A ti sọ ìtàn wọn fún ọ ṣíwájú pẹ̀lú àwọn Òjíṣẹ́ kan tí A kò sọ ìtàn wọn fún ọ. Allāhu sì bá (Ànábì) Mūsā sọ̀rọ̀ tààrà. (A ṣe wọ́n ní) Òjíṣẹ́, oníròó ìdùnnú àti olùkìlọ̀ nítorí kí àwíjàre má lè wà fún àwọn ènìyàn lọ́dọ̀ Allāhu lẹ́yìn (tí) àwọn Òjíṣẹ́ (ti jíṣẹ́). Allāhu sì ń jẹ́ Alágbára, Ọlọ́gbọ́n. (An-Nisa:163-165) "Musulumi ni lati gba gbogbo wọn gbọ, yoo si fẹ́ràn gbogbo wọn, yoo si ṣe atilẹyin fun gbogbo wọn, ko si ni ṣe iyatọ laarin eyikeyi ninu wọn. Nítorí náà ẹnikẹni ti o ba ṣe aigbagbọ si ọkan ninu wọn, tabi ti o bu u, tabi ti o ṣe ipalara fun un, irú ẹni bẹ́ẹ̀ ti ṣe aigbagbọ si gbogbo wọn."

"Ẹni ti o dara ju ninu wọn ti o si ni ọla ju ninu wọn ti ipo rẹ si ju ti gbogbo wọn lọ lọdọ Allahu náà ni ipari awọn Anọbi tii ṣe Muhammad (ki ike ati ọla Ọlọhun maa ba a)."

"Origun karùn-ún: Igbagbọ ninu ọjọ ikẹyin "

"Ati pe Allahu a gbe awọn ẹru dide lati inu sàréè wọn, ti yoo si ko wọn jọ pátápátá ni ọjọ igbedide lati ṣe ìṣirò awọn iṣẹ wọn ni aye." Ní ọjọ́ tí A máa yí ilẹ̀ ayé padà sì ǹǹkan mìíràn. (A máa yí) àwọn sánmọ̀ náà (padà. Àwọn ẹ̀dá) sì máa jáde (síwájú) Allāhu, Ọ̀kan ṣoṣo, Olùborí. (Ibrahim:48)

Nígbà tí sánmọ̀ bá fà ya pẹ́rẹpẹ̀rẹ, àti nígbà tí àwọn ìràwọ̀ bá já bọ́ káàkiri, àti nígbà tí àwọn ibúdò bá ṣàn jára wọn, àti (nígbà tí A bá ta ilẹ̀ sókè), tí A sì mú àwọn òkú jáde (láàyè) láti inú àwọn sàréè, (nígbà náà ni) ẹ̀mí kọ̀ọ̀kan yóò mọ ohun tí ó tì síwájú (nínú iṣẹ́ rẹ̀) àti ohun tí ó fi sẹ́yìn (nínú orípa iṣẹ́ rẹ̀). (Al-Infitar1-5)

Ṣé ènìyàn kò rí i pé dájúdájú Àwa l'A ṣẹ̀dá rẹ̀ láti inú àtọ̀? (Ṣebí lẹ́yìn) ìgbà náà l'ó di alátakò pọ́nńbélé. Àti pé ó fi àkàwé lélẹ̀ nípa Wa. Ó sì gbàgbé ìṣẹ̀dá rẹ̀. Ó wí pé: "Ta ni Ó máa sọ egungun di alààyè nígbà tí ó ti kẹfun?" Sọ pé: "Ẹni tí Ó ṣẹ̀dá rẹ̀ nígbà àkọ́kọ́ l'Ó máa sọ ọ́ di alààyè. Òun sì ni Onímọ̀ nípa gbogbo ẹ̀dá. (Òun ni) Ẹni tí Ó mú iná jáde fun yín láti ara igi tútù. Ẹ sì ń fi ko iná. Ǹjẹ́ Ẹni tí Ó ṣẹ̀dá àwọn sánmọ̀ àti ilẹ̀ kò ní agbára láti dá irú wọn (mìíràn) bí? Rárá (Ó ní agbára). Òun sì ni Ẹlẹ́dàá, Onímọ̀. Àṣẹ Rẹ̀ nígbà tí Ó bá gbèrò kiní kan ni pé, Ó máa sọ fún un pé "Jẹ́ bẹ́ẹ̀." Ó sì máa jẹ́ bẹ́ẹ̀. Nítorí náà, mímọ́ ni fún Ẹni tí ìjọba gbogbo ǹǹkan wà ní ọwọ́ Rẹ̀. Ọ̀dọ̀ Rẹ̀ sì ni wọn yóò da yín padà sí. Ya-Seen 77-83)

A máa gbé àwọn òṣùwọ̀n déédé kalẹ̀ ní Ọjọ́ Àjíǹde. Nítorí náà, wọn kò níí ṣe àbòsí kiní kan fún ẹ̀mí kan. Kí (iṣẹ́) jẹ́ ìwọ̀n èso kardal (bín-íntín), A máa mú un wá. A sì tó ní Olùṣírò. Suuratul Anbiyaah: 47.

"Nítorí náà, ẹni tí ó bá ṣe iṣẹ́ rere ní òdíwọ̀n ọmọ iná-igún, ó máa rí i.""Ẹni tí ó bá sì ṣe iṣẹ́ aburú ní òdíwọ̀n ọmọ iná-igún, ó máa rí i." (Az-Zalzalah:7-8) "Wọ́n maa ṣi awọn ilẹkun ina fun ẹni ti ibinu ati ikorira ati iya Allahu kò lé lórí, wọn tun maa ṣi awọn ilẹkun ọgba idẹra fun awọn onigbagbọ ti n ṣe awọn iṣẹ̀ere."

"Àwọn mọlāika yóò máa pàdé wọn, (wọn yóò sọ pé): "Èyí ni ọjọ́ yín tí À ń ṣe ní àdéhùn fun yín." Al-Anbiya',103) Wọn yó sì da àwọn t'ó ṣàì gbàgbọ́ lọ sínú iná Jahnamọ níjọníjọ, títí di ìgbà tí wọ́n bá dé ibẹ̀, wọ́n máa ṣí àwọn ìlẹ̀kùn rẹ̀ sílẹ̀ (fún wọn). Àwọn ẹ̀ṣọ́ rẹ̀ yó sì sọ fún wọn pé: "Ǹjẹ́ àwọn Òjíṣẹ́ kan kò wá ba yín láti ààrin ara yín, tí wọ́n ń ké àwọn āyah Olúwa yín fun yín, tí wọ́n sì ń kìlọ̀ ìpàdé ọjọ́ yín òní yìí fun yín?" Wọ́n wí pé: "Rárá (wọ́n wá bá wa)." Ṣùgbọ́n ọ̀rọ̀ ìyà kò lé àwọn aláìgbàgbọ́ lórí ni.""A óò sọ pé: "Ẹ wọ ẹnu ọ̀nà iná Jahnamọ. Olùṣegbére (ni yín) nínú rẹ̀. Ibùgbé àwọn olùṣègbéraga sì burú." Àti pé A óò kó àwọn t'ó bẹ̀rù Olúwa wọn lọ sínú Ọgbà Ìdẹ̀ra níjọníjọ, títí di ìgbà tí wọ́n bá dé ibẹ̀, wọ́n máa ṣí àwọn ìlẹ̀kùn rẹ̀ sílẹ̀ (fún wọn). Àwọn ẹ̀ṣọ́ rẹ̀ yó sì sọ fún wọn pé: "Kí àlàáfíà máa ba yín. Ẹ̀yin ṣe iṣẹ́ t'ó dára. Nítorí náà, ẹ wọ inú Ọgbà Ìdẹ̀ra, (kí ẹ di) olùṣegbére (nínú rẹ̀)." Wọ́n á sọ pé: "Gbogbo ọpẹ́ ń jẹ́ ti Allāhu,

Ẹni tí Ó mú àdéhùn Rẹ̀ ṣẹ fún wa. Ó tún jogún ilẹ̀ náà fún wa, tí à ń gbé níbikíbi tí a bá fẹ́ nínú Ọgbà Ìdẹ̀ra." Ẹ̀san àwọn olùṣe-rere mà sì dára." (Az-Zumar71-75)
"Ọgba idẹra yii, eyi ti o ṣe wipe o n bẹ nibẹ ninu idẹra ti oju kan o ri ri, ti eti kan o gbọ ri, ti ko si wa si ọkàn abara kankan ri. Kò sí ẹ̀mí kan tí ó mọ ohun tí A fi pamọ́ fún wọn nínú àwọn ñǹkan ìtutù ojú. (Ó jẹ́) ẹ̀san ohun tí wọ́n ń ṣe níṣẹ́ (rere). Ǹjẹ́ ẹni t'ó jẹ́ onígbàgbọ́ òdodo dà bí ẹni t'ó jẹ́ òbìlẹ̀jẹ́ bí? Wọn kò dọ́gba. Ní ti àwọn t'ó gbàgbọ́ ní òdodo, tí wọ́n sì ṣe iṣẹ́ rere, àwọn ibùgbé (nínú) Ọ̀gbà Ìdẹ̀ra ń bẹ fún wọn. (Ó jẹ́) ohun tí A pèsè sílẹ̀ (dè wọ́n) nítorí ohun tí wọ́n ń ṣe níṣẹ́ (rere). Ní ti àwọn t'ó balẹ̀jẹ́, Iná ni ibùgbé wọn. Ìgbàkígbà tí wọ́n bá fẹ́ jáde kúrò nínú rẹ̀, A ó sì máa dá wọn padà sínú rẹ̀. A sì máa sọ fún wọn pé: "Ẹ tọ́ ìyà Iná tí ẹ̀ ń pè níró wò." (As-Sajdah17-20)
Àpèjúwe Ọgbà Ìdẹ̀ra èyí tí Wọ́n ṣe ní àdéhùn fún àwọn olùbẹ̀rù Allāhu (nìyí): àwọn omi odò wà nínú rẹ̀ tí kò níí yí padà àti àwọn odò wàrà tí adùn rẹ̀ kò níí yí padà àti àwọn odò ọtí dídùn fún àwọn t'ó máa mu ún àti àwọn odò oyin mímọ́. Àwọn onírúurú èso wà fún wọn nínú rẹ̀ àti àforíjìn láti ọ̀dọ̀ Olúwa wọn. (Ṣé ẹni tí ó wà nínú Ọgbà Ìdẹ̀ra yìí) dà bí olùṣegbére nínú Iná bí, tí wọ́n ń fún wọn ní omi gbígbóná mu, tí ó sì máa já àwọn ìfun wọn pútupùtu? (Muhammad:15) Dájúdájú àwọn olùbẹ̀rù (Allāhu) máa wà nínú àwọn Ọgbà àti ìdẹ̀ra. Wọn yóò máa jẹ ìgbádùn pẹ̀lú ohun tí Olúwa wọn fún wọn. Àti pé (Allāhu) yóò ṣọ́ wọn nínú ìyà iná Jẹhīm. Ẹ máa jẹ, ẹ máa mu ní gbẹdẹmukẹ nítorí ohun tí ẹ̀ ń ṣe níṣẹ́. Wọn yóò rọ̀gbọ̀kú sórí àwọn ibùsùn tí wọ́n tò ní ọ̀wọ̀ọ̀wọ́. A sì máa fún wọn ní àwọn ìyàwó ẹlẹ́yinjú ẹgẹ́. (At-Tuur :17-20)
"Ki Allahu sọ gbogbo wa di ọmọ ọgba idẹra"
"Origun kẹfa: Igbagbọ ninu kadara, eyi to dáa nibẹ ati eyi to buru"
"Ati pe gbogbo lilọ-bibọ ni inu ayé yii, kadara ti a ti kọ lati ọdọ Allahu ti iyi rẹ tobi ni". Àdánwò kan kò níí ṣẹlẹ̀ ní orí ilẹ̀ tàbí (kí ó ṣẹlẹ̀) sí ẹ̀yin àyàfi kí ó ti wà nínú Tírà ṣíwájú kí A t'ó dá ẹ̀dá. Dájúdájú ìyẹn rọ̀rùn fún Allāhu. (Al-Hadid:22)
Dájúdájú A ṣẹ̀dá gbogbo ñǹkan pẹ̀lú kádàrá. Suratul Qomar: 49. Ṣé o ò mọ̀ pé dájúdájú Allāhu l'Ó mọ ohun tí ń bẹ nínú sánmọ̀ àti ilẹ̀? Dájúdájú (àkọsílẹ̀) ìyẹn wà nínú tírà kan. Dájúdájú ìyẹn rọrùn fún Allāhu. (Al-Hajj:70)
Àwọn origun mẹ́fà yii, ẹni tí ó bá pé e ti o si ni igbagbọ si i gẹ́gẹ́ bí ó ṣe yẹ, yoo wa nínú àwọn ẹrú Ọlọhun ti wọn jẹ onigbagbọ (mumini). Àwọn ẹ̀dá lapapọ ju ara wọn lọ ni ipo igbagbọ, ipo igbagbọ ti o ga ju naa ni ipo IH'SAAN, oun naa ni dide ipo "ki o maa sin Ọlọhun bii ìgbà ti o n ri I, ti o o ba ri I, Oun n ri ọ". [4] "Ati pe awọn wọnyi ni awọn ẹsa ninu awọn ẹda, àwọn naa ni wọn maa jèrè ipo ti o ga ju ninu alujanna ninu awọn ipo Firdaos.

# 6- "Awọn ẹkọ Isilaamu ati awọn iwa rẹ"

## " 1- Awọn nkan ti wọn pa wa laṣẹ lati ṣe"

Eyi ni diẹ ninu awọn iwa ati ẹkọ Isilaamu, eyi ti o n ṣe ojúkòkòrò lati jẹ ki àwùjọ musulumi o ni i. A maa ka wọn ni ṣókí, ti a si n ṣe ojúkòkòrò láti fa àwọn iwa naa yọ nínú ẹ, àwọn ẹ̀kọ́ naa wa láti inú àwọn ibuṣẹrisi ipilẹ fun Isilaamu, àwọn naa ni Kuraani ati Hadiisi ojiṣẹ Ọlọhun (ki ikẹ ati ọla Ọlọhun máa bá a).

### " Akọkọ: Ọrọ òdodo

Isilaamu n ṣe e ni túláàsì fun àwọn Mùsùlùmí láti máa sọ òdodo, o si n ṣe e ni àmì ti o jẹ dandan fun wọn, ko si lẹtọọ fun wọn bi tii wu bi tii mọ ki wọn bọra kuro ninu ẹ, o wa n kilọ fun wọn gidigidi lati jina si iró pẹ̀lú agbekalẹ ti o dáńtọ́ ju ati iroyin ti o han ju, Ọlọhun ti ọla Rẹ ga sọ pe: Ẹ̀yin tí ẹ gbàgbọ́ ní òdodo, ẹ bẹ̀rù Allāhu, kí ẹ sì wà pẹ̀lú àwọn olódodo. [At-Taobah:19] Ojiṣẹ Ọlọhun - ki ikẹ ati ọla Ọlọhun maa ba a - sọ pe: Otitọ sisọ di ọwọ yin; nitori pe otitọ yoo maa tọni sọna lọ sibi daadaa, dajudaju daadaa o si maa tọni sọna lọ si ọgba alujanna, ọmọniyan o nii yẹ ko si nii gbo ni ẹni tí yoo maa sọ ododo, ti yoo si maa ṣe àwárí ododo titi ti wọn o fi kọ ọ silẹ lọdọ Ọlọhun pe olododo ni. Irọ pipa di ọwọ yin, ẹ jina si i; tori pé irọ pipa maa n tọka lọ si ẹṣẹ dida ni, bákannáà ni ẹṣẹ dida maa n tọka ẹni lọ si inu ina, ọmọniyan o ni yẹ ko si nii gbo ni ẹni tí yoo maa pa irọ, ti yoo si maa ṣe àwárí irọ pipa titi ti wọn o fi kọ ọ silẹ lọdọ Ọlọhun pe opurọ ni in.[5]
Irọ pipa o si ninu awọn iroyin awọn olugbagbọ ododo, ṣugbọn ninu awọn iroyin munaafiki ni o wa [6]. Ojiṣẹ Ọlọhun (Ki ikẹ ati ọla Ọlọhun maa ba a) sọ pe: Àmì ti a fi n da munaafiki mọ jẹ mẹta: Ti o ba sọrọ, yoo parọ, ti o ba ṣe adehun yoo yapa, ti wọn ba fi nnkan pamọ si ọdọ rẹ, yoo janba [7]

---

[4] "[5] Bukhari ni o gbe e jade 4777 "
[5] Bukhari ni o gbe e jade (6094) ati Muslim (2607)
[6] Munaafiki ni ẹni tí yoo maa ṣe bíi musulumi, ṣugbọn ni paapaa alamọri rẹ ati adisọkan rẹ ti ń bẹ lọkan rẹ, kii ṣe Mùsùlùmí.
[7] Hadiisi yii, Bukhari ni o gbe e jade: Kitaabul-Eeman, ipin (awọn ami ti a fi ń dá Munaafiki mọ)

Fun idi eleyii, awọn saabe alapọn-ọnle maa n fi iroyin ododo ṣe iwa wu, titi ti ọkan ninu wọn fi sọ pe: A o mọ nǹkan ti n jẹ irọ ni asiko ojiṣẹ Ọlọhun (Ki ikẹ ati ọla Ọlọhun maa ba a).

## Ẹlẹẹkeji: Dida awọn nnkan afipamọ-sini-lọwọ pada, ati pipe awọn adehun, ati ṣiṣe deedee laarin awọn eeyan.

Ọlọhun Ọba ti ọla Rẹ ga sọ pe: Dajudaju Allāhu n pa yin ni aṣẹ pe ki ẹ da agbafipamọ pada fun awọn olowo wọn. Ati pe nigba ti ẹ ba n dajọ laaarin awọn eniyan, ẹ dajọ pẹlu deedee An-Nisaa: 58 Ọlọhun ti O mọ tun sọ pe : Ki ẹ si mu adehun ṣẹ. Dajudaju adehun jẹ ohun ti A o beere nipa rẹ. Ẹ wọn òṣùwọ̀n kún nígbà tí ẹ bá wọ̀n ọ́n. Ẹ fi ìwọ̀n t'ó tọ́ wọ̀n ọ́n. Ìyẹn lóore jùlọ, ó sì dára jùlọ ní ìkángun. [Al-Israa:34, 35]
O si tun yin awọn olugbagbọ ododo pẹlu ọrọ Rẹ pe: (Àwọn ni) àwọn t'ó ń mú àdéhùn Allāhu ṣẹ. Àti pé wọn kì í tú àdéhùn. Ar-Ra'd 20

## Ẹẹkẹta: Mimaa tẹriba ati aiṣe igberaga:

Anabi (ki ikẹ ati ọla Ọlọhun maa ba a) jẹ ẹniti o ni itẹriba julọ ninu awọn eeyan, o maa n jokoo si aarin awọn saabe rẹ gẹgẹ bii pe o jẹ ọkan ninu wọn. O si korira ki awọn eeyan maa dide fun un nigba ti o ba de. Ẹniti o ba ba bukaata kan lọ si ọdọ rẹ, yoo gba a lọwọ mu ti yoo si maa mu un dani kaakiri, ko si ni ja ọwọ rẹ danu titi ti yoo fi ba a gbọ bukaata rẹ. O si pa awọn olugbagbọ ododo lasẹ pẹlu mimaa tẹriba. O sọ pe: Ọlọhun ti ranṣẹ si mi pe ki ẹ maa tẹriba, titi ẹni kankan ninu yin o fi nii maa ṣe faari lori ẹlomiran, bakan naa ti enikẹni o si nii tayọ ẹnu-àlà lórí ẹlomiran

## Ẹlẹẹkẹrin: Ọrẹ-tita ati mimaa nawo si awọn oju ọna rere:

Ọlọhun Ọba ti ọla Rẹ ga sọ pe: Ohunkóhun tí ẹ bá ń ná ní ohun rere, fún ẹ̀mí ara yín ni. Ẹ ò sì níí náwó àfi láti fi wá ojú rere Allāhu. Ohunkóhun tí ẹ bá sì ná ní ohun rere, A ó san yín ní ẹ̀san (rẹ̀) ní ẹ̀kún-rẹ́rẹ́. Wọn kò sì níí ṣàbòsí si yín. [Al-Baqarah:272] Ọlọhun si tun yin awọn olugbagbọ ododo pẹlu ọrọ Rẹ pe: Tòhun ti bí wọ́n ṣe ní ìfẹ́ sí (ọ̀rọ̀ tó), wọ́n ń fún mẹ̀kúnnù, ọmọ òrukàn àti ẹrú ní oúnjẹ jẹ. [Al-Insaan:8] Ọrẹ-tita jẹ iroyin ojiṣẹ Ọlọhun (Ki ikẹ ati ọla Ọlọhun maa ba a) ati awọn ti wọn ba kọṣe rẹ ninu awọn olugbagbọ ododo, owo kankan o nii ṣẹku si i lọwọ ayafi ki o na an si awọn oju ọna rere. Jaabir (Ki Ọlọhun ba wa yọnu si i) ti o jẹ ọkan ninu awọn saabe Anabi (Ki ikẹ ati ọla Ọlọhun maa ba a) sọ pe: Wọn o beere nnkan kan lọwọ ojiṣẹ Ọlọhun (Ki ikẹ ati ọla Ọlọhun maa ba a) ri ki o wa sọ pe rara. O si tun ṣeni loju ọyin lati maa ṣe apọnle alejo. O wa sọ pe: Ẹniti o ba jẹ ẹniti o ni igbagbọ ninu Ọlọhun ati ọjọ ikẹyin, ki o yaa maa ṣe apọnle alejo rẹ. Bakannaa ẹniti o ba jẹ ẹniti o ni igbagbọ ninu Ọlọhun ati ọjọ ikẹyin, ki o yaa maa so ẹbi rẹ pọ, ẹniti o ba jẹ ẹniti o ni igbagbọ ninu Ọlọhun ati ọjọ ikẹyin, ki o yaa maa sọ ọrọ rere abi ki o dakẹ.

## Ẹlẹẹkarun: Mimaa ṣe suuru ati nini ifarada lori ṣuta:

Ọlọhun Ọba ti ọla Rẹ ga sọ pe: ki o si ṣe suuru lori ohun ti o ba ṣẹlẹ si ọ. Dajudaju iyẹn wa ninu awọn ipinnu ọrọ t'o pọn dandan. [Luqmăn:17], Ọlọhun ti O mọ tun sọ pe : Ẹ̀yin tí ẹ gbàgbọ́ ní òdodo, ẹ fi sùúrù àti ìrun kíkí tọrọ oore (Allāhu). Dájúdájú Allāhu ń bẹ pẹ̀lú àwọn onísùúrù. [Al-Baqorah:153] Allah tun sọ pe: Dajudaju A si maa fi eyi t'o dara julọ si ohun ti wọn n ṣe nisẹ san awọn t'o ṣe suuru lẹsan wọn. [An-Nah'l:96] Anabi (Ki ikẹ ati ọla Ọlọhun maa ba a) jẹ ẹniti o ni suuru julọ ninu awọn eeyan ati ẹniti o maa n ni atẹmọra lori ṣuta ti wọn ba fi kan an, kii sii ṣe ẹniti o maa n fi aburu san aburu; awọn ijọ rẹ fi inira kan an nigba ti o n pe wọn si oju ọna ẹsin Isilaamu, wọn lu u, titi ti wọn fi gba ẹjẹ lara rẹ, ti yoo si maa nu ẹjẹ naa kúrò ni oju rẹ lẹniti n sọ pe: Ìwọ Ọlọhun, forijin awọn ijọ mi; tori pe wọn ko mọ nnkan ti wọn n ṣe. [8]

## Ẹlẹẹkẹfa: Ìtìjú

Mùsùlùmí jẹ oníwàmímọ́ onítìjú, ìtìjú jẹ akẹtun kan nínú àwọn akẹtun ìgbàgbọ́, ọ jẹ nǹkan ti o maa ti mùsùlùmí lọ sí gbogbo iṣẹ rere, ó sì máa ń kọ fún olówó rẹ kúrò níbi èébú àtí ìbàjẹ́ níbi ọrọ àti iṣẹ, Òjíṣẹ́ Ọlọrun- kí ikẹ àti ọlà Ọlọrun máa ba a- sọ báyìí pé: (Ìtìjú kìí wá àyàfi pẹlú oore)[9]

## "Ẹlẹẹkeje: Ṣíṣe dáadáa sí àwọn òbí méjèèjì"

Ṣíṣe daadaa si àwọn òbí méjèèjì àti níní ìbálòpọ̀ dáadáa pẹlú wọn, àti rìrẹ iyẹ apá ẹni nílẹ̀ fún àwọn méjèèjì wa ninu awọn ọranyan ipilẹ nínú ẹ̀sìn ìsìláàmù, ohun tí ó jẹ dandan yìí yóò sì máa lékún sii ní ohun tí a o máa kanpa mọ ní gbogbo ìgbà tí àwọn òbí méjèèjì bá ti ń dàgbà tí wọn sì n ní bùkáátà sí ọmọ wọn. Ọlọrun ọba àlekè ọlá sì ti pàṣẹ ṣíṣe dáadáa sí àwọn òbí méjèèjì nínú ìwé Rẹ, O sì tún kanpa mọ títóbi iwọ wọn. Ọlọrun tí O tóbi jùlọ sọ pé: Olúwa rẹ pàṣẹ pé: "Ẹ má ṣe jọ́sìn fún ẹnì kan àyàfi Òun. Kí ẹ sì ṣe dáadáa sí àwọn òbí (yín) méjèèjì. Tí ọ̀kan nínú àwọn méjèèjì tàbí ìkíní kejì wọn bá dàgbà sí ọ lọ́dọ̀, má ṣe ṣíọ̀ sí wọn, má ṣe jágbe mọ́ wọn. Máa bá àwọn méjèèjì sọ ọ̀rọ̀ àpọ́nlé. Kí ó sì rẹ apá rẹ nílẹ̀ láti fi bọ̀wọ̀

---

[8] Hadiisi yii, Bukhari ni o gbe e jade ninu Kitaabul Mur'taddeen, ipin (9/20)
[9] Ìmáámù Bùkháárí ni ó gbe Àdíísì nàà jáde: Nínú Tírà AL-ADAB ojupọnna ìtìjú (8/35)

fún àwọn méjèèjì nípa ṣíṣe àánú wọn. Kí o sì sọ pé: "Olúwa Ẹlẹ́dàá mi, kẹ́ àwọn méjèèjì gẹ́gẹ́ bí wọ́n ṣe rè mí ní kékeré." [Al-Israa: 23,24]"

Ọlọhun ti O mọ tun sọ pe : Àti pé A pa á ní àṣẹ fún ènìyàn nípa àwọn òbí rẹ̀ méjèèjì - ìyá rẹ̀ gbé e ká (nínú oyún) pẹ̀lú àìlera lórí àìlera, ó sì gba ọmú lẹ́nu rẹ̀ láààrin ọdún méjì – (A sọ) pé: “Dúpẹ́ fún Èmi àti àwọn òbí rẹ méjèèjì.” Ọ̀dọ̀ Mi sì ni àbọ̀ ẹ̀dá. Luqman: 14

Arákùnrin kan béèrè lọwọ ojiṣẹ Ọlọ́run- kí ikẹ àti ọlà Ọlọhun máa ba a- pé: (Taani ó ní ẹtọ jù sí ibalopọ dáadáa mi? Anọbi dáhùn pé: " "(Ìyá rẹ ni, arákùnrin yìí sọ pé: Lẹ́yìn náà taani? O sọ pé: Ìyá rẹ, ó tún sọ pé: Lẹ́yìn náà taani? O sọ pé: Ìyá rẹ, ó tún ní lẹyìn náà taani: O sọ pé: Bàbá rẹ)[10]"

"Nítorí ìdí èyí, ẹ̀sìn ìsìláàmù ṣe é ní dandan fún mùsùlùmí láti tẹ̀lé àwọn òbí rẹ̀ méjèèjì níbi gbogbo ohun tí wọ́n bá pa a láṣẹ àyàfi tó bá jẹ́ ìyapa Ọlọ́run nìkan; torí pé a kò gbọdọ̀ máa tẹ̀lé ẹ̀dá alàáyè kankan láti fi yapa Ọlọrun Ọba Adẹ́dàá. Ọlọ́run Ọba Aleke ọlá sọ báyìí pé: " "(Tí àwọn méjèèjì bá sì jà ọ́ lógun pé kí ó fi ohun tí ìwọ kò ní ìmọ̀ nípa rẹ̀ ṣẹbọ sí Mi, má ṣe tẹ̀lé àwọn méjèèjì, Fi dáadáa bá àwọn méjèèjì lò pọ̀ ní ilé ayé)" Luqman: 15 Gẹ́gẹ́ bi o ṣe ṣe e ni dandan fún un láti maa rẹ ara rẹ silẹ fun wọn, ki o si maa pọn wọn le pẹ̀lú ọ̀rọ̀ àti ìṣe, ati ṣíṣe dáadáa si wọn pẹ̀lú gbogbo nǹkan ti o ba ni ni ikapa ninu awọn oríṣiríṣi daadaa bii bibọ wọn, ati rira aṣọ fun wọn, ati titọju alàìsàn wọn, ati titi suta dànù fun wọn, ati ṣíṣe adua fun wọn, ati titọrọ aforijin fun wọn, ati mimu adehun wọn ṣe, ati ṣíṣe apọnle ọ̀rẹ́ wọn.

## "Ẹlẹ́ẹkẹjọ: Wíwu ìwà dáadáa sí àwọn ẹlòmíràn:"

Anabi – ki ike ati ola Olohun maa ba a – so pe: "(Mùùmìní tí ó pé jù ní ìgbàgbọ́ ni èyí tí ó bá dára jù ní ìwà) [11]

O tun so – ki ike ati ola Olohun maa ba a – pe: "Dájúdájú nínú àwọn tí mo nífẹ̀ẹ́ sí jù nínú yín, àti àwọn tí wọn yóò sunmọ mi jù ní ìjókòó lọjọ ìgbéǹde àlùkìyámọ̀ ni àwọn tí wọn bá dára jù nínú yín ní ìwà)[12]"

Ọlọhun Ọba ròyìn Anọbi rẹ- ki ikẹ ati ọla Ọlọhun máa bá a- pẹlu gbólóhùn Rẹ pe: Dájúdájú ìwọ sì wà lórí ìwà àpọ́nlé. Al-Qalam 4 O tun so – ki ike ati ola Olohun maa ba a – pe: (Dájúdájú Ọlọhun gbé mi dìde láti wá pé àwọn ìwà rere)[13] Fun idi eyi, o jẹ dandan fun Mùsùlùmí ki o ni iwa rere si awọn obi rẹ gẹ́gẹ́ bí a ṣe sọ ṣíwájú, ki o si ni iwa rere si awọn ọmọ rẹ, ni ẹni tí yoo maa rè wọn ni rire ti o dáa, ti yoo maa kọ wọ́n ni ẹkọ Isilaamu, yoo si gbe wọn jina si nǹkan ti o ba le pa wọn lara ni ayé ati ni alukiyaamọ, yoo si maa náwó le wọn lori titi ti wọn yoo fi dá dúró, ti wọn maa ni ikapa lati ṣiṣẹ́. Gẹ́gẹ́ bẹẹ naa ni o ṣe maa ni iwa dáadáa si ìyàwó rẹ ati awọn ọmọ-ìyá rẹ lọkunrin ati lobinrin, ati si awọn mọlẹbi rẹ, ati awọn alabagbe rẹ, ati si awọn eeyan lapapọ. Yoo maa fẹ́ fun àwọn ọmọ-iya rẹ nǹkan ti o ba n fẹ funra rẹ, yoo si maa da ẹbi ati alabagbe pọ, yoo maa ṣe apọnle àgbàlagbà wọn, yoo si maa ṣaanu àwọn ọmọdé wọn, yoo si maa ṣe abẹwo ẹni ti àjálù ba kan, yoo si maa pẹ̀tù si i lọkan láti ṣe àmúlò gbólóhùn Ọlọhun ti O sọ pe: Ẹ ṣe dáadáa sí àwọn òbí méjèèjì àti ẹbí àti àwọn ọmọ òrukàn àti àwọn mẹ̀kúnnù àti aládùúgbò t’ó súnmọ́ àti aládùúgbò t’ó jìnnà àti ọ̀rẹ́ alábàárìn àti ẹni tí agara dá lórí ìrìn-àjò An-Nisaa: 36 Àti ọ̀rọ̀ ànọ́bì (ki ikẹ ati ọla Ọlọhun máa bá a) ti o sọ pe:" (Ẹnití ó bá gba Ọlọhun gbọ́ àti ọjọ́ ìkẹhìn, kò gbọdọ̀ fi sùtá kan alábàágbé rẹ̀ )[14]"

## Ẹlẹ́ẹ̀kẹsàn-án: Ìgbìyànjú sí ojú ònà Ọlọhun fún ríran ẹnití wọ́n ṣe àbòsí rẹ̀ lọ́wọ́, àti fífi òdodo rinlẹ, àti fífọn déédéé ká"

Ọlọhun Ọba ti ọla Rẹ ga sọ pe: Fún ààbò ẹ̀sìn Allāhu, ẹ pa àwọn t’ó ń jà yín lógun. Kí ẹ sì má ṣe tayọ ẹnu-àlà. Dájúdájú Allāhu kò nífẹ̀ẹ́ àwọn olùtayọ ẹnu-àlà. [Al-Baqorah: 190]" Ọlọhun Ọba ti ola Rẹ ga tún sọ pé:" Kí l’ó ṣe yín tí ẹ ò níí jagun fún ẹ̀sìn Allāhu, nígbà tí àwọn aláìlágbára nínú àwọn ọkùnrin, àwọn obìnrin àti àwọn ọmọdé (sì ń bẹ lórí ilẹ̀), àwọn t’ó ń sọ pé: “Olúwa wa, mú wa jáde kúrò nínú ìlú yìí, ìlú

---

[10] Ìmáàmù Bùkháárí ni ó gbe Àdíìsì náà jáde: Nínú Tírà AL-ADAB, ojúpọ̀nnà "Taani ó ní ẹtọ jù sí ibalopọ dáadáa"(8/2)

[11] Abu Daa'ud ni o gbe e jade: Tira AS-SUNNAH, ojupọnna ẸRI LORI ALEKUN ATI ADINKU RẸ (5/6) ati Tirmiziy ninu tira AR-RỌDỌỌHU, ojupọnna "Nǹkan ti o wa nipa ẹtọ obìnrin lórí ọkọ rẹ (3/457), Tirmiziy wa sọ pé: O dáa, o si ni àlàáfíà, ninu idajọ ti Al-Baaniy: Wo "Sọhiihu Abii Daa'ud" (3/886)

[12] Ìmáàmù Bùkháárí ni ó gbe Hadiisi náà jade: Nínú Kitaabul-Manaaqib, ojupọnna Ìròyìn Anọbi Muhammad (ki ikẹ ati ọla Ọlọhun máa bá a) (4/230), pẹ̀lú gbólóhùn (Dajudaju nínú àwọn ẹni rere nínú yín ní àwọn tí wón dára jù ní ìwà).

[13] Ìmáàmù Ahmad ni ó gbe e jade ninu Musnad (17/80), Ahmad Shakir wáá sọ pé: Isnaadu rẹ̀ ní àlàáfíà, Ìmáàmù Bùkháárí náà gbe e jade ninu Al-Adab, àti Ìmáàmù Bayhaqiy ninu Shuhabul-Eemaan, àti Al Haakim ninu Al-Mustadrok"

[14] Ìmáàmù Bùkháárí ni ó gbe e jade ninu Kitaabul Adab, ojúpọ̀nnà "Ẹnití o bá gba Ọlọhun gbọ àti ọjọ́ ìkẹhìn kí ó má fi sùtá kan alábàágbé rẹ̀:(8/13)"

àwọn alábòsí. Fún wa ní aláàbò kan láti ọ̀dọ̀ Rẹ̀. Kí Ó sì fún wa ní aláràǹṣe kan láti ọ̀dọ̀ Rẹ.” [An-Nisai : 75]"

Afojusun jijagun ti Isilaamu naa ni fifi òdodo rinlẹ, ati fifọn déédéé ká, ati dida oju ìjà kọ àwọn ti wọn n ṣe àbòsí fun àwọn ẹrú Ọlọhun, ti wọn n funlẹ mọ wọn, ti wọn si kọ fun wọn lati jọsin fun Ọlọhun, ati lati gba Isilaamu. Ni idakeji ẹ̀wẹ̀, o tun kọ irori ìjẹninípá láti gba Isilaamu. Ọlọhun ti ọla Rẹ ga sọ pe: "(Kòsí ìjẹninípá nínú ẹ̀sìn)" [Al-Baqorah : 256]"

Lásìkò ogun, kò tọ́ fún mùsùlùmí láti pa obìnrin ati ọmọdé ati àgbàlagbà, bí kò ṣe pé àwọn jagunjagun alábòsí ni wọn máa bá ja.

"Ẹnití wọn ba pa si oju ọna Allahu ti ọla Rẹ ga, iru ẹni bẹẹ ti ku iku ṣẹhiidi, o si maa ni ipo ati ẹsan lọdọ Allahu ti ọla Rẹ ga. Allahu ti ọla Rẹ ga sọ pe: " Ẹ má ṣe lérò pé òkú (ìyà) ni àwọn tí wọ́n pa s’ójú ogun ẹ̀sìn Allāhu, àmọ́ alààyè (ẹni ìkẹ́) ni wọ́n. Wọ́n sì ń pèsè ìjẹ-ìmu fún wọn lọ́dọ̀ Olúwa wọn. Wọ́n ń dunnú nítorí ohun tí Allāhu fún wọn nínú oore-àjùlọ Rẹ̀. Wọ́n sì ń yọ̀ fún àwọn tí kò tí ì pàdé wọn nínú àwọn tí wọ́n fi sílẹ̀ pé: “Kò sí ìpáyà fún wọn. Wọn kò sì níí banújẹ́.” Aal-Imraan: 169‹170

## "Ẹlẹẹkẹwaa: Adua ati iranti ati kika Alukuraani:"

Gbogbo ìgbà tí ìgbàgbọ́ mumini ba ti n lekun naa ni asopọ rẹ mọ Ọlọhun naa maa lekun, ati pipe E, ati ifaragbolẹ rẹ ni iwájú Rẹ pẹ̀lú gbigbọ bùkátà rẹ ni ayé, ati ṣíṣe aforijin ẹṣẹ rẹ, ati gbigbe ipo re ga ni ọjọ́ ìkẹyìn. Ọba Ọlọrẹ ni Ọlọhun, O si nífẹ̀ẹ́ si ki wọn maa tọrọ nǹkan lọ́wọ́ Oun, O sọ pe: "Nígbà tí àwọn ẹrúsìn Mi bá bi ọ léèrè nípa Mi, dájúdájú Èmi ni Olùsúnmọ́. Èmi yóò jẹ́pè àdúà aládùúà nígbà tí ó bá pè Mí." [Al-Baqara:186] "Allahu a gba adua naa ti o ba jẹ oore fun ẹrusin, yoo si san ẹsan fun ẹrusin naa fun adua yii.”

Ninu awọn ìròyìn mumini naa ni ṣíṣe ìrántí Ọlọhun ni ọpọlọpọ ni ọsan ati alẹ, ni jẹ́ẹ́jẹ́ ati síta, yoo waa gbe Olohun tobi pẹ̀lú oríṣiríṣi igbetobi ati ìrántí bíi gbolohun: "Subhaanallooh", ati "Alhamdulillaah", ati "Laa ilaaha illal Looh", ati Allahu Akbar, ati nǹkan ti o yatọ si ìyẹn nínú àwọn gbólóhùn ìrántí Ọlọhun, Ọlọhun si fi ẹsan ńlá rinlẹ fun un. Ojiṣẹ- ki ikẹ ati ọla Ọlọhun máa bá a- sọ pé: (Awọn Mufarriduun ti gba waju, wọn sọ pe: Tani Mufarriduun, iwọ ojiṣẹ Allahu? O sọ pe: Awọn naa ni àwọn ti wọn n ṣe iranti Allahu lọpọlọpọ lọkunrin, ati lobinrin) [15]. Ọlọhun ti O mọ tun sọ pe : Ẹ̀yin tí ẹ gbàgbọ́ ní òdodo, ẹ rántí Allāhu ní ìrántí púpọ̀. "Ẹ ṣàfọ̀mọ́ fún Allāhu ní àárọ̀ àti ní ìrọ̀lẹ́." (Al-Ahzab:41-42) "Allahu tun sọ pe: "Nítorí náà, ẹ rántí Mi, Mo máa rántí yín. Ẹ dúpẹ́ fún Mi, ẹ má ṣàì moore sí Mi". -(Al-Baqarah:152) "Ninu iranti naa ni kika Kuraani, bi ẹru ba ṣe n ka Kuraani si, ti o si n ronu nipa ìtumọ̀ rẹ si, naa ni ipo rẹ o ṣe maa ga lọdọ Allahu.”

“Wọn maa sọ fun oluka AluKuraani ni ọjọ igbedide pe:” “Máa kà, maa goke lọ, maa ka gẹ́gẹ́ bi o ti maa n ka ni aye; nitori pe ipò rẹ wa nibi òpin aaya ti o n ka.” [16]

## "Ẹlẹẹkọkanla": Kikọ ẹkọ imọ ti shariah, ati fifi mọ awọn eniyan, ati pipepe lọ sibẹ:

O sọ – ki ikẹ ati ọla Ọlọhun maa ba a– pe: “Ẹnikẹni ti o ba tọ ọna kan ti o n wa imọ nibẹ, Allahu yoo ṣe e ni irọrun lati jẹ ọna fun un lọ sí alujanna, dajudaju awọn Malaika maa n tẹ iyẹ wọn silẹ fun ẹni tí n wa imọ lati fi ìyọ́nú wọn han si nǹkan ti o n ṣe. [17]

O tun so – ki ike ati ola Olohun maa ba a – pe: “(Ẹni ti o loore julọ ninu yin ni ẹni ti o kọ Kuraani ti o wa fi kọ ẹlòmíràn) [18]" O tun so – ki ike ati ola Olohun maa ba a – pe: “(Dájúdájú awọn Malaika maa n ṣe adua fun awọn olukọ awọn eniyan ni daada) [19]. O tun so – ki ike ati ola Olohun maa ba a – pe: “(Ẹnikẹni ti o ba pepe lọ sí imọna kan, yoo ni ẹsan gẹ́gẹ́ bii ti àwọn ti wọn n lò ó, laisi adinku kankan ninu ẹsan wọn.” [20]

Ọlọhun ti O mọ tun sọ pe : "Ta ni ó dára jùlọ ní ọ̀rọ̀ sísọ t’ó tayọ ẹni tí ó pèpè sí ọ̀dọ̀ Allāhu, tí ó ṣe iṣẹ́ rere, tí ó sì sọ pé: "Dájúdájú èmi wà nínú àwọn mùsùlùmí." (Fussilat:33)

## Ẹlẹẹkejila: Iyọnu si idajọ Allahu ati Ojiṣẹ Rẹ:

---

[15] "“[18] Muslim ni o gbe Hadiisi naa jade: Tira iranti ati adua - Abala iṣenilojukokoro si iranti (4/17).”

[16] “[19] Abu Dawood ni o gbe e jade (1464), gbólóhùn naa si ni ti ẹ̀, ati Tirmidhi (2914), ati Nasa’i ninu (As-Sunan al-Kubra) (8056), ati Ahmad (6799).

[17] Tirmiziy ni o gbe e jade: Àwọn ojupọnna mimọ, ojupọnna ọla ti n bẹ fun agboye ninu ìjọsìn (4/153), ati Abu Daa'ud: Tira imọ, ojupọnna "iṣeni lojukokoro lati wa imọ" (4/5857), ati Ibnu Maajah nínú Al-Mukọddimọ (1/81), Albaaniy sọ pé o ni àlàáfíà (Sohiihul Jaamih 5/302).

[18] “[21] Hadiisi naa, Bukhari ni o gbe e jade: Iwe "Awọn Aṣegbọrẹ, Abala:" Ẹni ti o dara julọ ninu yin ni ẹniti o kọ Kuraani ti o si fi mọ ẹlòmíràn (6/236).

[19] “[22] Hadiisi naa, Tirmidhi ni o gbe e jade: Iwe" Imọ", abala" Nnkan ti o wa nipa ọlá agbọye ẹsin lórí ijọsin (5/50) pẹlu ọrọ to gun."

[20] “[23] Muslim ni o gbe e jade: Iwe "Imọ", Abala "Ẹniti ti ṣe àfihàn ìlànà ti o dara tabi ti o buru" (16/227)

Àìtako nǹkan ti Ọlọhun ṣe ni òfin, Ọlọhun ni o mọ ẹjọ da ju lọ nínú àwọn oludajọ, Oun si ni O ni aanu ju lọ ninu awọn aláàánú, nǹkan kan ko pamọ́ fun Un ni ilẹ ati sanmọ, ìdájọ́ rẹ kii lapa pẹ̀lú ifẹ-inu àwọn ẹrusin, ati irankan àwọn apàṣẹwàá, ninu aanu Rẹ naa ni pe O ṣe lofin fun àwọn ẹrusin Rẹ nǹkan ti o maa ṣe wọ́n ní àǹfààní ni ayé ati ni ọjọ́ ìkẹyìn, ko si la bọ wọn lọrun ohun ti wọn ko ni ikapa rẹ, lara nǹkan ti ijẹ ẹrusin n wá naa ni gbigbe ẹjọ lọ ba nǹkan ti Ọlọhun ṣe lofin nibi gbogbo àlámọ̀rí pẹ̀lú yiyọnu si i pátápátá
Ọlọhun Ọba ti ọla Rẹ ga sọ pe: Rárá, Èmi fi Olúwa rẹ búra pé wọn kò tí ì gbàgbọ́ ní òdodo títí wọn yóò fi gbà ọ́ ní olùdájọ́ lórí ohun tí ó bá dá yánpọnyánrin sílẹ̀ láàárin wọn. Lẹ́yìn náà, wọn kò níí ní ẹ̀hónú kan sí ìdájọ́ tí o bá dá. Wọ́n sì máa gbà pátápátá. Sūratun Nisā': 65 Ọlọhun ti O mọ tun sọ pe : Ṣé ìdájọ́ ìgbà àìmọ̀kan ni wọ́n ń wá ni? Ta ni ẹni tí ó dára ju Allāhu lọ níbi ìdájọ́ fún ìjọ t'ó ní àmọ̀dájú (nípa Rẹ̀)? (Al-Ma'idah:50)

# "2- Awọn nnkan eewọ ati awọn nǹkan ti a kọ̀"

## "Akọkọ: Ẹbọ: (yiyi eyikeyi ninu iran ijẹ ẹrusin fun ẹlòmíràn ti o yatọ si Allahu ti ọla Rẹ ga):

gẹ́gẹ́ bíi ẹni tí n fori balẹ fun nǹkan ti o yatọ si Ọlọhun, tabi o n pe nǹkan ti o yatọ si Ọlọhun, tabi o n wa bibiya bùkátà rẹ lọdọ rẹ, tabi o n du ẹran àsè fun nǹkan ti o yatọ si Ọlọhun, tabi o n ṣe èyíkéyìí ninu awọn iran ijẹ ẹrusin fun nǹkan ti o yatọ si Ọlọhun, boya ẹni tí wọ́n n pe yii jẹ alàáyè ni tabi òkú, tabi sàréè, tabi oosa, tabi okuta, tabi igi, tabi Malaika, tabi Anọbi, tabi wòlíì, tabi ẹranko, tabi nǹkan ti o yatọ si i. Gbogbo eleyii jẹ ẹbọ ti Ọlọhun ko nii fi ori rẹ jin ẹrusin àyàfi ti o ba tuuba ti o si tun wọnu Isilaamu pada ni tuntun.
Ọlọhun Ọba ti ọla Rẹ ga sọ pe: Dájúdájú Allāhu kò níí foríjin (ẹni tí) ó bá ń ṣẹbọ sí I. Ó sì máa ṣàforíjìn fún ohun mìíràn yàtọ̀ sí ìyẹn fún ẹni tí Ó bá fẹ́. Ẹni tí ó bá ń ṣẹbọ sí Allāhu, dájúdájú ó ti dá àdápa irọ́ (tí ó jẹ́) ẹ̀ṣẹ̀ ńlá. (An-Nisa',48) Musulumi kọ gbọ máa sin nkankan yatọ si Allāh, ko si gbọdọ maa pe nǹkan kan àyàfi Allāh, ko sì gbọdọ tẹriba fún nkankan àyàfi Allāh, Allāh ti ọlá Rẹ ga sọ pe: Sọ pé: "Dájúdájú ìrun mi, ẹran (pípa) mi, ìṣẹ̀mí ayé mi àti ikú mi ń jẹ́ ti Allāhu, Olúwa gbogbo ẹ̀dá. Kò sí akẹgbẹ́ fún Un. Ìyẹn ni Wọ́n pa láṣẹ fún mi. Èmi sì ni ẹni-àkọ́kọ́ àwọn mùsùlùmí (ní àsìkò tèmi)." Al-An"aam:162-163
Ninu ẹbọ bákannáà ni: Nini adisọkan wipe dajudaju Ọlọhun ni ìyàwó tàbí ọmọ- Ọlọhun ga tayọ ìyẹn gan-tabi nini adisọkan wipe awọn ọlọhun míràn tun n bẹ lẹyin Allāh ti wọn n dari ayé yi. Tí ó bá jẹ́ pé àwọn ọlọ́hun kan wà nínú sánmọ̀ àti ilẹ̀ lẹ́yìn Allāhu, sánmọ̀ àti ilẹ̀ ìbá ti bàjẹ́. Mímọ́ ni fún Allāhu, Olúwa Ìtẹ́-ọlá, tayọ ohun tí wọ́n ń fi ròyìn (Rẹ̀). Sūratul Anbiyā': 22

## Ẹlẹ́ẹkeji: Idan, yiyẹ iṣẹ wo, ati pipe apemọra imọ kọkọ.

Idan ati yiyẹ-iṣẹ-wo jẹ iṣẹ́ keferi, opidan o si le jẹ opidan ayaafi ki o ni asopọ pẹlu awọn èṣù, ati ki o jọ́sìn fun wọn lẹyin Ọlọhun, fún ìdí yẹn ko lẹtọọ fún Musulumi ki o lọ sí ọdọ àwọn opidan, ko sì lẹtọọ fún un ki o gba wọn gbọ nibi nkan ti wọn fi n parọ nipa pipe apemọra ìmọ̀ kọkọ wọn, ati nibi awọn nǹkan ti wọn n fún ni ni iro rẹ nipa awọn iṣẹlẹ ati awọn iroyin ti wọn n lero pe o maa ṣẹlẹ̀ ni ọjọ iwaju"
Ọlọhun Ọba ti ọla Rẹ ga sọ pe: Sọ pé: "Àwọn t'ó wà nínú àwọn sánmọ̀ àti ilẹ̀ kò nímọ̀ ìkọ̀kọ̀ àfi Allāhu Sūratun Naml: 65. Ọlọhun ti O mọ tun sọ pe : Onímọ̀-ìkọ̀kọ̀, kò sì fi (ìmọ̀) ìkọ̀kọ̀ Rẹ̀ han ẹnì kan àyàfi ẹni tí Ó ṣàlẹ́ṣà t'ó jẹ́ Òjíṣẹ́. Dájúdájú Ó ń mú ẹ̀ṣọ́ kan rìn níwájú Òjíṣẹ́ náà àti lẹ́yìn rẹ̀ Suuratul Jinn: 26-27.

## Ẹlẹ́ẹkẹta: Abosi

Abosi, ojú ọna kan ti o fẹ ni, ti ọpọlọpọ awọn iṣẹ aburú àti àwọn iroyin buruku wọ inu rẹ, eleyii ti máa n lapa lara onikaluku. O wọ inú rẹ abosi èèyàn kan sí ẹmi ara rẹ, ati abosi rẹ sí àwọn tí wọn yí i ka, ati abosi rẹ sí àwùjọ rẹ, kódà ti o fi dórí abosi rẹ sí àwọn ọta rẹ, Ọba tí ọla Rẹ ga sọ pe: Ẹ má ṣe jẹ́ kí ìkórira àwọn ènìyàn kan tì yín láti má ṣe déédé. Ẹ ṣe déédé, òhun l'ó súnmọ́ ìbẹ̀rù Allāhu jùlọ. Al-Maa'ida: 8 Ọlọhun ti ọla Rẹ ga ti fún wa ní ìró wipe Oun ko nífẹ̀ẹ́ awọn alabosi. Òjíṣẹ́ Ọlọhun- ki ikẹ ati ọla Ọlọhun máa bá a-sọ pe: Ọlọhun ti ọla Rẹ ga sọ pe: (Ẹyin ẹrusin Mi, dajudaju Mo ṣe abosi ni eewọ fún Ẹmi ara Mi, Mo si ṣe e ni eewọ laarin yin naa; nítorí náà ẹ ma ṣe ṣe abosi ara yín). O tun so – ki ike ati ola Olohun maa ba a – pe: (Ran ọmọ-iya rẹ alabosi ati ẹnití wọn bo si lọwọ. Ni arakunrin kan wa sọ pe: Irẹ ojiṣẹ Ọlọhun, máa ran an lọwọ ti o ba jẹ ẹnití wọn bo si, sọ fún mi ti o ba jẹ alabosi, bawo ni máa ṣe ràn an lọwọ? O sọ pe: (Waa kọ fún un kuro nibi abosi, nítorí pé dajudaju ìyẹn ni riran an lọwọ).

## Ẹlẹ́ẹkẹrin: Pipa ẹmi ti Ọlọhun ṣe ni eewọ ayaafi pẹlu ẹtọ.

O jẹ ọran ti o tobi ninu ẹsin Islām ti Ọlọhun ṣe adehun iya ẹlẹta elero lori rẹ, ti O sí tun gbe awọn ìjìyà tí o le koko le e lori ní ayé, ìyẹn ni pipa apaayan ayaafi ti awọn èèyàn ẹnití wọn pa ba ṣe amojukuro, Ọlọhun ti ọla Rẹ ga sọ pe: Nítorí ìyẹn, A sì ṣe é ní òfin fún àwọn ọmọ 'Isrọ̄'īl pé dájúdájú ẹnikẹ́ni tí ó bá pa ẹ̀mí (ènìyàn) kan láìjẹ́ nítorí pípa ẹ̀mí (ènìyàn) kan tàbí ṣíṣe ìbàjẹ́ kan lórí ilẹ̀, ó dà bí ẹni tí ó pa gbogbo ènìyàn pátápátá. Ẹnikẹ́ni tí ó bá sì mú ẹ̀mí (ènìyàn) ṣẹ̀mí, ó dà bí ẹni tí ó mú gbogbo ènìyàn ṣẹ̀mí pátápátá. Suuratul Māidah: 32. Ọlọhun ti O mọ tun sọ pe : Ẹnikẹ́ni tí ó bá mọ̀ọ́mọ̀ pa onígbàgbọ́ òdodo kan, iná

Jahanamọ ni ẹsan rẹ. Olùṣegbére ni nínú rẹ̀. Allāhu yóò bínú sí i. Ó máa fi ṣẹ́bi lé e. Ó sì ti pèsè ìyà t'ó tóbi sílẹ̀ dè é. Sūratun Nisā': 93

## Ẹlẹẹkarun: Itayọ ààlà lori awọn eeyan nibi dukiya wọn.

Boya pẹlu ole jija ni, tabi gbigba ni tipa, tabi owó ẹyin, tàbí ṣíṣe gbájúẹ̀, tabi nkan ti o yatọ sí ìyẹn, Ọba ti ọla Rẹ ga sọ pe: Olè lọ́kùnrin àti olè lóbìnrin, ẹ gé ọwọ́ àwọn méjèèjì. (Ó jẹ́) ẹsan fún iṣẹ́ ọwọ́ àwọn méjèèjì. (Ó sì jẹ́) ìjìyà láti ọ̀dọ̀ Allāhu. Allāhu sì ni Alágbára, Ọlọ́gbọ́n. Sūratul Mā'idah: 38 Ọlọhun ti O mọ tun sọ pe : Ẹ̀yin kò gbọdọ̀ fi èrú jẹ dúkìá yín láààrin ara yín. Sūratul Baqorah: 188. Ọlọhun ti O mọ tun sọ pe : Dájúdájú àwọn t'ó ń jẹ dúkìá ọmọ òrukàn pẹ̀lú àbòsí, Iná kúkú ni wọ́n ń jẹ sínú ikùn wọn. Wọ́n sì máa wọ inú Iná t'ó ń jò. An-Nisaa 10

Islām gbe ogun ti ikọja ààlà lori awọn dukiya ẹlòmíràn gidigan, o sí lekoko nibi ìyẹn, o si tun gbe kalẹ lori olutayọ ààlà àwọn iya ti o lekoko ti yíò máa jẹ oludena fún ùn ati fún àwọn tó jọ ọ ninu awọn ti wọn n da ètò ati ifayabalẹ àwùjọ rú.

## Ẹlẹẹkẹfa: Irẹjẹ ati itanjẹ ati ijamba.

Ninu gbogbo ibara-ẹni-lopọ bii káràkátà, ati awọn àdéhùn, àti nkan ti o yatọ sí ìyẹn, o jẹ awọn ìròyìn eebu eléyìí ti Islām kọ ti o si tun sọ ni lara kuro níbẹ.

Ọlọhun Ọba ti ọla Rẹ ga sọ pe: Ègbé ni fún àwọn olùdín-òṣùwọ̀n-kù, àwọn (òǹtajà) t'ó jẹ́ pé nígbà tí wọ́n bá wọn ǹǹkan lọ́dọ̀ àwọn ènìyàn, wọ́n á gbà á ní ẹ̀kún, nígbà tí àwọn (òǹtajà náà) bá sì lo ìwọ̀n fún àwọn (òǹrajà) tàbí lo òṣùwọ̀n fún wọn, wọn yóò dín in kù. Ṣé àwọn wọ̀nyẹn kò mọ̀ dájú pé dájúdájú A máa gbé wọn dìde ní Ọjọ́ ńlá kan? Ní ọjọ́ tí àwọn ènìyàn yóò dìde nàró fún Olúwa gbogbo ẹ̀dá. Al-Mutaffifiin 1-5 O tun so – ki ike ati ola Olohun maa ba a – pe: (Ẹniti o ba rẹ wa jẹ kii ṣe ara wa). [21] Allah tun sọ pe: Dajudaju Allāhu ko fẹran ẹnikẹni ti o jẹ onijanba, ẹlẹṣẹ. [An-Nisaa:107]

## Ẹlẹẹkeje: Títayọ ààlà lórí àwọn ènìyàn.

nibi ijẹ-ọmọlúwàbí wọn pẹ̀lú bibu èébú àti sísọ ọrọ-ẹyin ati ofofo, ati keeta, ati èrò burúkú, ati itọpinpin, ati ifiniṣe-yẹyẹ, ati nǹkan ti o yatọ si iyẹn. Isilaamu n ṣe ojúkòkòrò láti gbe àwùjọ ti o mọ́ dúró, ti ìfẹ́ maa jọba nibẹ, ati ijẹ ọmọ-iya, ati irẹpọ, ati ìran-ara-ẹni-lọwọ, torí naa ni o ṣe n gbógun ti gbogbo àìsàn àwùjọ ti o le ṣe okunfa ki àwùjọ o tuka, ati hihan ìkórìíra ati imọtara-ẹni-nikan láàrin àwọn ènìyàn rẹ.

Ọlọhun Ọba ti ọla Rẹ ga sọ pe: Ẹ̀yin tí ẹ gbàgbọ́ ní òdodo, àwọn ènìyàn kan kò gbọ́dọ̀ fi àwọn ènìyàn kan ṣe yẹ̀yẹ́. Ó lè jẹ́ pé àwọn (tí wọ́n sọ di oníyẹ̀yẹ́) dára ju àwọn (t'ó ń ṣe yẹ̀yẹ́). Àwọn obìnrin kan (kò sì gbọ́dọ̀ fi) àwọn obìnrin kan (ṣe yẹ̀yẹ́). Ó lè jẹ́ pé àwọn (tí wọ́n sọ di oníyẹ̀yẹ́) dára ju àwọn (t'ó ń ṣe yẹ̀yẹ́). Ẹ má ṣe búra yín. Ẹ má pe'ra yín lóríkì burúkú lẹ́yìn ìgbàgbọ́ òdodo. Ẹnikẹ́ni tí kò bá ronú pìwàdà, àwọn wọ̀nyẹn ni àwọn alábòsí. Ẹ̀yin tí ẹ gbàgbọ́ ní òdodo, ẹ jìnnà sí ọ̀pọ̀lọ́pọ̀ àròsọ. Dájúdájú apá kan àròsọ ni ẹ̀ṣẹ̀. Ẹ má ṣe tọpinpin ara yín. Kí apá kan yín má ṣe sọ̀rọ̀ apá kan lẹ́yìn. Ṣé ọ̀kan nínú yín nífẹ̀ẹ́ sí láti jẹ ẹran-ara ọmọ ìyá rẹ̀ t'ó ti kú ni? Ẹ sì kórira rẹ̀. Ẹ bẹ̀rù Allāhu. Dájúdájú Allāhu ni Olùgba-ìronúpìwàdà, Àṣàkẹ́-ọ̀run. [Al-Huj'raat:11, 12]

Gẹ́gẹ́ bi o ṣe jẹ́ pé Isilaamu n gbógun ti ẹlẹyamẹya, ati àìbánilò lọ́gbọọgba láàrin àwọn èèyàn nínú àwùjọ, bákan náà ni gbogbo èèyàn ri lójú rẹ, ko si ọlá fun larubawa lórí ẹni ti kii ṣe larubawa, funfun kan ko si ni ọla ju dúdú lọ àyàfi pẹ̀lú nǹkan ti o ba n bẹ ninu ọkan bii ẹsin ati ìpayà. Gbogbo ènìyàn yio maa fi iga gbaga bákan náà nibi awọn iṣẹ rere, Ọlọhun ti ọla Rẹ ga sọ pe: Ẹ̀yin ènìyàn, dájúdájú Àwa ṣẹ̀dá yín láti ara ọkùnrin àti obìnrin. A sì ṣe yín ní orílẹ̀-èdè orílẹ̀-èdè àti ìran-ìran nítorí kí ẹ lè dára yín mọ̀. Dájúdájú alápọ̀n-ọ́nlé jùlọ nínú yín lọ́dọ̀ Allāhu ni ẹni t'ó bẹ̀rù (Rẹ̀) jùlọ. Dájúdájú Allāhu ni Onímọ̀, Alámọ̀tán. [Al-Huj'raat:13]

## Ẹlẹẹkẹjọ: Mimaa ta tẹtẹ, ati ọti mimu, ati mimaa lo oogun oloro:

Ọlọhun Ọba ti ọla Rẹ ga sọ pe: Ẹ̀yin tí ẹ gbàgbọ́ ní òdodo, dájúdájú ọtí, tẹ́tẹ́, àwọn òrìṣà àti iṣẹ́ yíyẹ̀wò, ẹ̀gbin nínú iṣẹ́ Èṣù ni. Nítorí náà, ẹ jìnnà sí i nítorí kí ẹ lè jèrè. Ohun tí Èṣù ń fẹ́ ni pé ó máa dá ọ̀tá àti ìkórira sílẹ̀ láàarin yín níbi ọtí àti tẹ́tẹ́. Ó sì fẹ́ ṣẹ yín lórí kúrò níbi ìrántí Allāhu àti níbi ìrun kíkí. Ṣé ẹ̀yin kò níí jáwọ́ (níbi iṣẹ́ Èṣù) ni? Al-Maa'ida 90-91

## Ẹlẹẹkẹsan-an: Jijẹ okunbete, ẹjẹ, ati ẹran ẹlẹdẹ:

Ati gbogbo awọn nǹkan ẹgbin ti o le fi inira kan eeyan, bakan naa ni awọn nnkan ti wọn dú lati fi sunmọ nnkan miiran ti o yatọ si Ọlọhun ti O ga julọ. Ọlọhun ti ọla Rẹ ga julọ sọ pe: Ẹ̀yin tí ẹ gbàgbọ́ ní òdodo, ẹ jẹ nínú àwọn ǹǹkan dáadáa tí A pèsè fun yín, kí ẹ sì dúpẹ́ fún Allāhu tí ó bá jẹ́ pé Òun nìkan ṣoṣo ni ẹ̀ ń jọ́sìn fún. Ohun tí (Allāhu) ṣe ní èèwọ̀ fun yín ni òkúǹbete, ẹ̀jẹ̀, ẹran ẹlẹ́dẹ̀ àti ohun tí wọ́n pe orúkọ mìíràn

---

[21] Hadiisi yii, Imaam Muslim gbe e jade ninu Kitaabul-Eeeman, ojupọnna "Ọrọ Anabi (Ẹniti o ba rẹ wa jẹ, kii ṣe ara wa)" (2/109)

lé lórí yàtọ̀ sí (orúkọ) Allāhu. Ṣùgbọ́n ẹni tí wọ́n bá fi ìnira (ebi) kan, yàtọ̀ sí ẹni t'ó ń wá èèwọ̀ kiri àti olùtayọ-ẹnu-àlà, kò sí ẹ̀ṣẹ̀ fún un. Dájúdájú Allāhu ni Aláforíjìn, Àṣàkẹ́-ọ̀run. [Al-Baqorah: 172, 173]

## Ẹlẹ́ẹ̀kẹwaa: Sisunmọ agbere ati iwa ijọ Lût:

Agbere ṣiṣe jẹ iṣẹ ẹlẹgbin, ti o si maa n ba iwa eeyan ati awujọ jẹ, o si tun maa n fa didapọ ẹbi, ati rirare mọlebi, ati ṣiṣe afẹku itọju ti o dara. Awọn ọmọ agbere maa mọ kikoro ọran naa lara ati ikorira ẹni lawujọ. Ọlọhun ti ọla Rẹ ga sọ pe: Ẹ má ṣe súnmọ́ àgbèrè. Dájúdájú ó jẹ́ ìwà burúkú. Ó sì burú ní ojú ọ̀nà. [Al-Israa'i: 32]

Oun si ni okunfa fifọnka aisan ibalopọ ti o maa n pa awujọ run. Ojiṣẹ Ọlọhun (ki ikẹ ati ọla Ọlọhun maa ba a) sọ pe: Agbere ko nii fọnka laarin ijọ kan titi ti wọn yoo fi maa ṣe e ni gbangba, ayafi ki ajakalẹ arun o fọnka laarin wọn ati awọn aisan ti ko tii sẹlẹ si awọn ti wọn ṣaaju wọn ri.

Torí náà ni Islām ṣe pàṣẹ didi gbogbo ọ̀nà ti o já síbẹ̀, o wa pa Mùsùlùmí láṣẹ pẹlu rirẹ-oju wọn nilẹtorí pé wiwo nǹkan eewọ naa ni ibẹrẹ ojú ọna lọ sí àgbèrè, o si pa obìnrin láṣẹ lati bo ara àti ojú ati jijẹ ẹni mimọ, titi ti wọn fi maa ṣọ àwùjọ kúrò nibi agbere. Ni idakeji ẹ̀wẹ̀, o pàṣẹ ṣíṣe ìgbéyàwó, o si ṣe ni lojukokoro lórí rẹ, kódà o ṣe àdéhùn laada ati ẹsan lórí adùn ibalopọ láàrin lọkọ-laya, ki mọlẹbi alapọn-ọnle ti o mọ le jáde latara rẹ, ti yoo kúnjú ìwọ̀n láti jẹ ààyè ẹkọ fun ìkókó òní ti yoo di ọkùnrin ni ọla.

## Ẹlẹ́ẹ̀kọkanla: Jijẹ owo-ele:

Ele maa n ko iparun ba isuna ni, o si tun jẹ ilo-anfaani bùkátà ẹni ti o n bùkátà si owó, boya o jẹ sowosowo ni ninu òwò rẹ, tabi ki o jẹ talika fún bùkátà rẹ. Oun naa ni yiyani lowo di asiko kan pàtó pẹ̀lú alekun kan pàtó nígbà ti wọn ba fe da owó naa pada. Ẹni ti n gba owó èlé maa n lo àǹfààní bùkátà talika si owó, yoo wa di ẹrù awọni-lọ́rùn gbèsè ti yoo maa sarajọ ti yoo si le si owó idokowo rù ú

Ẹniti o n ya eeyan ni owo ele yoo lo anfaani bukata oluṣowo, tabi òṣìṣẹ́, tabi agbẹ ati awọn ẹniti o yatọ si wọn ninu awọn ti wọn o jẹ ki isuna o dúró sójú kan.

Yoo lo anfaani bukata wọn ti o pàtàkì si owó, yoo waa ṣe ni ọranyan le wọn lórí ipin kan ti o le ninu èrè nibi nǹkan ti o ya wọn, lai nii ba wọn pin ninu ewu àìjèrè.

Ti sowosowo yii ko ba wa jèrè, gbèsè maa wọ ọ lọrun, olówó-èlé yii maa waa pa á run, ti o ba si jẹ pe wọn jọ da owo papọ ni nibi èrè ati òfò, èyí pẹ̀lú wàhálà rẹ, èyí pẹ̀lú owó rẹ, gẹgẹ bi Islām ṣe pa wa láṣẹ, isuna i ba maa tẹsiwaju ni ọ̀nà ti o gba maa jẹ anfaani fun gbogbo èèyàn.

Ọlọhun Ọba ti ọla Rẹ ga sọ pe: Ẹ̀yin tí ẹ gbàgbọ́ ní òdodo, ẹ bẹ̀rù Allāhu, kí ẹ sì fi ohun t'ó ṣẹ́kù nínú èlé sílẹ̀, tí ẹ bá jẹ́ onígbàgbọ́ òdodo. Tí ẹ ò bá ṣe bẹ́ẹ̀, ẹ lọ mọ̀ pé ogun kan láti ọ̀dọ̀ Allāhu àti Òjíṣẹ́ Rẹ̀ (ń bọ̀ wá ba yín). Tí ẹ bá sì ronú pìwàdà, tiyín ni ojú-owó yín. Ẹ ò níí ṣàbòsí (sí wọn). Wọn kò sì níí ṣàbòsí si yín. Tí (onígbèsè) bá jẹ́ ẹni tí ara ń ni, ẹ wò ó níran di àsìkò ìdẹ̀ra. Àti pé kí ẹ fi ṣe sàráà (fún un) lóore jùlọ fun yín, tí ẹ bá mọ̀. [Al-Baqorah: 278, 279, 280]

## Ẹlẹ́ẹ̀kejila: Ṣíṣe ahun

Itọka ni o jẹ si imọtara-ẹni-nikan, ahun yii ma maa ko owó jọ, ko si nii yọ Zakat rẹ fun àwọn talika ati awọn mẹkunnu, lẹniti o ti kọ àwùjọ rẹ silẹ, ati ipilẹ iran-ara-ẹni-lọwọ ati ijẹ ọmọ-iya ti Ọlọhun ati ojiṣẹ Rẹ pàṣẹ rẹ. Ọlọhun ti ọla Rẹ ga sọ pe: Kí àwọn t'ó ń ṣahun pẹ̀lú ohun tí Allāhu fún wọn nínú oore-àjùlọ Rẹ̀ má ṣe lérò pé oore ni fún wọn. Rárá, aburú ni fún wọn. A ó fí ohun tí wọ́n fi ṣahun dì wọ́n lọ́rùn ní Ọjọ́ Àjíǹde. Ti Allāhu sì ni ogún àwọn sánmọ̀ àti ilẹ̀. Allāhu sì ni Alámọ̀tán nípa ohun tí ẹ̀ ń ṣe nísẹ̀. Aal-Imraan: 180

## Ẹlẹ́ẹ̀kẹtala: Irọ̀ àti jijẹrii èké

Ati sọ síwájú ọrọ Anọbi (ki ikẹ ati ọla Ọlọhun máa bá a) pé: (Dajudaju irọpipa a máa ti ni lọ sí ibi iwa burúkú, dajudaju ìwà burúkú a sì máa ti ni lọ sí inú iná ni, ọmọnìyàn ko wáá níí yẹ kò sì níí gbò lẹnití yóò máa parọ tí yóò sì tún máa ṣe àwárí irọ títí ti wọn yóò fi kọ sílẹ̀ lọdọ Ọlọhun pé òpùrọ́ gbáà ni)

Nínú àwọn ìran irọ tí a kórira ni èyítí ó bá jẹ ijẹrii èké, ojiṣẹ Ọlọhun- ki ikẹ ati ọla Ọlọhun máa bá a- sì ti dé ògóńgó níbi lílénijìnnà tefétefé kúrò níbi mímáa jẹrii èké, o si kilọ nipa àtúbọ̀tán rẹ, o gbe ohun rẹ sókè lẹniti n sọ fún àwọn saabe rẹ pe: Ẹ tẹti ẹ jẹ ki n fun yin ni iro nipa eyi ti o tobi ju nínú àwọn ẹṣẹ ńlá: Mímú orogun pẹ̀lú Ọlọhun, ati ṣiṣẹ obi méjèèjì, o rọgbọku tẹlẹ ni, ni o ba jókòó, o wa sọ pe: Ẹ tẹti ẹ gbọ, ati ọrọ iró, ẹ tẹti ẹ gbọ, ati ijẹrii èké) [22] Anọbi ko yẹ kò gbò lẹnití ń pààrà rẹ lati jẹ ikilọ fún àwọn ìjọ mùsùlùmí láti má le kó sínú rẹ.

## Ẹlẹ́ẹ̀kẹrinla: Igbéraga, àti ẹtanjẹ, àti motómotó:"

Ìgbéraga àti ẹtanjẹ jẹ ìròyìn burúkú ti a korira ninu ẹsin Isilaamu, Ọlọhun si ti sọ fun wa pe Oun ko nífẹ̀ẹ́ àwọn onigbeeraga, O sọ nípa wọn ni ile ìkẹyìn pe Ṣe inu ina Jahnamọ kọ ni ibugbe fun awọn onigbeeraga ni? [Suuratu- Zumar : 60] Onigbeeraga, janujanu, onimotómotó ènìyàn jẹ ẹni ìkóriira lọdọ Ọlọrun àti lọdọ àwọn ẹda Rẹ"

[22] Bukhari ni o gbe Hadiisi naa jade: Tira "Àwọn ijẹrii", ojupọnna "Nǹkan ti wọn sọ nípa ijẹrii èké" (3/225)

## 3- Títúúbá níbi àwọn ohun tí a ṣe ní èèwọ̀

Àwọn ẹṣẹ ńlá ati awọn nǹkan eewọ ti a dárúkọ yii, o di dandan fun musulumi lati ṣọ́ra ki o ma baa ko sinu rẹ, gbogbo iṣẹ ti ọmọniyan ba n ṣe pata ni wọn maa san an lẹsan lori rẹ ni ọjọ́ igbende alukiyaamọ, ti o ba ṣe rere, o maa gba ẹsan rere, ti o ba si jẹ aburu, o maa gba ẹsan aburu.
Ti Mùsùlùmí ba wa ko sinu nǹkan kan ninu awọn nǹkan ti a ṣe ni eewọ yii, ki o yaa tete tuuba kuro nibẹ, ki o si sádi Ọlọhun, ki o si wa aforijin Rẹ, ti tuuba rẹ ba dé ọkàn, o di dandan ki o jawọ kúrò nibi ẹṣẹ ti o ko si, ki o si kabamọ lori nǹkan ti o ṣe, ki o si pinnu pe oun ko nii pada sibẹ mọ, ti o ba gba nǹkan lọ́wọ́ ẹnikan pẹ̀lú abosi, ki o yaa da a pada fun un, tabi ki o wa amojukuro rẹ, igba yẹn ni tuuba rẹ maa jẹ òdodo, Ọlọhun si maa gba tuuba rẹ, ko si nii fi iya jẹ ẹ lori ẹ, ẹni tí ó bá tuuba kuro nínú ẹṣẹ da gẹgẹ bii ẹni ti ko ni ẹṣẹ ni.
O wáá jẹ dandan fún un lati tọrọ àforíjìn lọwọ Ọlọrun lọpọlọpọ, ọ si jẹ dandan fún gbogbo musulumi láti máa pọ ni ìtọrọ aforijin níbi àwọn ẹṣẹ kéékèèké tàbí ńlańlá ti o ba n da, Ọlọhun ti ọla Rẹ ga sọ pe: ẹ tọrọ àforíjìn ní ọ̀dọ̀ Olúwa yín, dájúdájú Ó ń jẹ́ Aláforíjìn. [Nuuh : 10]" Pipọ ní títọrọ àforíjìn ati ìrònúpìwàdà jẹ ìròyìn àwọn mumini olùfọkànbalẹ̀ sọ́dọ̀ Allāhu, Ọlọhun ti ọla Rẹ ga sọ pe: Sọ pé: "Ẹ̀yin ẹrúsìn Mi, tí ẹ ti dẹ́ṣẹ̀ púpọ̀ sí ẹ̀mí ara yín lọ́rùn, ẹ má ṣe sọ̀rètí nù nípa ìkẹ́ Allāhu. Dájúdájú Allāhu l'Ó ń ṣàforíjìn gbogbo ẹ̀ṣẹ̀ pátápátá. Dájúdájú Allāhu, Òun ni Aláforíjìn, Àṣàkẹ́-ọ̀run. Ẹ ṣẹ́rí padà (ní ti ìronúpìwàdà) sí ọ̀dọ̀ Olúwa yín. Kí ẹ sì juwọ́-jusẹ̀ sílẹ̀ fún Un ṣíwájú kí ìyà náà t'ó wá ba yín. (Bí bẹ́ẹ̀ kọ́) lẹ́yìn náà, A ò níí ràn yín lọ́wọ́. [Az-Zumar:53,54]

## 4- Àkólékàn awọn mùsùlùmí pẹlu lilalaafia titan ẹsin yii ká"

Nigba ti àwọn ọ̀rọ̀ ojiṣẹ Ọlọhun- ki ikẹ ati ọla Ọlọhun máa bá a- ati iṣe rẹ ati ifaramọ rẹ jẹ nǹkan ti n ṣàlàyé ọ̀rọ̀ Ọlọhun ti ọla Rẹ ga, ti o n túmọ̀ àwọn àṣẹ àti àwọn nǹkan ti wọn kọ nínú ẹsin Isilaamu, eyi ni o mu ki awọn musulumi ni akolekan nla si ìní àlàáfíà títàn ká àwọn Hadiisi ti wọn gba wa lati ọdọ ojiṣẹ Ọlọhun- ki ikẹ ati ọla Ọlọhun máa bá a- wọn si gbìyànjú gan láti ṣe afọmọ àwọn ẹ̀gbàwá yii kúrò nibi awọn alekun ti ko si nínú ọ̀rọ̀ ojiṣẹ Ọlọhun- ki ikẹ ati ọla Ọlọhun máa bá a- ati nibi ṣíṣe àlàyé àwọn ọ̀rọ̀ ti wọn parọ rẹ mọ ọn- ki ikẹ ati ọla Ọlọhun máa bá a-, wọn wa gbe àwọn ìlànà ati ètò ti o péye julọ kalẹ fun ìyẹn, èyí tí o di dandan lati woye si i nibi titan àwọn Hadiisi yii ka lati ìran de ìran.
A maa sọrọ ni ṣókí nipa imọ yii (imọ Hadiisi), titi ti yoo fi han si olùkà, àlámọ̀rí yẹn ti ìjọ Islām fi da yàtọ̀ si awọn ẹsin to ṣẹku nibi nǹkan ti Ọlọhun ṣe ni irọrun fun un, bii didaabo bo ẹsin rẹ ni nǹkan ti o wa ni mimọ ti irọ ati ìgbàgbọ́ nínú ohun asán ko ropọ mọ ọn lati ìgbà dé gbà.
"Ẹgbàwá ọrọ Ọlọrun àti ojiṣẹ Rẹ- ki ikẹ ati ọla Ọlọhun máa bá a- ti gbarale awọn àlámọ̀rí pàtàkì méjì kan, àwọn méjèèjì ni:
Hiha sínú igbaaya ati kikọ silẹ, àwọn Mùsùlùmí àkọ́kọ́ wa ninu awọn ijọ ti wọn ni ikapa lori hiha nǹkan jù, ati agbọye ti o fẹ; tori pe wọn da yàtọ̀ pẹ̀lú làákàyè ti o mọ, ati ìrántí ti o lágbára, nǹkan ti a mọ ti o han ni eléyìí si ẹni ti o ba ka nipa itan wọn, ti o si mọ ìròyìn wọn, saabe kan a maa gbọ́ Hadiisi lẹ́nu ojiṣẹ Ọlọhun- ki ikẹ ati ọla Ọlọhun máa bá a- yoo si ha a dáadáa, òun naa yoo gbe e lọ fun taabihiy ti oun naa maa ha a, lẹ́yìn naa oun naa maa sọ ọ fun ẹni tí o wa lẹ́yìn oun naa, bayii ni isnaad Hadiisi ṣe maa tẹsiwaju de ọdọ ọkan ninu awọn olumọ nipa Hadiisi ti o maa n kọ àwọn Hadiisi yii, yoo waa ha a sori, yoo tun ko o jọ sínú tira kan, yoo wa ka tira yii fun àwọn ọmọ akẹ́kọ̀ọ́ rẹ, àwọn naa maa ha àwọn Hadiisi yii, wọn si maa kọ ọ, lẹ́yìn naa wọn maa ka a fun àwọn akẹ́kọ̀ọ́ wọn, bayii ni o ṣe ma maa to tẹle ara wọn titi ti àwọn tira yii fi maa de ọdọ gbogbo àwọn iran ti wọn ba n wa lẹyin pẹ̀lú ọ̀nà yii.
Nitori ìdí èyí, wọn kò níí gba Àdíísìi kankan láti ọdọ ojisẹ ọlọhun ki ikẹ ati ọla ọlọhun lọ máa ba láì mọ àfitì rẹ láti ọdọ àwọn olùgbà ẹgbàwá tósepé wón sí Àdíísìi yìí nípò wáá báwa"
Ìmọmíràn náà sì tún tẹlé àlámọ̀rí yi, eyitosewipe àwọn ìjọ mùsùlùmí fi tayọ awọn ìjọ míràn, ohun náà ni ìmọ nípa isesi awon olùgbà ẹ̀gbàwá Àdíísìi ati iroyin wọn"..''
Òhun sìni ìmọ tí o ni àkólékàn pẹlu mímọ ìsesí àwọn olùgbà wá tí wọn ń gba àwọn Àdíísìi òjíṣẹ ọlọrun kí ìkẹ àti ọlà ọlọrun lọ máa ba. Ìmọ yìí wáá ni àkólékàn nipa mímọ pàápàá itan wọn, pẹlu ìtàn bíbí àti ikú wọn pẹlu mímọ awọn olukọ ati awọn akékòó wọn àti igbekele awọn onimimo ayé òde òni fún àwọn àti òpin díde nǹkan mọlẹ wọn àti níní amọdaju lori wọn níbi nnkan híhá, àti àwọn ohun tí wọn fi gba ẹsá gege bi afọkantan ati ije ijẹ olódodo ati awọn awọn nnkan míràn nínú àwọn nnkan ti Onimo adisi ni bùkáátà sí mímọ wọn lati le mo amọdaju níbi ilalafia Àdíísìì tí ó bá gbà wá láti ipasẹ awọn ikọ olùgbàwá wọn yi."
Dájúdájú ó jẹ ìmọ tí àwọn ìjọ ìsìláàmù fi dáwà láti máa fi se ojúkòkòrò níbè lori ilalaafia ọrọ ti a ba se àfitì rẹ lọ sí ọdọ anọbi rẹ, a kò sì rí nínú gbogbo itan patapata lati ijọ ti alaye ti dáyé wipe ìgbìyànjú nla kànkà yìí wá láti ibi níní àkólékàn pẹlu ọrọ ìkan ninu àwọn ọmọnìyàn gẹgẹ bi won se ni àkólékàn pelu ọrọ òjíṣẹ ọlọrun kí ìkẹ àti ọlà ọlọrun lọ máa báa"
Dajudaju o jẹ ìmọ kan tí ó fẹ púpọ tí a kójọ sínu awọn Tírà kan ti o ni àkólékàn tó pé pẹlu ẹgbàwá Àdíísìi, àwọn pàápàá ìtàn ti a fọsíwẹwẹ fún àwọn ẹgbẹgbẹrún olùgbàwá Àdíísìì tí dárúkọ wípé wón jẹ alágàta níbi

sísí adiisi nípò lati ọdọ ojisẹ ọlọhun ki ikẹ ati ọla ọlọhun lọ máa ba lọsí awọn ìran ti o tẹlé wọn, kòsìsí ìpán ọrọ fún ẹnikẹni níbi ìmọ yìí bíkòsepé ó dà gégébí oṣuwọn níbi àrídájú àtakò tiwọn máa n sọ nípa òpùrọ ènìyàn wipe òpùrọ ni, àti olódodo wipe olododo ni, àti fún ẹnití làákàyè rẹ lẹ ,àti fún ẹnití làákàyè rẹ múnná dóko wipe gẹgẹ bẹẹ ni o se ri, wọn si se agbekalẹ awọn òpó tí ó ṣe pé àwọn tí wọn wá ní ojú ònà yìí náà damo."

Àdíísìì kòsì leè jẹ nnkan ti óní àlàáfíà lọdọ wọn àyàfi ìgbàtí apákan ninu awọn sísẹntẹlé olùgbàwá Àdíísìì bá sopọ mọ apámìrán-àn, ti isedeede ati isododo pẹlu ìmúnádóko làákàyè and ìdeǹkanmálẹ sì ń wáyé láàrin àwọn olùgbàwá Àdíísìì náà."

## "Àlámàrí mìíràn ninu ìmọ Àdíísìì"

Òhun ni níbi púpọ àwọn òníran-ìran sísẹntẹlé ìsàfiti fún Àdíísìì ẹyọkan soso, lọnà tí adiisi ti a gbàwá lọdọ anọbi ní ojúpọnnà púpọ ninu àwọn sísẹntẹlé awọn olùgbà ẹ̀gbàwá adiisi yóò fi dé, ìsàfitì meji yóò wáá máa bẹ fún adiisi ẹyọkan, tabi ìsàfitì mẹta tabi mẹrin, nigbamiran o si le jẹ mẹwa, ó sì tún lè pọjùyẹnlọ nigbamiran

Gbogbo ìgbà tí sísẹntẹlé ìsàfiti adiisi ba ti n pọsíi ni adiisi yóò máa lágbára síi ti igbarale yóò sì máa lékún sìi níbi ṣiṣe àfitì rẹ lọsí ọdọ ojisẹ ọlọhun ki ikẹ ati ọla ọlọhun lọ máa ba. Àdíísìì ti ẹnití o pọ ju mẹwa ninu awọn olugbarale ba gbàwá ninu gbogbo awon ìpele rẹ ni a n pé ni Mùtàwáátír, ohun sì ni èyí tí o ga jùlọ nínú àwọn ìran ohun tí a sínípò lọdọ awon mùsùlùmí, gbogbo ìgbà tí àlámọrí ìdájọ bá tin jẹ gbogboogbo ninu ẹṣin ìsìláàmù gẹgẹbi alaye nipa awọn orígun ìsìláàmù lápẹẹrẹ, àwọn ẹgbàwá ọrọ ti o wá fun-un yóò pọ síi, àwọn ìsàfiti ẹgbàwá ọrọ yóò síi pẹka fún un , gbogbo ìgbà tí ìdájọ àlámọrí náà bá sì ti n wa ninu awọn akẹtún ati awọn nnkan ti a fẹ, awọn ìsàfiti ẹgbàwá ọrọ fún-un yóò kéré síi, ìní àkólékàn pẹlu rẹ yóò sì máa lẹ síi."

Àkólékàn to gajulo pẹlu ẹgbàwá ọrọ ti àwọn mùsùlùmí kóo lekan níbi ìsínípòpadà ni titi kuraani lọnà tósepé o se alabapade àkólékàn to gajulo níbi nnkan kíkọ ati híhá sí óókan- an àyà, ati mímọ amọdaju fún àwọn ọrọ rẹ àti ibùjáde awọn áràfí i rẹ ati ojúpònà kikaa rẹ, ẹgbẹẹgbẹrún ni ó wáá gbàá wá pẹlu ìsàfiti olùgbàwá nipasẹ awọn ìran díran tí ń to tẹleraawon, nitori ìdí èyí ni ìtọwọbọ tabi ọwọ àyípadà ko fi leè wọlé tọọ fún àìmọye mọye ọdún, alukurani ni wọn ń ké ní ibùwọ oòrùn náà ni èyí tí wọn n ké ní ibùyọ oorun, òhun náà sì ni èyí tí wọn n ké ní gbogbo awọn oríṣìíríṣìí àáyè lórílẹ, lati fi jẹ irinṣẹ ìgbàgbọ sí ọrọ ọlọhun ọba àleké ọlá to sọpé : Dájúdájú Àwa l'A sọ Tírà Ìrántí kalẹ̀ (ìyẹn al-Ḳur'ān). Dájúdájú Àwa sì ni Olùṣọ́ rẹ̀. Al-Hijr 9

# "Lẹyìn náà :"

Eleyi ni ẹṣin ìsìláàmù eyitosepe óún kéde ìmú ọlọhun ọba àleké ọlá ni ọkan soso níbi ìjọlọhun rẹ, àmì ìdámò rẹ ni (kosi eniti ìjọsìn òdodo tósì, àyàfi ọlọhun), eleyi ni ẹṣin ìsìláàmù eyitosepe ọlọhun ọba yọnu síi fún àwọn ẹrúsìn rẹ láti máa jẹ ẹṣin."

Mo parí ẹ̀sìn yín fun yín lónìí. Mo sì ṣe àṣepé ìdẹ̀ra Mi fun yín. Mo sì yọ́nú sí 'Islām ní ẹ̀sìn fun yín. (Al'Maa'idah 3)

Eleyii ni ẹṣin ìsìláàmù tosewipe ọlọhun konii tẹwọgba ẹṣin míràn tó yàtọ síi lọwọọ ẹnikẹni" Ẹnikẹ́ni tí ó bá wá ẹ̀sìn kan ṣe yàtọ̀ sí 'Islām, A ò níí gbà á lọ́wọ́ rẹ̀. Ní Ọjọ́ Ìkẹ́yìn, ó sì máa wà nínú àwọn ẹni òfò. Aal-Imraan 85

"Eleyi ni ẹṣin ìsìláàmù tosewipe ẹnití o bá n'igbagbọ pẹlu rẹ, to sì se dáadáa, yóò máa bẹ ninu awọn olujere ninu ọba alujanna onídẹra". Dájúdájú àwọn t'ó gbàgbọ́ ní òdodo, tí wọ́n sì ṣe àwọn iṣẹ́ rere, àwọn ọgbà Firdaos ti wà fún wọn ní ibùdésí. Olùṣegbére ni wọ́n nínú rẹ̀. Wọn kò sì níí fẹ́ kúrò nínú rẹ̀. [Suurat kahf : 107,108]."

Eleyi ni ẹṣin ìsìláàmù, kìí ṣe ẹṣin àdáníkànse fún àwọn ìjọ kan ninu awọn ọmọnìyàn, bẹẹ sì ni kii se ohun tí a dá sàlẹsà pẹlu awọn ìran kan pàtó nínú àwọn èlẹran ara, bíkòsepé enitóbá n'igbagbọ pẹlu rẹ, tósì tún pepe sibẹ, yóò máa jẹ ẹnití o lẹtọọ si jù, yóò sì máa jẹ ẹnití óní àpónlé julọ lọdọ ọlọhun ọba àleké ọlá :" Dájúdájú alápọ̀n-ọ́nlé jùlọ nínú yín lọ́dọ̀ Allāhu ni ẹni t'ó bẹ̀rù (Rẹ̀) jùlọ. Suuratul Hujirōt: 13.

O wáá jẹ dandan fún wa láti ta olùkà alaponle jí lori awọn àlámọrí to pandandan ti máa ń bẹ sílẹ láàrin àwọn ọmọnìyàn àti ẹṣin ìsìláàmù yìí, tí ó sì máa ń kọdíi wọn láti mále wọ ibè:"

Àkọkọ : Síse aimọkan pẹlu esin ìsìláàmù nititi adisọkan ati ofin ati awọn ẹkọ -awon ọmọnìyàn sì máa n je ọta fún ohun tí wọn bá saimọkan nipaa rẹ- Nítorí ìdí èyí,o jẹ dandan fún ẹnití o bá ni àkólékàn pẹlu mímọ ẹṣìn ìsìláàmù lati kàà ní àkàtúnkà tìtítí yóò fi ni ìdámò sí ẹṣin yii láti ibi awọn ibùsẹwá rẹ ti ìpìlẹ, kí kíkà sì jẹ pẹlu èmi tó mọkangá to jẹ ti déédéé ti yóò máa wá otitọ fún gbogbo aisedeede."

"Eleekeji: síse ẹlẹyamẹya fún ẹṣin ati awọn isesi ati awọn ọlaju tósepé olukuluku a máa dá sílẹ lài ronú jù àti làákàyè níbi lilalaafia ẹṣin tosewipe òhun ni o dàgbà lèé lórí, ẹlẹyamẹya titi ìjọ náà a sì máa lọọ níbẹ, ni gbogbo ẹṣin bá kọ ẹṣin míràn yàtọ sí ẹṣin awọn bàbá rẹ àti àwọn baba ńlá rẹẹ, Síse ẹyàmẹyà a máa kun ojú méjèèjì ní oorun, a sì tún máa di awọn etí, o sì tún máa ń kọdí awọn làákàyè, Nitori ìdí èyí,

ọmọnìyàn ko gbọdọ máa ronú nípa òmìnira ati àìní àfojúfòru , kòsí tún gbọdọ̀ máa ṣe ipinya laarin òkùnkùn àti imọlẹ ."

Ẹlẹẹkẹta" : ìfẹ́ ẹ̀mí àti àwọn ojúkòkòrò rẹ̀ ati àwọn adùn rẹ̀ , nitoripe dájúdájú ifẹ inú a máa mú ìròrí ati èròngbà rin lọ sí ààyè tó bá wùú, o sì máa n darí ọmọnìyàn lati ààyè ti ko lérò, o sì máa n kọdíi rẹ̀ pẹlu agbara kúrò níbi gbigba òdodo àti ijupajusẹ sílẹ̀ fún un."

Ẹlẹẹkẹrin : Rírí apákan ninu àwọn àṣìṣe àti àwọn àyípadà lọdọ apakan ninu awọn mùsùlùmí ati ìsàfiti èké àti irọ́ sí ibi ẹṣin ìsìláàmù, ìsìláàmù sì má kangá kuro níbẹ̀ , kí gbogbo ọmọnìyàn yaa mọ̀pé Dájúdájú ẹṣin ọlọhun kìí ṣe ohun tí à ń béèrè nipa àwọn àṣìṣe ẹlẹ́ran ara."

Dájúdájú ojú ònà tí ó rọrùn jù fún mímọ òdodo àti ọ̀náámà ni kí ọmọnìyàn dojukọ ọlọhun pẹlu ọkàn rẹ̀ lẹ́nití yóò gbára lée lẹ́nití yóò máa tijú rẹ̀, yóò máa fara gbolẹ̀ lọsí ọdọ rẹ, yóò máa tọrọ lọwọ rẹ wipe kí o fi ọ̀nà mọ̀ó lọsí ojú ọ̀nà tó dúró ṣinṣin àti ẹṣin tó tọ́ eyitosewipe ọlọhun ọba ni ìfẹ sí, ti o sì yọnusi pẹlu, kí ọwọ́ ẹrusin ọlọhun sì tẹ irọrun ati oríire láíláí eyitosewipe konii konii soriibu mọ́ lẹ́yìn in rẹ̀, kí ó sì le baà mọ̀ wipe Dájúdájú ọlọhun a máa tẹwọgba ipepe olupepe nígbàtí ó bá ké pèé, ọlọhun ọba àleké ọlá sọ báyìí pé :" Nígbà tí àwọn ẹrúsìn Mi bá bi ọ léèrè nípa Mi, dájúdájú Èmi ni Olùsúnmọ́. Èmi yóò jẹ́pè àdúà aládùúà nígbà tí ó bá pè Mí. Kí wọ́n jẹ́'pè Mi (nípa ìtẹ̀lé àṣẹ Mi). Kí wọ́n sì gbà Mí gbọ́ nítorí kí wọ́n lè mọ̀nà (gbígbà àdúà). [Al-Baqara:186]

"Ó parí pẹ̀lú oníran ìran ọpẹ́ lọ́wọ́ ọlọhun ọba".

" Ẹ̀sìn Ìsìláàmù
Ọrọ iṣaaju
Olùkàwé mi ọ̀wọ́n:
1- "Gbolohun imọ Allaahu ni ọ̀kan (laa ilaaha illa Allahu )"
B- Kilode tí Ọlọhun fi dá wa?
2- Muhammad ojiṣẹ Ọlọhun n:
A- Kini ìtumọ̀ ojiṣẹ? Tani Muhammad? Ǹjẹ́ àwọn ojiṣẹ míràn wa yàtọ̀ si i?
B- Àkọ́kọ́ àwọn ojiṣẹ ni bàbá wa Adam (ki ọlà maa ba a)
"3. Nuuh- ki alaafia maa ba a-:"
"4- Ojiṣẹ Allahu Hud (ki alaafia maa ba a)"
"5. Ojiṣẹ Allāhu to n jẹ Soolih, ki alaafia maa ba a"
Ojiṣẹ tii ṣe Ibraahim (Ki alaafia Ọlọhun maa ba a)
Ojiṣẹ Ọlọhun Lût (Ki alaafia Ọlọhun maa ba a)
Ojiṣẹ ti ń ṣe Shuaib (Ki alaafia Ọlọhun maa ba a) a
"Ojiṣẹ Allahu, Musa (ki alaafia maa ba a).
"Ojiṣẹ Allahu, Isa (ki alaafia maa ba a)."
3- Muhammad ojiṣẹ Allahu (ìgbẹ̀yìn àwọn Anọbi ati awọn Ojiṣẹ)
"1- Iran rẹ ati iyi rẹ "
"2- Awọn iroyin rẹ"
"3- Kuraishi ati awọn larubawa".
"4- Igbedide Anọbi Muhammad (ki ikẹ ati ọla Ọlọhun máa bá a)
Kikun Anabi (ki ikẹ ati ọla Ọlọhun maa ba a) lọ́wọ́ pẹlu àwọn iṣẹ́ iyanu
Awọn saabe alapọn-ọnle:
4- Awọn origun Isilaamu.
1- Origun akọkọ: Jijẹrii pe ko si ọlọhun kankan ti ijọsin ododo tọ si ayafi Ọlọhun Ọba Allaah, ati pe dajudaju Muhammad Ojiṣẹ Ọlọhun ni.
2- Origun keji: Gbigbe irun duro
3- Origun kẹta: Zakaat
"4- Origun kẹrin: Aawẹ Ramadan"
"5- Origun karùn-ún: ṣíṣe hajj lọ si ile ọwọ (ka'ba)"
"5- Awọn origun igbagbọ "
6- "Awọn ẹkọ Isilaamu ati awọn iwa rẹ"
" 1- Awọn nkan ti wọn pa wa laṣẹ lati ṣe"
" Akọkọ: Ọrọ òdodo
Ẹlẹẹkeji: Dida awọn nnkan afipamọ-sini-lọwọ pada, ati pipe awọn adehun, ati ṣiṣe deedee laarin awọn eeyan.
Ẹẹkẹta: Mimaa tẹriba ati aiṣe igberaga:
Ẹlẹẹkẹrin: Ọrẹ-tita ati mimaa nawo si awọn oju ọna rere:
Ẹlẹẹkarun: Mimaa ṣe suuru ati nini ifarada lori ṣuta:
Ẹlẹẹkẹfa: Ìtìjú
"Ẹlẹẹkeje: Ṣíṣe dáadáa sí àwọn òbí méjèèjì"
"Ẹlẹẹkẹjọ: Wíwu ìwà dáadáa sí àwọn ẹlòmíràn:"
Ẹléẹ̀kẹsàn-án: Ìgbìyànjú sí ojú ònà Ọlọhun fún ríran ẹnití wọ́n ṣe àbòsí rẹ̀ lọ́wọ́, àti fífi òdodo rinlẹ, àti fífọ́n déédéé ká"
"Ẹlẹẹkẹwaa: Adua ati iranti ati kika Alukuraani:"
"Ẹlẹẹkọkanla": Kikọ ẹkọ imọ ti shariah, ati fifi mọ awọn eniyan, ati pipepe lọ sibẹ:
Ẹlẹẹkejila: Iyọnu si idajọ Allahu ati Ojiṣẹ Rẹ:
"2- Awọn nnkan eewọ ati awọn nǹkan ti a kọ̀"
“Akọkọ: Ẹbọ: (yiyi eyikeyi ninu iran ijẹ ẹrusin fun ẹlòmíràn ti o yatọ si Allahu ti ọla Rẹ ga):
Ẹlẹẹkeji: Idan, yiyẹ iṣẹ wo, ati pipe apemọra imọ kọkọ.
Ẹlẹẹkẹta: Abosi
Ẹlẹẹkẹrin: Pipa ẹmi ti Ọlọhun ṣe ni eewọ ayaafi pẹlu ẹtọ.
Ẹlẹẹkarun: Itayọ ààlà lori awọn eeyan nibi dukiya wọn.
Ẹlẹẹkẹfa: Irẹjẹ ati itanjẹ ati ijamba.
Ẹlẹẹkeje: Títayọ ààlà lórí àwọn ènìyàn.
Ẹlẹẹkẹjọ: Mimaa ta tẹtẹ, ati ọti mimu, ati mimaa lo oogun oloro:
Ẹlẹẹkẹsan-an: Jijẹ okunbete, ẹjẹ, ati ẹran ẹlẹdẹ:

Ẹlẹ̀ẹ̀kẹ̀waa: Sisunmọ agbere ati iwa ijọ Lût:
Ẹlẹ̀ẹ̀kọkanla: Jijẹ owo-ele:
Ẹlẹ̀ẹ̀kejila: Ṣíṣe ahun
Ẹlẹ̀ẹ̀kẹtala: Irọ àti jijẹrii èké
Ẹlẹ̀ẹ̀kẹrinla: Igbéraga, àti ẹtanjẹ, àti motómotó:"
3- Títúúbá níbi àwọn ohun tí a ṣe ní èèwọ̀
4- Àkólékàn awọn mùsùlùmí pẹlu lilalaafia titan ẹsin yii ká"
"Àlámàrí mìíràn ninu ìmọ Àdíísìì"
"Lẹ̀yìn náà :"